# AWON EKO

## *ILE EKO OJO ISINMI*

## FUN ODUN 2026

### OSU IKINNI SI IKEJILA

*Ti a te jade lati*

**EKA ILE EKO OJO ISINMI**

*Ti*

**IJO METALOKAN MIMO ONIHINRERE L'AGBAYE**
*OKE-IBAPON, OTITOJU, P. O. BOX 37,*
*OGBOMOSO, OYO STATE.*
*NIGERIA.*

*GBOGBO ETO ATI ASE LORI IWE YI JE TI*

**IJO METALOKAN MIMO ONIHINRERE L'AGBAYE**
***(THE HOLY TRINITY GOSPEL CHURCH, WORLDWIDE)***

*Enikeni ko gbodo te tabi ko*
*ohunkohun jade ninu iwe yii lai gba*
*ase lowo awon ti o te iwe yi jade.*

**I S B N: 978-978-59740-2-7**

*A te iwe yi lati ile-ise:*

**RUTH ADIGUN TRINITY PRINTERS**
**Along Ikoyi/Igbeti Road, Beside Jesu O Seun House,**
**City Area Ogbomoso, Oyo State, Nigeria.**

**☎:-** 08034758079, 07066246368.

# ITOKASI


| | | | OJU EWE |
|---|---|---|---|
| **ORO AKOSO** | | | **iv** |
| **ORO ISAAJU LORI IWE ESEKIELI** | | | **v** |
| **OSU KINNI** | | | |
| **EKO** | **DEETI** | **AKORI** | |
| 1 | 4 | Ipe Esekieli ati iran ibere | 1-3 |
| 2 | 11 | Iran awon Eda Alaaye | 3-4 |
| 3 | 18 | Yiyan si ise Esekieli | 5-6 |
| 4 | 25 | Je, ki o si soro | 7-8 |
| **OSU KEJI** | | | |
| 5 | 1 | Alore | 9-11 |
| 6 | 8 | Sise afihan idoti Jerusalemu (I) | 11-12 |
| 7 | 15 | Sise afihan idoti Jerusalemu (II) | 13-14 |
| 8 | 22 | Iparun Juda (I) | 14-16 |
| **OSU KETA** | | | |
| 9 | 1 | Iparun Juda (II) | 16-17 |
| 10 | 8 | Asotele si awon oke Israeli | 18-19 |
| 11 | 15 | Ibinu Olorun lori Israeli | 20-21 |
| 12 | 22 | Idajo Olorun si awon Eniyan naa | 21-23 |
| 13 | 29 | (ISIN IMO-OPE) Omo Ketekete titun kan | 24-25 |
| **OSU KERIN** | | | |
| 14 | 5 | (ISINMI AJINDE) O ti jinde! Ji Igbagbo re dide | 26-28 |
| 15 | 12 | Irira loju Olorun | 28-30 |
| 16 | 19 | Mase duro de ojo idajo ki o to ronupiwada | 30-31 |
| 17 | 26 | Iran Ologo ti a fi han Woli Esekieli | 32-33 |
| **OSU KARUN** | | | |
| 18 | 3 | Ninu Egbe awon eniyan buburu tabi ti awon eni Iwa-bi-Olorun | 33-35 |
| 19 | 10 | Oluwa nba awon tire wi | 36-37 |
| 20 | 17 | Kiyesi ikilo Olorun | 37-39 |
| 21 | 24 | Awon ami idajo Olorun | 39-41 |
| 22 | 31 | Ewu ikegan oro Olorun | 42-43 |
| **OSU KEFA** | | | |
| 23 | 7 | Idajo Olorun lori awon woli eke | 44-46 |
| 24 | 14 | Idajo Olorun lori awon woli eke obinrin | 46-48 |
| 25 | 21 | Awon Alagabangebe Elesin | 48-50 |
| 26 | 28 | Idajo Olorun daju lori Juda | 50-53 |
| **OSU KEJE** | | | |
| 27 | 5 | Igi Ajara ti ko wulo | 53-55 |
| 28 | 12 | Ekun rere oore-ofe Olorun | 55-57 |
| 29 | 19 | Aya Alaisooto | 57-59 |
| 30 | 26 | Idajo ati imupada sipo Aya Alaisooto | 59-61 |
| **OSU KEJO** | | | |
| 31 | 2 | Oluwa re agberaga sile | 61-63 |
| 32 | 9 | Oluwa gbe onirele ga | 63-65 |
| 33 | 16 | Awon Baba ti je eso ajara kikan, ehin awon omo si kan | 65-66 |

| | | | |
|---|---|---|---|
| 34 | 23 | Ayanmo wa, wa lowo wa | 67-68 |
| 35 | 30 | Pipohun-rere ekun fun awon adari Israeli | 69-70 |
| **OSU KESAN** | | | |
| 36 | 6 | Olorun safihan okan re fun awon olusewadi | 71-73 |
| 37 | 13 | Israeli kegan awon ilana at'orun wa | 74-77 |
| 38 | 20 | Bi awon Obi; bee ni awon Omo | 77-81 |
| 39 | 27 | Yiyan Israeli lati dabi awon orile-ede miiran | 81-84 |
| **OSU KEWA** | | | |
| 40 | 4 | A o mu Israeli pada bo sipo | 85-88 |
| 41 | 11 | Idajo nipa ina ati ida | 88-92 |
| 42 | 18 | Olorun ti o n binu pelu ida pipon ati didan | 92-96 |
| 43 | 25 | A kede ese Jerusalemu ati ijiya ti yo te le | 96-99 |
| **OSU KOKANLA** | | | |
| 44 | 1 | A ko ri enikan ti o ye lati duro niwaju Olorun fun Israeli | 100-103 |
| 45 | 8 | Awon ibalopo ailola ati aito ti Ahola ati Aholiba ati ijiya won | 104-106 |
| 46 | 15 | Kiko Olorun sile Juda ati Jerusalemu ati awon abayorisi re | 107-109 |
| 47 | 22 | A kede idajo lori Ahola ati Aholiba | 109-111 |
| 48 | 29 | Ibere idoti / idojuko Jerusalemu | 111-113 |
| **OSU KEJILA** | | | |
| 49 | 6 | Iku iyawo Esekieli | 113-115 |
| 50 | 13 | Idajo awon Orile-ede ti o je ibatan Israeli | 115-117 |
| 51 | 20 | Iroyin ayo ninu Papa itoju Eranko | 117-118 |
| 52 | 27 | Idajo Orile-ede ti o je ibatan ati eyi ti o wa ni agbegbe | 119-120 |

# *Admission! Admission!! Admission!!!*

## FOR EXCELLENCE IN LIFE AND MINISTRY

*attend*

# TRINITY COLLEGE OF THEOLOGY

**AROJE, OGBOMOSO.**

***Where Education is Bible-based, Research-integrated, God-centered, Love, Motivated and Holy Spirit - Empowered.***
***We balance Academic Brilliance with Spirituality.***

## PROGRAMMES

* Certificate in Evangelism & Mission
* Certificate in Church Leadership
* Certificate in Ministerial Studies
* Certificate in Religious Education
* Certificate in Theology

* Diploma in Evangelism & Mission
* Diploma in Church Leadership
* Diploma in Ministerial Studies
* Diploma in Religious Education
* Diploma in Theology

* Bachelor of Ministerial Studies
* Bachelor of Religious Education
* Bachelor of Missiology
* Bachelor of Theology

* Post Graduate Diploma in Theology

***For more information visit:***

* The College Campus at Aroje, Ilorin Road, Ogbomoso.

* The Holy Trinity Gospel Church Worldwide, General Headquarters,
  Oke – 'Bapon, Otitoju, Ogbomoso.

* Any of The Holy Trinity Gospel Church Worldwide branch nearest to you
  or call : +2348062383033, +2349020410800, +2348062269040

* E-mail: trinitycollegeoftheology94@gmail.com
  Website: www.thtgc.org

# ORO AKOSO

Ogo ni fun Olorun fun awon ohun nla ti o ti se. Adupe lowo Olorun ti O fun wa ni anfani miran lati ni awon eko fun ile eko ojo isinmi titun fun odun yi. A fe mo riri awon onkowe ile eko ojo isinmi wa, ti won fi ise naa kun ise olusoagutan, olukoni ati awon ise miran ti o yato si ise iranse. Sibe, won tun le fun wa ni awon akosile ti o ba igba mu pelu iwadi ti o to. Ki Olorun rere bukun won ni Oruko Jesu Kristi.

A ko le saimo riri eyin olukawe wa fun ifowosowopo ati atileyin yin ninu adura, imoran, ati rira awon iwe naa lododun bi o ti le je wipe o le owo nitori bi oro aje wa se wa lowolowo ati bi ohun gbogbo se gbe owo lori. Adura wa ni wipe ohun gbogbo yio dara ni Naijaria ati gbogbo agbaye. Eyin ara, a ro yin lati ma rewesi ninu ife ati ifowosowopo yin. E jowo, e maa fi awon imoran rere ninu ife yin sowo si wa. Igbagbo wa ti o le koko ni wipe, eyi yio mu ki awon eko ile eko ojo isinmi wa ma dara si, so eso rere ati ki o si ma ba awujo wa mu, beeni yio si ma wulo fun idagbasoke orile ede wa.

Iwe ti Olorun fi si okan Eka Ile Eko Ojo Isinmi, ti Ile Ise Iranse ti Eto Eko Kristiani Ijo yi ni iwe Woli Esekiel. A maa ko abala akoko ni odun yi, nigba ti a o pari abala ikeji ni odun ti o nbo. Ni afikun, a ni awon eko meta pataki lori; Isinmi Imo Ope, Ajinde ati Isinmi Keresimesi. L'apapo, a ni eko mejile l'aadota, pelu Bibeli kika ojoojumo ati awon akori ninu iwe yi.A pese re ni ona ti eko ati emi lati ba awon aini wa pade ninu odun yi. A gbodo ka won, pelu ijosin, pelu oye eko ijnle ati akoko.

Iwe Esekieli da lori iparun Jerusalemu ati imupadabosipo re. Woli yi saba ma nse agbekale isotele re nipa lilo apejuwe ati owe. Nitorinaa, o gbodo ka iwe re pelu awon akosile iwadi awon onkowe wa ti won ko sile ninu iwe Ile Eko Ojo Isinmi, ki o le ran wa lowo lati ni oye awon eko naa. A ni oro akoso lori iwe Esekiel ni erefe ninu iwe yi, a ro awon Oluko ati awon akeko lati kaa, lati mu ki imo won gbooro ninu eko ijnle nipa Olorun ati Bibeli. E se, ki e di alabukun fun ni oruko Jesu Kristi. Amin. Alaafia ni fun yin.

***Ti yin ninu Kristi,***

**THE RTD REVD E.O. AJADI**
**THE REVD DR. S.O. OLAJIDE**
**THE REVD I.O. ADISA**
**THE REVD DR. J.J. ISAAC ZOKRO**
**THE REVD DR. S.I. ASOKERE**
**THE REVD S.A. ALABI**
**THE REVD DR. J.O. OLANLEGE**
***Fun: Eka Ile-Eko Ojo Isinmi***

# ORO ISAAJU LORI IWE ESEKIELI

**ONKOWE:**
Onkowe, ti oruko re tumosi ‘‘Olorun nro L’agbara’’ ni a mo si Esekiel alufa, omo Busi’’ (1:3). O see ki o je alufa ti idile Sadoku ti o di olokiki ni akoko akanse ise atunse Josiah. (621 B.C.) O ko eko re gege bi alufa ni akoko ijoba Jehoiakimu, ti a ko lo igbekun Babiloni ni 597BC, o si tedo si Tel Abib leti odo Kebari, li egbe Nippuri. Ise iranse re je akoko kan naa pelu ise iranse Jeremiah.

**DEETI/AKOKO TI A KO IWE NAA:**
Ipe Esekieli wa ni 593 B.C., ti nse odun karun ijoba Jehoiakini. Odun ti o gbeyin ti a fun isotele re ni nkan bi 571 B.C. eyi ni o mu ki ise iranse je nkan bi ogun odun. Iku iyawo re waye ni nkan bi akoko naa pelu iparun Jerusalemu ni 587 B.C. A ko o ni igbekun ni igba idoti ikeji Jerusalemu,o ko iwe yi si awon eniyan ti o si wa ni Jerusalemu nipa iparun patapata ti o nbo wa, pelu ikuro iwa laaye Olorun laarin won. A si ko awon abala kan nigba ti ati pa Jerusalemu run patapata.

**AWON EKO INU IWE NAA:**
Igbesi aye Esekieli se afihan tito leseese ohun ijinle. Ona iba pade kiakia re pelu emi, awon iran re, ati oro Oluwa loore koore se asopo pelu awon woli alakatakiti ti aye atijo ati awon ti aye igba ti re ti won k’owe. Awon iriri ti emi re se afojusun ise Emi Mimo ninu Majemu Titun. A lee pe akori re ni ‘‘ alakatakiti’’.
Esekieli doju ise iranse re ko awon iyoku Judah ti igbekun Babiloni ti so di alailagbara. Ojuse enikookan lati je mimo ni akori akoko ise iranse re. Ojuse apapo ko daabo bo enikookan mo. Enikookan gbodo gba wipe oun ni o fa laasigbo ti o de ba orile ede. Enikookan ni o je okunfa ese ara re. Akojopo awon ese enikookan ni o se okunfa yiye majemu Olorun pelu awon Israeli, ti won si pin ninu idalebi ti o yorisi idajo ikolosi igbekun ni Babiloni.

A pin iwe naa si ona meta: Idajo Judah (ori 4-24), Idajo orile ede keferi (ori 25-32), ati ibukun ojo iwaju fun awon eniyan majemu Olorun. (ori 33-48).
Bi o se nka iwe Esekieli, kaa pelu ipongbe okan, iwo yio si di alabukun fun ni oruko Jesu. Amin.

**JANUARY 4, 2026** **EKO 1**

# IPE ESEKIELI ATI IRAN IBERE

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 1:1-14*

***ESE AKOSORI:-*** *"… bi mo ti wa laarin awon igbekun leti odo Kebari, orun si, mo si ri iran Olorun'' (Esekiel 1:1b)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 29/12/2025 | Papa ti o njo | Eksodu 3:1-4 |
| Ojo Isegun | 30/12/2025 | Ipe Nitori Awon ti ani lara | Eksodu 3:5-9 |
| Ojoru | 31/12/2025 | Olupeni Nla | Eksodu 3:10-14 |
| Ojobo | 1/12026 Ipe | Gege bi Woli | Jeremiah 1:4-10 |
| Ojo Eti | 2/1/2026 | Kini Iwo ri? | Jeremiah 1:11-19 |
| OjoAbameta | 3/1/2026 | Awon eda alaye bi eniyan | Esekiel 1:1-7 |
| Ojo Aiku | 4/1/2026 | Awon eda alaye ti oju won yato | Esekiel 1:8-14 |

## ORO AKOSO

Oluwa feran awon omo Isareli, sugbon, o seni laanu wipe, won ko feran Re. Awon eniyan Israeli je alaigboran si Olorun, beeni won si da ese. Olorun ti so lati enu awon woli bi apeere; Amosi, Hosea, Isaiah, Jeremiah ati bee bee lo wipe, ti won ba tesiwaju ninu ese won ti won ko si gboran si Oun, won yio ko won lo si igbekun fun awon akoko kan (II Awon Oba 17:7-23). Sugbon, ni opo igba, awon eniyan naa ko ronupiwada, ki won sii yipada si I. (II Awon Oba 21:3-7). Nitorinaa, a ko awon eniyan ti ijoba Ariwa lo si igbekun ni odun 722 BC lati owo awon ara Assiria. A o maa ro wipe, o ye ki awon eniyan ti ijoba Gusu ko eko lara awon igun keji won, sibesibe, won tun tesiwaju ninu awon ese won. Ni odun 612 BC, Ninefe ti nse olu ilu Assiria subu si owo Babiloni. Nebukadnessari,saaju awon omo ogun re lati gbogun ti Jerusalemu ni akoko ijoba Jehoiakimu (Eliaimu). O fi ipa mu won lati san owo ori, sugbon won ko. Nitori idi eyi, o ko lara awon ohun elo mimo ninu Tempili lo. A ko Danieli ati awon ojogbon ni aafin lo si igbekun ni odun 606 BC, eyi ti nse ibere aadorin odun ti Jeremiah sotele nipa re.Awon eko wa ninu iwe Esekieli se akosile bi ikonigbekun lo si Babiloni ikeji ati iketa ti sele ni akoko Jehoakini (odun 597 B.C.) ati Mattani'ah (ti ayi oruko re pada si Sedekiah) ni odun 586 B.C. Awa naa mo wipe, Olorun feran wa ni iran yii, sugbon , O korira ese. Nigbakugba ti a ba gba ese laaye lokan wa, a nsi aye wa sile fun ewu ati ikoleru lati owo esu ati awon omo ogun re. Nitorinaa, ronupiwada nisisiyi, nitori iku ni ere ese. (Romu 6:23).

## EKO

**I. ORISUN ESEKIELI ATI IPE RE - 1:1-3**

**(a) Orisun Esekiel – ese 1a, 2, 3b**

A bi Esekiel lati inu idile Alufa ni Jerusalemu, ayanmo re ni lati maa sise ninu Tempili. Oruko Baba re ni Busi (ese 3a). O wa ninu awon ti a ko lo si igbekun ni Babiloni ni odun 597 B.C. O sese ki o wa lara awon ti a kolo ni egbe keji, nigba ti Daniel ati awon Heberu meta wa ni egbe akoko. Ibi ti o wa ninu igbekun ni ile awon ara Kaldea ni leti odo Kebari.Ibi yi je agbegbe Gusu Mesopotamia. Ni aye ode oni, ibe ni a npe ni Shatt en-Nil tabi Khabur (1 Chron, 5:26), ti o je isan omi ti o ya kuro lara odo Eufrate ti o si san lo si Nippuri ni Iraq. Bi o tile je wipe, o seese ki Esekiel ma da ese kankan, sugbon ese orile ede re se akoba fun un. Awon obi ati adari awujo gbodo kiyesara lati ma ko awon eniyan won sinu iyonu.Ti o ba si ba ara re ninu ikorita ti o ko fe, mase ko Olorun re sile gege bi Esekieli ti se, yi o fa o jade fun ise pataki kan.

**(b) Ipe Esekieli - ese 1e, 3a, e**

Nigba ti o wa ni igbekun, leti odo Kebari, o gba ipe lati je woli ni omo ogbon odun, ni ojo ikarun, osu kerin ni odun 593 B.C.O je odun kaarun igbekun Jehoiakini oba. Ipe re wa nipa awon orun ti o si, beeni o si ri awon iran Olorun. (ese1e) Oro Oluwa to o wa. (ese 3a), ati wipe owo Oluwa si wa lara re (ese 3e). O han gbangba wipe , o ni eko obi ati orisun ti o dara gege bi omo Alufa. De bi wipe, ninu igbekun, o gba ipe gege bi woli si awon orile ede. Awon omo ile iwe wa, ni ile iwe, gbodo ko eko lara re. Nigba ti awon kan di olusoagutan nile iwe, awon kan di elegbe okunkun. Tani o nigba ti o ko ba si labe awon obi re? Gbogbo wa gbodo sun mo Olorun ni akoko awon ipenija, ki a ba lee jinle ninu Re.

**II. IBERE IRAN ESEKIELI - 1:4-14**

Esekieli ri iran aja (iji) lati inu awosanma ti o jade wa lati ariwa. Laarin iji onina merin naa ni awon eda alaaye ti o ni iye wa.Okokan won ni abuda eniyan ati eranko(won dabi awon orisa kekeke ti a ya aworan won ni iha ila oorun atijo) ese 4-5. Apejuwe awon eda alaaye merin yi bani leru pupo. Won ni oju merin (oju eniyan, kiniun, maalu, ati idi, ese 10) iye merin (ese 11),ese won si too, atelese won si dabi atelese omo maalu, won si ni owo eniyan labe iye merin won. (7-9). Beeni, iye won si kan ara won; nwon ko si yipada nigbati nwon lo, olukuluku won lo li okankan taarata. Ni aarin awon eda alaaye wonyi ni kini kan wa ti o dabi ese ina, ati bi iri ina fitila, ti o nlo soke, ati sodo, ti o si mole, ati ti o si nko bi manamana. Iran yi tumo si ifarahan awon eda orun tabi angeli ni aworan eniyan,eranko ati eye. Olorun lee lo ohunkohun lati so okan Re di mimo fun awon eniyan Re. A gbodo loye tabi wa ninu ifunra nigbati Olorun ba nba wa soro yala ninu awon iran tabi ala. A ko gbodo so wipe ala go. O le ma je taarata, sugbon, oni itumo, ma se fi sere rara.

**<u>AWON IBEERE</u>**

1. Daruko awon ipele meta ikolo si igbekun ni Babiloni lati owo Nebukadnessari
2. Se alaye orisun Esekieli.
3. Bawo ati nibo ni ati pe e?
4. Eko wo ni a lee ri ko ninu ipe re?
5. Se alaye iran ibere Esekieli ati awon eko ti a ri ko ninu re.

**JANUARY 11, 2026 EKO 2**

# IRAN AWON EDA ALAAYE

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIEL1 1:15-28*

***ESE AKOSORI:-*** *“Bi mo si ti wo awon eda alaaye na, kiyesi I, keke kan wa lori ile aiye leba awon eda alaaye na, pelu oju re merin”. (Esekieli 1:15)*

## <u>BIBELI KIKA OJOOJUMO</u>

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo aje | 5/1/2026 | Iran Okunrin Ologo naa | Danieli 10:1-9 |
| Ojo isegun | 6/1/2026 | Iran Ite Olorun | Ifihan 4:1-4 |
| Ojoru | 7/1/2026 | Awon Eda Alaaye Juba Re | Ifihan 4:5-11 |
| Ojobo | 8/1/2026 | Awon Serafu Yin In | Isaiah 6:1-5 |
| Ojo Eti | 9/1/2026 | Tani ki I nran? | Isaiah 6:6-10 |
| Ojo Abameta | 10/1/2026 | Emi awon Eda Alaaye | Esekieli 1:15-20 |
| Ojo Aiku | 11/1/2026 | Ogo Oluwa | Esekieli 1:21-28 |

## ORO AKOSO

Ninu eko akoko, a ti ni oye nipa apejuwe awon eda alaaye merin ti Esekieli ri. Apejuwe awon eda alaaye merin wonyi deru bani pupo. Won ni oju merin; ti nse; oju eniyan, oju kiniun, oju maalu, ati oju idi (ese 10). Eko naa se apejuwe ese won ati bi won se nrin. Eko wa ti oni se alaye ni ekun rere nipa awon eda alaaye naa pelu keke ti a so mo okookan won. Ifihan Olorun maa ntesiwaju ni. Ti a ba mu ibasepo wa pelu Olorun dagbasoke lai je ki o ye, Oun yio ma fi asiri ijinle han wa nipa aye wa ati ijoba Re. (Marku 4:11-12).

## EKO

### I. AWON EDA ALAAYE NAA ATI KEKE - 1:15-21

Keke nla kookan ti o jo ara won, ni o wa pelu eda alaaye kookan bi o ti nlo. Iri awon keke na ati ise won dabi awo berili; ise won dabi enipe keke li aarin keke. Keke mererin naa ni oruka (tabi agba) ati awon irin ati wipe oruka won si kun fun oju yi awon mererin ka. Ohun ti o yanilenu ni wipe, emi awon eda alaaye naa wa ninu awon keke naa, nigbati awon eda alaaye naa ba dide duro, keke naa a si dide duro pelu. A lee tumo eyi si isokan awon angeli ni orun lati je awon ise ti a ran won si enikeni ti a ran won si. A lee wa ni irepo pelu awon angeli wa tabi Emi Mimo ti o je alabarin wa, ti a ba se ife Olorun. Ojo ti o ba ti pinya pelu angeli re, ojo naa ni o ti si aye ara re si igbogun ti lati odo esu. Gege bi keke naa ti ni oju, beeni oju Oluwa nwo isise re, o si nba lo ibi gbogbo ti o ba nlo. Nitorinaa, yago fun ibi.

### II. IKUNLE TABI TITE ORI BA AWON EDA ALAAYE NAA. - 1:22- 25

Ohun kan ti o dabi awosanmo wa ni ori awon eda alaaye naa, o si ndan bi kristali, o tan ka ori won ati ni abe awosanmo ni awon iye won mejimeji na gbooro, ti okookan won si fi iye meji bo ara re.Nigbakugba ti won ba nrin, awon iye naa a maa dun bi iro omi pupo ati bi iro ara Olodumare, ohun iro bi ariwo ogun:nigbati won duro, ohun kan wa lati awosanmo si ori won; won si re iye won sile. Iran Esekieli fi ara pe ibapade ti Isaiah ni ki o to di wipe a pe e, ti a si yasoto gege bi woli. (Isaiah 6:1-8). Nitorinaa, lati pe awon eda alaaye naa ni angeli, paapaa julo Serafu, ko jina si otito rara. Gege bi awon angeli ti tu iye won ka lati sin Olorun, bakan naa ni awon eda alaaye naa se. A ko gbodo to bi ju lati fi ijosin wa han si Olorun, gege bi awon angeli ti ma nse.

### III. ITE TI O WA NI ORI AWON EDA ALAAYE NAA - 1:26-28

Ni oke awosanmo naa ni ite kan ti a fi okuta iyebiye se loso. O ri aworan eniyan kan ti o joko si ori ite naa, ti o ntan bi ina, ti itansa ogo si yii ka . Bi Esekieli se kiyesi wipe, oun ri ohun ti o duro fun ogo Olorun, o teriba, o si da oju re bole.Nitooto, Oluwa fi ogo Re han Esekieli nipa iran ati aworan ti o gbooro. Nigbakugba ti a ba ri ifarahan eda ti o ba ni leru ninu majemu lailai, o ntokasi Omo eniyan ninu Majemu Titun, ti nse Jesu Kristi. Bi o ti se bere odun titun yi, sa ipa re lati wa oju Olorun. Ma se ni itelorun, ayafi ti Jesu ba fi ara Re han o. Ayo ti o wa ninu re ni wipe, o ko le ri iran orun ki aye re wa bakan naa.Teri re ba, ki o si gbadura, Jesu! Fi ara re han mi l'odun yi.

**AWON IBEERE**

1. Bawo ni iran Olorun se nsise?
2. Kinni ohun ti o pelu awon eda alaaye bi won ti nrin lo ati pe bawo lose ri?
3. Iwe wo ni o ni iran alaworan tabi apejuwe bi ti iwe Esekieli 1:22-25?
4. Kinni ati tani Esekieli ri l'oke awosanmo?
5. Kini o ye ki o se ni odun titun?

**JANUARY 18, 2026** **EKO 3**

# YIYAN SI ISE ESEKIELI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 2:1-10*
***ESE AKOSORI:-*** *"O si wi fun mi pe, Omo enia, duro li ese re, emi o si ba o soro". (Esekieli 2:1)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 12/1/2026 | A se awari Adari titun | Deut. 31:1-4 |
| Ojo Isegun | 13/1/2026 | Je Adari ti o mu aya le | Deut. 31:5-8 |
| Ojoru | 14/1/2026 | Ise ti Olorun ran Joshua | Joshua 1:1-9 |
| Ojobo | 15/1/2026 | Ipe Awon Aposteli | Matteu 10:1-4 |
| Ojo Eti | 16/1/2026 | Ise ti a ran Awon Omoeyin | Matteu 10:5-15 |
| Ojo Abameta | 17/1/2026 | Ise ti a ran Omo Eniyan | Esekieli 2:1-5 |
| Ojo Aiku | 18/1/2026 | Eniyan ti kii nberu | Esekieli 2:6-10 |

**ORO AKOSO**

Otito ti o daju ni wipe, opolopo ni a pe, sugbon die ni a yan. Ipe laisi yiyan,dabi akeko gboye ninu imo ofin ni ile eko giga Unifasiti ti ko lo si ile iwe ofin tabi ti a ko ya soto tabi fi ase fun gege bi amofin. A ko lee pe irufe enibe ni amofin. A ko lee ri iranse Olorun gege bi iranse Olorun ni ekun rere, ti a ko ba tii yasoto si okan ninu opo ise iranse mararun, iru enibe ko ti bere ise iranse ni ekun rere. Eniyan le daba eniti o ye ki a yan, sugbon Olorun ni o ma yan an sinu ise iranse. (fun apeere; Mose ati Josua- Deut. 31:7-14) Bibeli wipe, ''OLUWA si yan Josua omo Nuni…'' (Deut. 31:23, Josua 1:1-2). Nigba miran, yiyan yi maa nwa pelu ironilagbara nipa igbowo le awon agba ninu ise iranse ati iyasoto fun ise pataki. (kaa; Deut. 34:9, Ise Awon Aposteli 13:1-3, 1 Timoteu 4:14). Olusoagutan! Talo yan o? Alagba, Diakoni l'okunrin ati l'obinrin, talo yan o?Ti Olorun ko ba yan o, awon eniyan ko ni bu ola fun o. Ninu eko wa ti oni, a fe se agbeyewo bi Olorun se yan Esekieli si ise iranse woli ni igbekun. Ikorita ti o wa ko da Olorun duro lati ba o soro, ti o ko ba ya ara re kuro lodo Re.

## EKO

### I. ISE TI A RAN ESEKIELI SI ISRAELI - 2:1-5

Oluwa gbe Esekieli dide, O si yan gege bi iranse Re tabi woli. Esekieli ni imolara wipe Emi Olorun wole sinu aye Oun, beeni o si gbo ohun Olorun. A pe ni Omo eniyan. Jesu naa pe ara ni Omo eniyan ninu Majemu Titun. (Luku 19:10). O je ege gbolohun fun eniyan ti Olorun pe, ti O si ro ni agbara ti orun fun ise iranse ti aye. Olorun fi awon ti o ran si han an gege bi; awon olote, elese, alafojudi ati orile ede olokan lile-Israeli, ti won lee yan lati ma fetisi ise iranse re. Iru ipenija nla wo ni eyi! Gege bi iranse Olorun, adari ijo ati osise ijo, okan re ko gbodo rewesi nigbati a ba ran o si; awon alaigboran, olote ati awon eniyan buburu ninu ijo ati aye. Tesiwaju, ki o si lo je ise ti Olorun ran o. Ti won ba gbo, won yio gba ere re, bi won ba si ko,won yio ri atubotan re.

### II. A MU ESEKIELI NI OKAN LE - 2:6-7

Olorun mu woli naa lokan lee lati ma beru, ni akoko ikorira ati ewu; o gbodo kede oro Oluwa , lai fi ti iha ti won ko si se. O fi han gbangba fun wipe, yio je ise iranse laarin awon eniyan bii; egun ogan, osusu ati akeeke.Ko gbodo beru. Abalajo, Jesu ran awon omoeyin re gege bi agutan si aarin awon ikoko. O gba won niyanju lati se ologbon bi ejo, ki won si je oniwa tutu bi adaba. Gbogbo iranse Olorun, awon adari ijo ati osise ijo; fun apeere; Awon alagba, Diakoni l'okunrin ati l'obinrin, adari egbe, awon akorin, awon asona, awon oluko ile eko ojo isinmi gbodo mo wipe, ako lee fe awon iko emi okunkun ku ninu ijo.

Nitorinaa, won ko gbodo beru won, bikosepe ki won ro ara won ni agbara Emi Mimo. (Filippi 1:28, 2 Timoteu 1:7, Efesu 6:10 siwaju) Nigbamiran, leyin ti o ti se laala ninu ise iranse, ti ko si mu esi ti o dara jade, ma se pa ara re, saa ri daju wipe o je olooto si Olorun. Tesiwaju ninu gbigba aawe ati adura fun won; Olorun lee yan lati yi won pada.

**III. A KI ESEKIELI NILO - 2:8-10**

Olorun gba Esekieli ni iyanju lati ma darapo mo awon olote, ese 8. Dipo bee, ki o ya enu re ki o si je iwe kika kan ti a fi fun un. Olorun pase fun un ki o je iwe kika kan ti o kun fun oro ohun-rere-ekun, ofo ati egbe. Oluwa so fun Josua wipe; ‘‘Iwe ofin yi ko gbodo kuro li enu re, sugbon iwo o ma se asaro ninu re li osan ati li oru, …’’, (Josua 1:8 se afiwe pelu 1 Timoteu 4:13-16). Lati je iwe kika naa lee tumo si; lati ka ati lati se asaro ninu oro Olorun , titi ti yio fi di omi, eje ati ara wa. O seni laanu loni wipe awon agba ati odo pelu awon ewe ko ka oro Olorun si.Ero ayelujara ti gba ipo oro Olorun ninu okan wa. Aniyan aye ti fun oro naa pa ninu okan wa. E jeki a ronupiwada!O gbodo je eje lati je oro Olorun nipa kika gbogbo iwe inu Bibeli patapata ninu odun yi. Otito ni wipe, Bibeli ni awon oro; fun eko, fun ibaniwi ati fun itoni ti o wa ninu ododo (2 Timothy 3:16) pelu awon egun ati ibukun (Jowo kaa; Deut. 28). A gbodo ka gbogbo re nitori wipe o ni ete ti a fi koo sile.

**AWON IBEERE**

1. Bawo ni yiyan se se pataki to?
2. Awon wo ni a ran Esekieli si?
3. Bawo ni Olorun se mu ni okan le?
4. Awon eko wo ni a lee ko lati inu “A mu Esekieli ni okan le’’?
5. Awon eko wo ni a lee ko lati inu “A Kilo fun Esekieli’’?

**JANUARY 25, 2026** **EKO 4**

# JE, KI O SI SORO

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 3:1-11*

***ESE AKOSORI:-*** *“Pelupelu o wi fun mi pe, Omo enia, je ohun ti iwo ri, je ika-iwe yi, si lo ba ile Israeli soro”. (Esekieli 3:1)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 19/1/2026 | Olorun ni oro naa | Johannu 1:1-5 |
| Ojo Isegun | 20/1/2026 | Mimo Iwe Mimo | 2 Tim. 3:10-17 |
| Ojoru | 21/1/2026 | Waasu Oro Naa | 2 Tim. 4:1-5 |
| Ojobo | 22/1/2026 | Di Oro naa mu sisin | Filippi 2:12-18 |
| Ojo Eti | 23/1/2026 | Nje Oro naa gbe inu re? | Kolosse 3:12-17 |
| Ojo Abameta | 24/1/2026 | Je Edidi naa | Esekieli 3:1-6 |
| Ojo Aiku | 25/1/2026 | Ile Olote | Esekieli 3:7-11 |

**ORO AKOSO**

O je oro to gbajugbaja wipe, o ko lee fun eniyan ni ohun ti o ko ni. Nigbati o rorun fun awon Kristiani kan lati so ori ati ese Bibeli sori bi o ti wa ninu Bibeli tabi ki won pee so, awon miran ko lee se iyen nitori oro naa ko si ninu won bikose aye. Iran tabi ise iranse ti Olorun fun Esekieli je nipa aworan tabi ona owe. O je iyalenu, Olorun pase fun wipe ki o je ika-iwe, ki o si fi kun inu re. Esekieli gbodo ri ara re sinu oro Olorun, ki o si je ki awon oro naa kun inu re pelu otito ti o dabi ina ki o to di wipe yio jade lo lati lo so oro

naa fun awon olote eniyan eniyan.Kini a npe ni ika-iwe?Ika- iwe je awo tabi iwe ti a ka fun kiko awon ohun kan sinu re.O je irufe iwe kan ni akoko Bibeli. A ti lo ni Egipti ni igba atijo, alakoko iru e ni a fi papirusi se, iru awon iwe ti o nipon bi eyi ti a fi n nu'wo ni a fi iru awon igi ti o dagba ni Nile se. Lai de na penu, osese lati je ika-iwe. Jije ika-iwe ninu bibeli je oro akanlo ede, ki se wipe eniyan ma dede mu ika-iwe ma je lenu ni. Ninu eko wa yi,ika-iwe je oro aropo oruko fun Oro Olorun ni.

## EKO

**I. KI NI OLORUN SO WIPE KI O JE?**
**- 3:1-**3

**(a) Omo eniyan**

Olorun pe Esekieli ni omo eniyan. Eyi je apejuwe oro aponle pataki ti a ama nlo fun awon woli ni majemu lailai. Jesu fun'rare lo apejuwe yi lati pe ara re nigba ti o wa ni aye. Eyi yi fun awon eniyan ti abi sugbon ti a ti yawon si oto pelu ifami oroyan fun ise Olorun. Awon iranse Olorun je eniyan bi ti wa, sugbon, a ni lati bowo fun ifami oroyan Olorun lori aye won eyi ko ni fi se pelu ojo ori.

**(b) Ika-Iwe**

Olorun pase fun woli Esekieli ki o je ika-iwe eyi ti o ri ni. Ni aisi ani ani, o mu si enu re, o si je.ki se pe oje niwonba, sugbon o je gbogbo re. O ni lati je titi inu re yio fi kun,woli Esekieli si se be. Ika-iwe na si dun ni enu re bi oyin. Ika-iwe na duro fun oro Olorun ati ohun ti Olorun ni fun awon eniyan re. Awa gege bi kristieni, a ni lati ma se asaro ninu oro Olorun ki a si fi kun okan wa. Sugbon, o je ohun ti o se ni lanu lode oni, orin aye, awon ere agbelewo ni opolopo kristieni ati awon odo wa n poungbe fun. Se iwo naa ti je oro Olorun? Bi woli Esekieli se gboran, gbogbo iranse Olorun ati awon omo ijo gbodo gboran si Olorun yala o bawalaramu tabi ko ba wa lara mu laisi ikunsinu.

**II. KINI OLORUN NI KI O SE LEYIN IGBA TI O JE IKA-IWE NAA? - 3:4-**6

Olorun pase ki o so oro ika-iwe ti o je fun awon eniyan re, awon ara ile Israeli. A ko ran si awon eniyan ajeji ede tabi awon ti ko gbo ede won. Jesu naa ran awon omo eyin re ni iru ise yi ni iwe Matteu 10:1-6ff. Gege bi kristieni, awon molebi wa ni akoko ran wa si. Olorun seun pe o wulo fun ijo re, sugbon iyawo ati awon omo re n ko ? Ko si aseyori ninu wipe o lo si ijoba Olorun ki awon molebi re lo si orun apadi. E je ki a dekun lati maa se agabagebe, ki akoko to awon molebi wa lo naa, ki a to to awon aladugbo wa lo. Awon ti o wa ninu ijo gbodo koko di eni igbala ki a to wasu fun awon ti o wa ni ita.

**III. KINI IHA TI AWON ENIYAN RE KO SI EYI ? - 3:7-11**

O je ohun ti o banilokan je wipe Olorun so pe awon ara ile Israeli ki yio gbo nitori won je olokan lile, ati alagidi. Sibe,Olorun ru Esekieli soke lati lo jise ti Oun ran. A si ti pa lase fun wa lati lo wasu ihinrere bo ya awon ti a nwasu re fun gbo tabi won ko gbo.( 2 Timoteu 4:1-5) bi o ti je pe, won gbo sugbon won ko lati yipada, awa bo lowo idalebi ati ebi eje won. Sugbon,bi a ko ba jise ti Olorun ran wa bi won ba ku sinu ese won, Olorun yio bere eje won lowo wa. E yi gbodo je eko fun awa ti a fi ise ijere okan ran, ki nse gbogbo awon ti o gbo iwasu ni won yo yi pada lesekese tabi pelu irorun.

**AWON IBEERE**

1. "A ko le fun eniyan ni ohun ti a ko ni", ba wo ni eyi se se pataki si ninu eko wa ti oni?
2. Gegebi ayoka wa ti oni, ki ni itumo ika-iwe ?
3. Ki ni ika-iwe duro fun ati pe ki ni a o

se pelu re?
4. Bawo ni o se se pataki to ki awon molebi wa di eni igbala?
5. Iha wo ni awon eniyan ko si oro woli Esekieli ati wipe kini a le ko ninu eyi?

**FEBRUARY 1, 2026 EKO 5**

# ALORE

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 3:12-27*
***ESE AKOSORI:-*** *"Omo eniyan, mo ti fi e se Oluso fun ile Israeli, nitorina gbo oro li enu mi, si kilo fun won lati odo mi wa". ( Esikieli 3:17)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 26/1/2026 | Olorun Ni Oro Na | John 1:1-5 |
| Ojo Isegun | 27/1/2026 | Mi Mo Iwe Mimo | 2 Tim. 3:10-17 |
| Ojoru | 28/1/2026 | Waasu Oro Na | 2 Tim. 4:1-5 |
| Ojobo | 29/1/2026 | Didi Riru Soke Nipa Emi Mimo | Esekieli 3:12-15 |
| Ojo Eti | 30/1/2026 | O Je Alore Si Awon Eni Buburu | Esekieli 3:16-19 |
| Ojo Abameta | 31/1/2026 | O Je Alore Si Awon Olododo | Esekieli 3:20-23 |
| Ojo Aiku | 1/2/2026 | Itoni Lati Odo Emi Mimo | Esekieli 3:24-27 |

**ORO AKOSO**

Alore je eniti ise re ni se pelu siso ile tabi ohun ini, paapaa ni ale tabi ti eni toba ni ohun ini naa ko ba si ni ile. A tun ma npe won ni olode, tabi onibode. Ni ilana esin igbagbo, alore je eni ti o gba oro ati ikilo lati odo Olorun fun awon eniyan re. Ninu bibeli, a ma nsaba se apejuwe alore bi eniti o ma duro si ori oke ile lati le ma sona fun ewu tabi ikolu awon ota, bo ya nipa ti ara tabi nipa ti emi. Won le je iranse Olorun, ni pataki eniti o ma gba oro lati odo Olorun lati so fun awon eniyan re. Ojuse won pataki ni lati bojuto idagbasoke emi awon eniyan Olorun ati lati kilo fun won nipa awon nkan ti Olorun ko fe. A yan Esekieli lati je alore fun ile Israeli ni igbekun. Ipe re wa fun siso won ati lati ma kilo fun won, sugbon se won o gbo ? A pe awon iranse Olorun ati awon ti o njere okan gege bi alore lori wa, nje a ngboran si won lenu? Otito ibe ni wipe, ewu ati ijamba ko ni dekun ni awujo wa, ti a ko ba gboran si awon alore wa lenu.

**<u>EKO</u>**

**I. IBAPADE AT'OKE WA TI ALORE**
**NAA. - 3:12-15**

Esekieli gburo ogo lati orun wa. O si gbo ohun ariwo iye awon eda alaye gegebi ati so ni awon eko wa ti o koja, wipe o nkan ara won. Ati ariwo awon keke ti o wa pelu won, ati ariwo iro nla ti n mi ile. Beni emi na gbe soke, o si mu kuro ni ibanuje ati ni gbigbona okan, owo Oluwa si le lara re. Leyin ibapade yi pelu Olorun, ni o to awon ti igbekun Telabibi lo ni Babiloni, ti won ngbe eba odo kebari. Nibe ni o si joko pelu won ni idakeje pelu iyanu fun ojo meje. Eyi je iriri pataki fun awon woli, awon onidajo, alufa, ati awon oba ni majemu lailai. Iriri yi kanna ni awon Kristieni akoko ninu majemu titun ni ni ojo penticosti. (Ise Awon Apos. 2:1siwaju).Iru ibapade at'oke wa yi ni yio dari wa si ibi ti Olorun fe ki a lo gan fun ise iranse wa, bo ya ni igboro tabi ni abule. Ti a ba si dari wa si ibikibi yala ni iju, ki a ri wipe a duro fun itoni emi mimo ki a to bere ohun kohun.

## II. ISE AKANSE AT'OKEWA FUN ALORE - 3:16-21

### (a) Diduro Ati Gbigbo –vs 16-17

Leyin igba ti woli Esekieli duro ninu Olorun fun ojo meje, oro Olorun to wa. Olorun jeri si ise ranse re gegebi alore. Ise re ni lati ma gba ikilo lodo Olorun fun awon eniyan re, awon omo Israeli. O di dandan fun awon kristieni, ni pataki awon iranse Olorun lati ni akoko ti won fi ma nduro de Olorun. Enikeni ti o ba kugburu tabi sare wo inu ise iranse lai gba itoni lowo Olorun yi o ba ijakule pade.

### (b) Ise Akanse At'Okewa fun Awon Eniyan Buburu - ese 18- 19

A fun woli Esekieli ni ise ti o ni baa ninu, nitori Olorun sope, ti oun ba ran si eniyan buburu, "wipe kiku ni oun yio ku"ese 18, ti o si kuna lati so fun irufe eniyan be lati yipada kuro ni ona buburu re ki o si ye, eniyan na yio ku ninu ese re, sugbon eje re ni a o bere lowo Esekieli. Ni ona keji ewe, ti o ba kilo fun eni na, lati yipada kuro ninu ona buburu re ki o si ye, sugbon ti eniyan na ko lati yipada kuro ninu iwa buburu re, eniyan na yio ku ninu ese re Esekieli ki yio si gba idalebi (ese 19). Olorun n fe ki a wasu ironupiwada fun awon eniyan buburu nitoripe inu re ko dun si iku elese, ti a ba wasu fun eniyan buburu bi won ko si yipada, won yio segbe a ki yio si bere eje won lowo wa. Bi a ko ba wasu fun won, sugbon ti won ba ku, a jebi eje won. E je ki a mu ero ti a ni nipa awon eniyan kuro, ki a si lo wasu fun awon ara ile wa, awon ara adugbo wa, o se se ki won ki o ronupiwada ki won si pada wa jasi ibukun fun awa na.

### (d) Ise Akanse At'okewa Si Awon Olododo - Ese 20- 21

A ran woli Esekieli si awon olododo na ki won ki o mase bo sinu ese, nitoripe, ti olododo ba pada sinu ese, ti o si ku, a o si gbagbe gbogbo iwa ododo re. Ti woli Esekieli ba ko lati kilo fun olododo, a o bere eje re lowo woli Esekieli.Sugbon ti o ba kilo fun olododo na ki o ma da ese mo , yio si ye, nitori ti o gba ikilo. Woli na yio si gba ara re la. Ara, e je ki a je alabojuto awon arakunrin wa. Eniti o je olododo le pehinda nitori isoro aye ti ko ba ri eni too sona. E je ki a tubo ma farada ipenija wa nitori ogo eyi ti a gbee kale niwaju wa. O san ki eniyan ku sinu isoro re ki o lo ijoba Olorun, ju ki o ye , ki o wa pada lo si orun apaadi leyin igba ti o ba ku tan. (Orin Daf. 34:19, 125:3, Johanu 16:33, 14:1-4, Romu 8:18, Kol. 1:27).

## III. IRIRI TI O LE TI ALORE DOJUKO - 3:22-27

Ko pe ti o je ise na ni a gbe gbedeke le. Woli Esekieli ko ni ominira lati se ikilo nibiti o wu lati se ise naa. Olorun pa lase fun ki o wo inu ile re lo, nibiti yio duro ti ko si le soro. Ayafi ti Olorun ba so fun pe ki o soro, tabi ki o jade nikan lo ku. Gbedeke yi yio je eko pataki fun awa omo Olorun wipe iwa ipa wa je ohun idena tabi idiwo fun un lati ba wa soro. Gege bi alore, a ni lati ko, lati mo igba ti o ye ki a soro. Nitori awon eniyan le padanu ore ofe Olorun ki won ki o si dojuko ibinu Re. Nitorina ronupiwada nisisiyi!

## AWON IBEERE

1. Tani alore ?
2. Se apejuwe ibapade at'okewa ti alore naa. (Esekieli)
3. Kini ise at'oke wa ti a ran woli Esekieli si awon eniyan buburu ?
4. Kini ise atoke wa ti a ran woli Esekieli si awon olododo ?
5. Kini awon eko ti o ko ninu idanileko wa ti oni yi?

**FEBRUARY 8, 2026** **EKO 6**

# SISE AFIHAN IDOTI JERUSALEMU (I)

***BIBELI KIKA:-*** *EZEKIEL 4:1-8*

***ESE AKOSORI:-*** *"Iwo, omo eniyan, mu awo kan, ki o si fi si iwaju re, ki o se aworan Jerusalemu sinu re". (Esekieli 4:1)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 2/2/2026 | Igbese Sinu Isegun 1 | Joshua 6:1-5 |
| Ojo Isegun | 3/2/2026 | Igbese Sinu Isegun 2 | Joshua 6:6-10 |
| Ojoru | 4/2/2026 | Nomba Ikeje | Joshua 6:11-15 |
| Ojobo | 5/2/2026 | Igbe Isegun | Joshua 6:16-21 |
| Ojo Eti | 6/2/2026 | Isubu Jerusalemu | Jeremiah 39:1-10 |
| Ojo Abameta | 7/2/2026 | Tabili Amo | Esekieli 4:1-4 |
| Ojo Aiku | 8/2/2026 | A se Idoti naa bi Ere Itage | Esekieli 4:5-8 |

## ORO AKOSO

Ise aworan yiya je ohun elo ti o l'agbara fun ibanisoro, a maa ran awon ayaworan lowo lati so awon erongba, imolara ati iriri won pelu awon eniyan di mimo. O lee koja diduro fun ohun kan ni erefe, ki o si se awari ijinle awon akori kan, irusoke ijiroro, ki o si agbajopo oye ti o ni itumo. A maa nlo awon ise aworan fun oro ti a fi oju ri, awon ami, ero ori nipa aworan, ati ona lati so itumo kan ti awon oro nikan ko lee so di mimo. Ise Onise ti Iseda ati Asa je eko ti o dara fun awon odo wa lati yan laayo. Ninu eko wa ti oni, Olorun so fun Esekieli ki o ya aworan Jerusalemu si ori awo kan tabi Tabili alamo, lati je ise iranse nipa ijiya ti o nbo fun awon eniyan Israeli. Bi o tile je wipe, ni akoko isotele re, a ti ko awon eniyan kan lo si igbekun, ninu awon ti o je okan.Nitoriti won kuna lati ronupiwada, owo awon miran yio tun lo si igbekun. Gege bi Kristiani, o ko gbodo fi gbogbo ala ti o ba nla tabi iran ti o ba nri bi aworan sere. O ni itumo.

## EKO

### I. YIYA AWORAN IDOTI JERUSALEMU - 4:1-3

Oluwa pase fun Esekieli ki o ya aworan Jerusalemu si ori awo kan (tabili alamo tabi biriki) ki o si se afihan aworan kekere nipa idoti ilu naa, ki o pari re pelu ile iso, awon ago ota ati ki o si to olu yii ka. Beeni ki woli ki o mu awo irin kan, ki o si gbe e duro bi odi irin laarin re ati ilu na. O see se ki igbese yi se apejuwe bi idoti naa yio se tele ara won tabi sopo mo ara won lai duro tabi ki o duro fun idena laarin Olorun ati awon eniyan Re. Lati sotito,idoti naa le ma wa, ti won yio ba ronupiwada, o seni laanu wipe, won koni ronupiwada, beeni idoti naa yio wa. Awon ibi kan ki ba ti wa sinu aye wa gege bi omo Olorun. Sugbon, o di dandan ki won wa, ti a ba ko ti a ko ba gboran si ikilo awon eniyan Olorun ti a ran si wa.

### II. SISE AFIHAN IDOTI JERUSALEMU NI ONA TI O DUNNI - 4:4-7

Oluwa ti pase fun woli naa lati ru ajaga ese (boya ijiya) awon Israeli nipa apeere. O gbodo dubule pelu iha osi re fun irinwo ojo odin mewa, eyi ti o duro fun iye odun ijiya awon ese ti ijoba ariwa. Leyin eyi o gbodo dubule pelu iha otun re fun ogoji ojo, ti o duro fun iye odun ijiya awon ese ti Juda. O tumosi wipe, Esekieli yio se afihan bi ijiya awon eniyan re yio se le to fun irinwo odun, o le ogbon ti o duro fun awon odun ijiya won. A ko awon ijoba ariwa lo igbeku ni odun 772 BC nigbati a ko awon gusu lo si igbekun ni odun 586 BC awon mejeji si pada si ile won ni nkan bi odun 516 BC,eyi ti o mu ki o je bi igba odun o lee. Bi o tile je wipe awon akoko wonyi wonu ara won nipa ti onka isiro.

Okan ninu ona ti Olorun ma nlo lati so okan re di mimo fun Israeli ni nipa lilo igbesi aye tabi idile woli re. Olorun lo igbeyawo ati idile Hosea lati sotele fun Israeli. Ninu eko wa ti oni, a ri bi Olorun se lo igbeaye woli Esekieli gan lati ba awon Israeli olote soro. Gege bi iranse Olorun, Olorun le lo aye re tabi idile re lati

ba awon omo ijo soro. Nitori idi eyi, awon ipenija ti o ndojuko ninu ise iranse je ohun elo ikoni, bakan ni oro naa kan gbogbo Kristiani, farada, yio pada wa di eri fun o.

**AWON IBEERE**

1. Kinni ise pataki Ise aworan tabi aworan yiya?
2. Se apejuwe aworan Jerusalemu ti Olorun so fun Esekieli ki o ya.
3. Bawo ni Olorun se so pe ki woli se afihan ijiya ti o nbo fun Israeli?
4. Ona wo ni Olorun maa ngba lati so okan Re di mimo fun awon Omo Israeli gege bi eko wa ti oni yii?
5. Awon ipenija aye re, awon ohun elo ikoni ni, se alaye.

**FEBRUARY 15, 2026 EKO 7**

# SISE AFIHAN IDOTI JERUSALEMU (II)

***BIBELI KIKA:-*** *EZEKIEL 4:9-17*

***ESE AKOSORI:-*** *"Iwo o si je onje re nipa iwon, ogun iwon sekeli li ojo kan, lati akoko de akoko ni iwo o jee.'' (Ezekiel 4:10).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 9/2/2026 | Ikerora ninu inira 1 | Ekun Jeremiah 5:1-5 |
| Ojo Isegun | 10/2/2026 | Ikerora ninu inira 2 | Ekun Jeremiah 5:6-10 |
| Ojoru | 11/2/2026 | Ikerora ninu inira 3 | Ekun Jeremiah 5:11-15 |
| Ojobo | 12/2/2026 | Ikerora ninu inira4 | Ekun Jeremiah 5:16-22 |
| Ojo Eti | 13/2/2026 | Iriri inira Jerusalemu | Orin Dafidi 79:1-5 |
| Ojo Abameta | 14/2/2026 | Ami inira | Esekieli 4:9-12 |
| Ojo Aiku | 15/2/2026 | Akara Aimo naa | Esekieli 4:13-17 |

## ORO AKOSO

Ni ose ti o koja, a ko wipe Olorun ba Esekieli sora nipa ona aworan. Ninu eko wa ti oni, O baa soro nipa ona ere itage. Olorun ara ni Olorun; O le e lo ona ti O ba wu U lati ba awon omo Re soro. Esekieli 4:9-17, se afihan woli bi o se nse awon oniruru ise, o fihan wa wipe lekookan, a maa dide kuro ni ipo apeere ti o wa. Ko ye wa ni pato, boya awon akoko ese atijo tabi ijiya ojo iwaju li o nse apeere. Ise pataki nomba irinwo odin mewa ati ogoji ko ye wa rara.Awon asiri ijinle kan wa ti ko lee ye wa lekan naa tabi ni aye yi, a fi igba ti a ba de orun ni ohun gbogbo yio han kedere si wa.Sugbon, ohun ti o se pataki ni lati se ife Olorun ki a ba lee bo lowo ibinu Re.

## EKO

### I. AKARA ATI OMI TI O NSE APEERE - 4:9-13

Gege bi ase Oluwa,  Esekieli fi oniruuru irugbin bii; alikama, oka baba, eree, lentile, milleti ati ewe se akara  (ese 9) o si fi won sinu ikoko kan (oseese ki o je ikoko oru). Ni akoko irinwo ojo odin mewa (woo 4:5), o gbodo je iwon sekeli ogun ni ojo kan (iwon mejo), pelu omi nipa iwon, idamefa osuwon hini kan (idameji ninu idameta iwon ife omi kan). Irufe ounje ti o ni gbendeke yii se apeere iru ounje ti won yio maa

je ni akoko idoti Jerusalemu ti o nbo wa. Oluwa tun so fun Eselieli wipe ki o fi igbe eniyan din akara re. (eyi tumo si, fifi igbe eniyan da ina). Igbe eniyan je ohun aimo ninu Deut. 23:12-14. Sa fun ibinu Olorun, Olorun le lo ohunkohun lati fi iya je awon elese ti ko ronupiwada. Awon woli majemu lailai ma nfi ara won rubo, won ko dabi awon woli ti ode oni, ti won so awon eniyan di ohun irubo tabi fi ipa gba owo lowo awon eniyan.

**II. YIYONDA ARA ENI LEYIN FIFARIGA - 4:14-17**

Esekieli ko wipe oun ko ni fi igbe eniyan din akara oun nipa titenu wipe, a ko ti so okan oun di aimo pelu eran irira lati igba ewe oun wa titi ti oun fi dagba. ( Eks 22:31, Left. 11:40, Deut. 14:3). Eyi tumosi wipe, o ti maa npa ara re mo nipa bi esin re ti gba. Olorun wa pase fun wipe ki o lo igbe maalu dipo igbe eniyan, eyi ni wipe, ki o lo igbe maalu gege bi epo. A gbodo duro ninu iwa mimo wa lati igba odo titi di igba agba. Igbese Esekieli se awojiji inira awon ti o wa ni igbekun, ti a ma fi ipa mu won lati je ounje ni ile ajeji ti ko mo. (Kaa, Ekun Jeremiah 5:1-22, paapa julo 5:4, 9). O je ohun ti o lewu lati subu sowo ibinu Olorun. Olorun yio gba awon ota laaye lati fi iya je awon omo Re nitori won se aigboran si I. A gba gbogbo omo ijo niyanju lati yago fun ese ti o lee ko olusoagutan won sinu iyonu ati ijiya nigbeyin.

**AWON IBEERE**

1. Ona wo ni Olorun gba ba Esekieli soro loni?
2. Awon irugbin wo ni Esekieli fi se akara re?
3. Se afiwe laarin awon woli majemu lailai ati awon ti ode oni.
4. Kini Olorun lo dipo igbe eniyan?
5. Kini igbese Esekieli nse awojiji?

**FEBRUARY 22, 2026 EKO 8**

# IPARUN JUDA (APA KINNI)

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 5:1-11*

***ESE AKOSORI:-*** *"Emi o si se ninu re ohun ti emi ko se ri, iru eyii ti emi ki yoo si se mo, nitori gbogbo ohun irira re" (Esek. 5:9).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 16/2/2026 | Ere aigboran ni iparun | Owe 29:1-3 |
| Ojo Isegun | 17/2/2026 | Eni ba ronupiwada ese, a o darijin | Ise A. A. 3:19 |
| Ojoru | 18/2/2026 | Awon eni ti ki yoo se rere | Owe 28:12-14 |
| Ojobo | 19/2/2026 | Asilo ohun ti Olorun fi fun ni | Danieli 5:1-7 |
| Ojo eti | 20/2/2026 | Ese mu iberu wa, nitori naa sa fun ese | Genesisi 3:1-10 |
| Ojo Abameta | 21/2/2026 | Elese kan ki yoo lo laijiya | Owe 11:18-21 |
| Ojo Aiku | 22/2/2026 | Ijiya daju fun elese | Esekieli 5:8-11 |

**ORO AKOSO**

Ikun n je ogede, ikun nredi, ikun ko mo pe ohun ti ndun nii pa ni". Bee ni oro awon omo Israeli. Opo igba ni Oluwa Olorun ki won ni ilo pelu iwa-buburu won; sugbon won ko eti-ikun si ikilo Olorun. Abajo ti iwe Owe fi so wipe (Owe 29:1) "Eni ti a ba nbaa wi ti o nwa orun ki, yoo parun lojiji lai si atunse". Osuwon awon omo Israeli kun wayi, Oluwa ranse iparun si won lai si atunse mo. Fun apere, e ka ese ikokanla (vs. 11).

Bakan naa ni Olorun nranse ironupiwada si awa naa loni, e je ki a gbo ikilo ki a si gbaa, ki a sa fun ese, ki ojo ibinu Oluwa to ro sori aye, yoo si dara fun wa.

**EKO**

**I. ISE TI A FI RAN WOLI ESEKIELI - Ese 1-4**

Yoruba bo ninu owe won, wipe "Eni ti o ran ni nise ni aa beru, a kii beru eni ti a o ji'se naa fun". Bee ni oro woli Esekieli, ko beru lati jise ti Oluwa ran-an. Fun idi eyi, bi Oluwa ba ran awa naa ni'se ohun kan, ki a mase beru lati jise naa bi a ba ti fi ran wa.

(I Samueli 2:27-32) Ise ti a fi ran woli naa wa ni ese (1-4) kinni si ese kerin iwe ti a ka.

(a) Ki o fi abe oni-gbajamo fa irun ori ati irungbon re. Leyin naa ki o fi osuwon won-on (ese 1).

(b) Oluwa so fun-un bi yoo ti se pin awon irun naa gege bii iru iparun ti yoo fi je awon omo Israeli ni'ya (vs. 2-4).

Eyi nki wa ni'lo wipe, ki a tete ronupiwada ki aisedeede wa to kun osuwon niwaju Oluwa wa.

**II. ASILO IPO TI OLUWA OLORUN TO JERUSALEMU SI LAARIN AWON ORILE-EDE (Ese 5-7)**

Awon omo Israeli si ipo won lo laarin awon orile-ede ti o yi won ka. Igbe-aye awon omo Israeli wa da bii oruka wura ni imu elede. Asise ti won paapa buru ju ti orile-ede ti ko mo Olorun (vs. 6). Eyi mu ki Oluwa pinnu re lati se idajo ti o ni eru fun won. Bawo ni awa pelu ti nlo ipo ti Olorun to wa si gege bii Kristiani? Se Kristiani ti wa ko ti di isoro-odi si lawujo ti a wa ati nibi ise wa? E je ki a mo eyi daju pe, elese kan ko nii lo laijiya (Owe 11:21).

**III. IJIYA TI ESE MU WA (Ese 8-11)**

**(a) O je eyi ti o gbona (ese 8-9).**

Eyi fi ye wa pe, eni ti o ba se ohun ti enikan ko se ri, oju re a ri ohun ti oju enikan ko ri ri. Fun idi eyi, e je ki a sora wa gidigidi, ki a mase mu Olorun wa binu.

**(b) Ohun buburu miran ti ese maa n mu wa tabi da sinu aye eniyan (vs. 10-11)**

Ese a maa mu ki aja je ifun-ara won (vs. 10). Iyen ni pe, elese maa nfi owo ara re se ara re. Nitori naa, eje ki a yago fun ese, ki a sa nigba ti o ba (ese) ndode wa (Gen. 39:12; I Tess. 5:11). Yoo si dara fun wa.

**AWON IBEERE**

1. Ni ibamu pelu igbe-aye awon omo Israeli, so ni soki pelu owe yi "Aja ti yoo nu, kii gbo fere olode".
2. Kin ni ise ti Oluwa ni ki woli yi (Esekieli) koko se?

3. Kinni ipin-irun naa ni i se pelu ohun ti Oluwa fe se si ile-Israeli?
4. Kinni atubotan asilo ipo maa nmu ba eniyan ni ibamu pelu eko wa oni?
5. Ti a ko ba fe ibawi Olorun ti o gbona jan-jan, kinni o ye ki a se?

**MARCH 1, 2025** **EKO 9**

# IPARUN JUDA (APA KEJI)

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 5:12-17*
***ESE AKOSORI:-*** *“Bi a tile fi owo so owo, eniyan buburu ki yoo lo laijiya, sugbon iru-omo olododo ni a o gbala (Owe 11:21).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| OJO AJE | 23/2/2026 | Ko si ohun ti Olorun ko le lo lati fi je elese ni iya | Num. 21:4-7 |
| OJO ISEGUN | 24/2/2026 | Elese kan ba opo ohun rere je | Oniwasu 9:15-18 |
| OJO RU | 25/2/2026 | Okun gbolo-gbolo ni ese, sa fun-un, ki o mase akoba fun elomiran | Josua 7:19-26 |
| OJO BO | 26/2/2026 | Aigboran ni amona si iparun, nitori naa je olugboran | Isaiah 1:19-20 |
| OJO ETI | 27/2/2026 | Egun kii wa lainidi | Owe 26:1-4 |
| OJO ABAMETA | 28/2/2026 | “Omi ole dun...” | Owe 9:12-18 |
| OJO AIKU | 1/3/2026 | Ko si eyi ti o rorun ninu ere-ese, sora | Esekieli 5:13-17 |

**ORO AKOSO**

Nitooto ni Olorun feran elese, sugbon O korira ese. Idi eyi ni o se ran omo Re wa sinu aye lati le gba wa la kuro ninu ese wa (John 3:16-17 & Matiu 1:21). Nitori iru-ife nla bi eyi, eese ti awa yoo se ko iru igbala nla yi, ti a ko si ni lee sa fun ese, ki a ko gbogbo ese wa sile ki o to pe ju. E je ki a mo eyi daju pe, suuru Olorun nbo wa d’opin lojo kan. Ki a wo bi Olorun ti mu suuru to fun awon omo Israeli, boya won yoo ronupiwada ese won, sugbon won ko, won ntesiwaju pelu buburu ise won. Osuwon iwa won kun wayi, Olorun ti wo ona miran lati je won niya ese won. A o maa se alabapade irufee ona ti Olorun tun la kale lati fi je won niya ninu eko wa ti oni. E jeki a koja lo sinu eko naa.

## EKO

**I. ORISI ONA META TI OLUWA FE GBA JE JUDA NI IYA ESE (Ese 12)**

Bi a wi fun omo-eni a gbo, nitori naa, ohun ti oju oku ba ri ni sa-ree, iku ni o mu un wa. Awon omo Israeli ni o fa isoro ti o de ba won yii. Kinni awa naa nfa lese lowo-lowo tii se buburu, ki ba dara ki a tete jawo nibe; ki o to pe ju. E je ki a se akiyesi awon ona naa ti Oluwa fe gba je won (Juda) niya (vs. 12):

i. Idameta re yoo ku nipa ajakale arun
ii. Idameta yoo si subu nipa ida yi kaa-kiri.
iii. Oluwa ni oun yoo tu idameta ka si gbogbo efuufu - leyin naa yoo yo ida tele won.

Ninu iparun tabi ijiya wonyi, ewo ni o dara ninu won? E jeki a sa fun ibinu Oluwa, ko si eyi ti o see fara-da ninu re yoo si dara fun wa - bi a ti nse bee.

**II. IPARUN PATA-PATA TI OLUWA PINNU RE (Ese 13-17)**

Nigba ti ilu bata tabi dun-dun ba nro lako-lako, ki a mo pe ilu naa fe tabi setan lati faya ni. Bee gege ni oro awon omo Juda. Fun ori-kun-kun won, Oluwa Olorun ti pinnu re lati fi won sofo ninu iparun ti o fe se gbeyin ninu ori iwe yi.

**(a) Ni ibinu, Oluwa pinnu ati fi won sofo (ese 13-14)**

O se ni laanu fun awon omo Juda, bi Olorun ti yan won fe to, sibe, won ja Olorun kule. Nje e je mo wipe Olorun feran awa naa. Se awa pelu ko nii ja Olorun kule? Se a ko nii doju ti I laarin awon alaigbagbo pelu iwa wa ati ise wa ti a nse?

**(b) Awon ohun ija miran ti Oluwa Olorun fe lo lati fi je awon omo Israeli niya (ese 15-17)**

Lara awon ohun ti Olorun pinnu re lati fi je awon eniyan yi niya ni a ti ri ifini-sesin, isoni-di-eni-egan, abbl. Bakan naa ni Oluwa se ileri ati ran ofa-buburu-iyan si won (ese 15-17) abbl.

Ohun buburu gbogbo ti ese maa nmu ba eniyan ni wonyi. Nitori naa, yoo je ohun buburu ti a ko ba le ko eko lara ohun ti o de ba awon omo Israeli nibi, ki a si sa fun ohun gbogbo ti a pe ni ese, ati ohun gbogbo ti o jo ibi; ki awa pelu mo baa fara gba ninu ibinu Olorun ti o bo wa de ba aye lojo kan.

**AWON IBEERE**

1. Kin ni yoo mu Olorun binu si araye?
2. Nje Olorun jebi awon omo Israeli niti ibi ti o so pe oun yoo se si won?
3. Ni idahun si ibeere keji oke yi, se alaye ni ekun-rere igun ti o ba ko si wipe Olorun jebi, tabi ko jebi.
4. Ka ese akosori wa ti oni, ki o si fi ko wa ni eko laarin iseju meji.
5. So ona ti a lee to ti a o fi bo kuro ninu iparun ti nbo wa de ba "Tinu-mi ni maa se"

**MARCH 8, 2026** **EKO 10**

# ASOTELE SI AWON OKE ISRAELI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 6:1-14*

***ESE AKOSORI:-*** *"Bayii ni Oluwa wi, e duro ni oju-ona, ki e si wo, ki e si beere oju ona igbaani, ewo ni ona didara, ki e si rin nibe, eyin o si ri isinmi fun okan yin, sugbon won wipe awa ki yoo rin" (Jeremiah 6:16).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| OJO AJE | 2/3/2026 | Asiri Oluwa wa pelu awon eniyan re | O.D. 25:14 |
| OJO ISEGUN | 3/3/2026 | Asotele ti o wa si imuse | Sakariah 9:8-10 |
| OJO RU | 4/3/2026 | Mase gba etan awon elese | Owe 1:10-19 |
| OJO BO | 5/3/2026 | Ere nbe fun olukuluku ise | Ifihan 22:11-12 |
| OJO ETI | 6/3/2026 | Ikosile ninu ibinu | Isaiah 1:13-25 |
| OJO ABAMETA | 7/3/2026 | Olorun je ina-ajoni-run | Deut. 4:23-28 |
| OJO AIKU | 8/3/2026 | Ibawi fun alaigboran | Deut. 28:15-25 |

### ORO AKOSO

Iwa ti o buru ju ni ki eniyan fi ohun miran dipo Olorun eleda re, lati maa sin-in. Idi eyi ni Olorun fi mu-un ni pataki ninu ofin ti o fi fun awon omo Israeli (Eksodu 20:3-5). Bi a ba si fi oye woo-fin, a o ri wipe iwa-omugo gbaa ni ki a maa bo ohun ti a fi owo wa da, ohun ti o loju, ti ko fi riran, o l'eti, ko fi gboran, o ni ese, ko lee fi rin ayafi ki awon olujosin re maa gbee kiri, abbl. Fun idi eyi, Olorun fi iborisa gegun-un, O si pinnu re lati fo won tuutuu. E gbo ohun ti oro Olorun so pelu gbogbo okan ti o kun fun iborisa (O.D. 115:4-8). Nitori naa, ona wo ni iborisa ti fe rapala wonu aye ti wa naa l'oni, se nipa akoko, ise wa, ounje jije, ohun-elo wa, abbl. E jeki a sora, ki a mase fa ibinu Olorun sori ara wa. Ese yi ni awon omo Israeli se ni aginju ti opolopo emi si baa lo (Eksodu 32:1-35). Oluwa ko oju ija si ese-iborisa. Sora ki okan buburu ti aigba-Olorun gbo ki o ma se wa ninu enikeni yin - nitori iparun ati egbe ni atubo tan-an re.

### EKO

**I. IDAJO ONIPELE MEWA FUN ISRAELI (Ese 1-7)**

Nigba ti ese de, itiju de, ko si ohun ti elese tabi ese-dida ko lee se akoba fun. Fun apere, Oluwa ni ki woli so asotele si oke, kinni o faa, ese awon omo Israeli ni. Nitori naa, ko si ere ninu iwa ese, e jeki a sa fun-un.

**(a) Asotele Iparun awon-oke (ese 1-3)**

Eyi mu wa ranti ese Akani, o ko ba ara-ile, o ko ba ara oko, o tun ko ba je-je mi ni mo joko-o mi pelu. Opo omo ogun ni won subu nigba ti won lo ja ogun ilu-Ai (Josua 7:1-6). O mu ki won sa niwaju awon ota won. Bee ni ese awon omo Israeli se akoba fun awon oke ti o yi won ka. Kinni awa naa nfowo fa lakoko yi, se ko ni fa wahala ati idaamu ba awon elomiran? Ese loro, e je ki a sora se.

**(b) Idajo ti Oluwa pinnu lati fi je awon oke niya (ese 4-7)**

Oluwa Olorun so pe oun yoo wo gbogbo pepe iborisa won lule, yoo si di ahoro, yoo fo won. Oku yoo si po titi ti won yoo fi te won siwaju orisa won. Bakan naa ni o so wipe, gbogbo ilu-nla won yoo di piparun abbl. Ohun ti o lee fa ibinu-nla bi eyi, e je ki a sa fun un. Nitori ti ko si ojusaaju eniyan lodo Olorun.

**II. ILERI ATI DA DIE SI NINU WON (Ese 8-10)**

Olorun oniyonu julo, bi ese awon eniyan yi ti po to, sibe Olorun tun se ileri ati da die si ninu awon eniyan wonyii. Ti a ba se akiyesi, erongba okan Olorun ni alo yi, a o rii wipe o si nfe ki awon eniyan le yipada iwa buburu won (Isaiah 1:18). Nje awa naa setan ati lee se atunse ona wa niwaju Oluwa? Nje awon eniyan wonyi ronupiwada irekoja won? A o ri idahun si ibeere yi ninu abala ti a o fi kadi eko yi ni'le.

**III. IPE SAKIYESI JUDA FUN IDANILOJU IDAJO TI KO LE SAI DE BA WON (ESE 11-14)**

Nigba ti o ye ki awon omo Israeli kiyesara, ki won se atunse ona won, ati iwa buburu won, won o se eti ikun si Oluwa Olorun Eleda won. Ni bayi, irufee ohun ti Olorun fe fi ba won ja ni a ri ninu awon ese oro

Olorun wonyii (ese 11-14). Oluwa ni ki woli Esekieli patewo, bakan naa o so fun un ki o fi ese re ki'le. Oluwa se eyi ki won le fiyesi ohun ti Olorun ran woli naa si won. A ri wipe eyi ko mi won lokan lati wa riri si ohun Olorun. Se eyi ko nri bee ninu aye wa loni?

Ni opin gbogbo re, Oluwa tun kede ohun ti ko le sai sele si won (ese 11-14). Fun apere, iku tabi isubu nipa ida, nipa iyan, ati nipa ajakale arun. Bori-bori re, Oluwa ni oun yoo so ile naa di ahoro. Eyi tumo si wipe ko ni si olugbe kan mo nibe. O se iye-biye, ki a je olugboran nigba ti Oluwa ba nranse si wa. Aye wa, ile wa, oko-owo wa, abbl. ese ko ni je ki Oluwa soo di koronfo - bee ni ko ni di ahoro mo wa lori.

**AWON IBEERE**

1. Ka ese akosori wa ti oni, ki osi fi ko ni laarin iseju-meji?
2. Se alaye ni ekun-rere, awon ona ti a lee gba fi ohun-miran dipo Olorun ninu iwa ati ise wa.
3. Nje otito ni pe "ko si ohun ti ese ko lee ko ba"? Se alaye ni ibamu pelu eko wa ti oni.
4. Kinni a le pe ni ete-Olorun lati da die si ninu awon omo Israeli ninu eko wa ti oni?
5. So ni soki ohun ti o ri ko ninu eko ti oni.

**MARCH 15, 2026 EKO 11**

# IBINU OLORUN LORI ISRAELI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 7:1-14*
***ESE AKOSORI:-*** *"Opin de si o wayi, emi o si ran ibinu mi sori re, emi o si da o lejo gege bi ona re; emi o si san gbogbo irira re pada si o lori" Esekieli 7:3.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| OJO AJE | 9/3/2026 | Iwo ko gbodo ni Olorun miran leyin Olorun alaaye | Eksodu 20:1-5 |
| OJO ISEGUN | 10/3/2026 | Ibinu Olorun lori Israeli | Esekieli 7:1-5 |
| OJO RU | 11/3/2026 | Ti Oluwa ni aanu | Romu 9:14-18 |
| OJO BO | 12/3/2026 | Suuru Olorun yoo dopin lojo kan | 2 Peteru 3:1-10 |
| OJO ETI | 13/3/2026 | Ojo idajo ku si dede | Sefaniah 1:14-18 |
| OJO ABAMETA | 14/3/2026 | Sora fun ibinu Olorun | Sefaniah 1:1-6 |
| OJO AIKU | 15/3/2026 | Ko si ohun ikoko lodo Oluwa | Jeremiah 16:16-18 |

## ORO AKOSO

Olorun wa je alaanu ti o si feran gbogbo awa eniyan ti o da ni aworan re, papa julo awon ti o ba wa ni iha Re. Bakan naa ni O ma se ikilo gidigidi ki o to binu, sugbon bi enikan ba ko lati gbo ikilo Olorun a je wipe iru enibee ni o fi owo ara re fa ibinu Olorun si ori ara re niyen, ninu eko yi, a o ri pe Olorun binu si awon omo Israeli gidigidi nitori won ko lati gba ikilo Oluwa. Nitori naa a nilo ikiyesi ara ni akoko tiwa yii lati

feti si ikilo Olorun lati enu awon iranse re ki Olorun mo ba binu si wa, mo gbadura Oluwa ko ni binu si wa o (Amin) Jer. 50:7.

## EKO

**I. ASOTELE NIPA OHUN TI YOO SELE SI ISRAELI (Ese 1-6)**

**(a) Opin de tan fun Israeli (ese 2)**

Nitori ese awon eniyan naa di pupo niwaju Oluwa, Olorun setan lati mu ki opin de ba won, nitori won ko lati ronupiwada leyin opo ikilo Olorun fun won (Amos 8:2). Kinni ese awon eniyan yii niwaju Olorun? Iborisa ni, won ko Olorun sile, won nsin orisa, eyi ni o mu Olorun binu si won (Eks. 20:2-5). Oju Oluwa koro si enikeni to nsin Olorun ajeji - Esekieli 5:11.

**(b) Ibinu Olorun si won (ese 3)**

Olorun mura tan lati binu si won, ewu nla ni ki Olorun binu si eniyan, bi eniyan ba binu si eniyan egbe re, yoo be Olorun si iru eni bee, sugbon nigba ti Olorun ba binu si enikan iru eni bee wa ninu ewu nla, adura wa ni pe Oluwa ko ni binu si wa, ki a mo ba bo sinu ibinu Olorun a ni lati ko ona tiwa sile ki a si pada si ona ti Olorun patapata, nitori ona ti wa irira ni loju Oluwa (Jer. 44:16-17).

**(d) Ki yoo si aanu fun awon eniyan naa mo (ese 4)**

Olorun fun ra Re lo se ileri aanu fun awon omo re (Eks. 33:19, Rom. 9:15). Iyen nigba ti enikan ba se ife Olorun, sugbon kiko ife Olorun sile le fa oniruuru ijiya iru eyi ti a kiyesi yi, Olorun ni Oun ki yoo saanu fun awon eniyan naa mo nitori aisedeede won ati irira won lati fihan pe, Oun Olorun to se ileri aanu tun le yipada ti enikan ba ko lati rin ni ona Re.

**II. ILE YOO MO BA AWON ONISE IBI (Ese 7-14)**

**(a) Asiri ikoko gbogbo yo han kedere (ese 7; Jer. 16:17).**

Olorun wa je Olumo ohun gbogbo ti o wa ni ikoko okan eniyan, ohun gbogbo ti eniyan se ni ikoko kedere ni niwaju Oluwa, nitori naa akoko to fun Olorun lati je awon omo Israeli niya ese won (Sefaniah 1:2-6) ki iru akoko yi to de a nilo atunse ti o ye nitooto (Sef. 2:1-2).

**(b) Awon idajo Olorun fun won (ese 8)**

i. Oluwa ni Oun O binu si won (ese 8b)
ii. Idajo laisi aanu (ese 8d)
iii. “Emi O si san fun o nitori gbogbo irira re” (ese 8e)
iv. Ko ni si aye fun olutaja ati olura ni ojo naa nitori gbogbo eniyan naa ni oro naa yoo kan (ese 14)

Ni iru akoko tiwa yii naa oniruuru iwa iborisa ni o ti gba aye kan, egbe okunkun po ni orisirisi, Olorun si kilo fun gbogbo iran eniyan fun ironupiwada ki akoko ibinu Olorun to de, adura wa ni pe ki Oluwa mu wa duro ninu ife Re dopin.

**AWON IBEERE**

1. Kinni o mu ibinu Olorun wa sori awon omo Israeli?
2. Tani a fi ise ikilo yii ran?
3. (a) Nigba wo ni opin yoo de?
   (b) Kinni o ye lati se ki opin to de?

4. Ko ni si aye fun olutaja ati oluraja, nitori kinni?

**MARCH 22, 2026 EKO 12**

# IDAJO OLORUN SI AWON ENIYAN NAA

***BIBELI KIKA:-*** *EZEKIELI 7:14-27*
***ESE AKOSORI:-*** *“Iparun nbo wa, won o si wa alaafia, ki yoo si si” Esekieli 7:25*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| **Ojo** | **Deeti** | **Akori** | **Bibeli Kika** |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 16/3/2026 | Mase feran aye | I John 2:15-17 |
| Ojo Isegun | 17/3/2026 | Bi o ti ri nigba aye Noa | Matiu 24:36-42 |
| Ojoru | 18/3/2026 | Idajo Olorun si awon eniyan naa | Esekieli 7:14-21 |
| Ojobo | 19/3/2026 | Ewu to wa ninu aigboran | Esekieli 7:21-27 |
| Ojo Eti | 20/3/2026 | Oju Oluwa wo gbogbo eniyan | Esekieli 39:23-24 |
| Ojo Abameta | 21/3/2026 | Sa asala fun emi re | Gen. 19:12-17 |
| Ojo Aiku | 22/3/2026 | Ko si alaafia fun eniyan buburu | Isaiah 48:17-22 |

## ORO AKOSO

Nigba ti Olorun ba kilo opo awon eniyan ni kii ka si, awon miran a ma fi ikilo Olorun se awada bii ti igba aye Noa (Matiu 24:38-39). Gbogbo ikilo Olorun lati enu Noa ni awon eniyan ko lati gbo titi ikun omi fi de ti o si gba won lo, beeni Olorun kilo fun awon omo Israeli lati enu awon woli re bii Esekieli, sugbon won ko, won se ife inu ara won eyi ti o si fa idajo Olorun si ori won tobee ti opo eniyan ku, oniruuru ise buburu ni o sele si won gege bi awon eyi ti a ti n gbeyewo bo, a o tun kiyesi awon miran ninu eko toni, awa o ni je abori kunkun ni oruko Jesu.

## EKO

### I. AWON IDAJO TI O LE (Ese 15-18)

***(a) Idajo Iparun (ese 15)***

Olorun ran idajo re si ori awon eniyan yii, ko si alaafia ninu ile, ko si alaafia ni ode. “Alaafia ko si fun awon eniyan buburu, ni Oluwa wi” (Isa. 48:22, 57:21, 59:8). Eniyan Olorun ni awon omo Israeli tele sugbon nigba ti won ya kuro ni ona Oluwa, O ti setan lati fi iya je won, wahala de si won, ida lode, ajakale arun ninu ile, ko si isinmi fun okan won mo. Bi ara re leere kinni okunfa isoro ti o wa ninu aye re lowolowo bayi? Se kii se aigboran re ni, ti o ko fi ni ifokanbale, se atunse ki o to peju.

**(b) Awon kan mori bo lowo iku (ese 16)**

Ninu awon eniyan yii awon kan mori bo lowo iku ida, sugbon won o bo lowo idajo Olorun nitori nibiti won salo naa ko si alaafia fun won nibe, ko si onje, won bere si gbaawe nibe nitori igbe aye ese ti won ti gbe niwaju Olorun. Mo wipe ohunkohun ti o se nikoko tabi ni gbangba ni o ni esan lowo Olorun, nitori naa se rere ki o le gba esan re lati odo Olorun.

**(d) Ijiya naa tesiwaju (ese 17)**

“Gbogbo awo ni yoo ro, gbogbo eekun ni yoo si di ailera bii omi” ese 17. Ko si ayo fun awon eniyan naa, ninu iberu ni won gbe igbe aye won, nitori won ti sina kuro lodo Eleda won, ninu ewu nla ni eniti o ba ti kuro lodo Olorun eleda re wa, nitori naa sa fun ewu idajo Olorun ti nbo.

**II. WON PADANU AWON DUKIA TI WON NI (Ese 19-21)**

**(a) Ini won ko gba won la (ese 19)**

Akiyesi nibi pe awon ohun alumoni ti won ni ko le sise igbala won kuro lowo idajo Olorun, ohun ti awon eniyan yi sare to leyin niyi ti won fi ko lati se ife Olorun, nibo ni afe aye ba iwo naa de loni, nitori ohun ti aye yoo ba aye koja lo (I John 2:15-17). Ife awon nkan ti aye yoo mu wa maa kolu ife ti Olorun, ewu si wa nibe.

**(b) Ife inu won mu Olorun jinna si won (ese 20)**

Awon ohun rere ti Olorun ni fun awon eniyan a po, sugbon nitori iborisa won, Olorun soro wipe awon nkan wonyi yoo jinna si won iyen ni pe a o gba kuro lowo won, nitori won se ohun irira loju Oluwa niti iborisa, opo ohun rere ni o jinna si iwo naa loni nitori awon iwa irira ti o wu niwaju Olorun loni, kiyesi ara.

**(d) Won yoo sise fun awon elomiran je (ese 21)**

Omo Olorun ni a se ileri jije oro keferi fun sugbon oro kori bee mo nibi fun awon omo Israeli nitori won tapa si ofin Olorun Eleda won, ohun gbogbo ti won ti ni Oluwa gba kuro lowo won, O si fi fun awon alejo lati maa se bo se wu won, a gbadura eto wa ko ni di ti elomiran.

**III. OJU OLUWA YOO KURO LARA WON (Ese 22-27)**

**(a) Oluwa yoo pa oju re mo kuro lara awon omo Israeli (ese 22)**

Ninu ewu nla ni eni ti Oluwa pa oju Re mo kuro lara re wa (Esekieli 39:23-24). Oluwa ni Oun o mu oju kuro lara won, eyi yoo fi aye oniruuru iwa ibi si awon eniyan lati odo awon eniyan ika lati fi iya je won gege bi ise owo won niwaju Oluwa (Owe 15:3, Job 34:21). Ni otito ni Olorun wo gbogbo eniyan, sugbon nigba ti O wo o, ipo wo ni o wa niwaju Re.

**(b) Ikilo Olorun fun woli Esekieli (ese 23)**

Ikilo Olorun ki O ro ewon kan, nitori ile naa kun fun ese ipaniyan ati awon iwa ipa, ti o ba wo orile-ede wa bayii, a o ri pe itaje sile ti poju nitori ati di olowo ojiji ati fifi agbara bo sipo, wiwa agbara ni orisirisi ona lati ipase esu, ki Olorun gba wa lowo iru awon eni esu bee, ki awa pelu mo darapo mo iru ise ibi bee, awon odo loni fe di olowo ojiji, awa obi ki a se ikilo fun awon omo wa, ki awa naa maa sora.

i. Awon keferi ti o buru ju won lo yoo jogun ohun ti won ni (24a)
ii. Nigba ti iparun naa ba de ki yoo si alaafia (ese 25) bi idajo ba de ko si eni ti o le mori bo ninu idajo Olorun.
iii. Nigba ti akoko idajo ba de awon eniyan yoo maa wa ona abayo sugbon yoo ti peju, akoko ironupiwada ko ni ju fun wa ni oruko Jesu (ese 26).
iv. Olorun kii se ojusaaju enikeni (ese 27, ese 4, Esekieli 18:20)

**<u>AWON IBEERE</u>**

1. Ka ese akosori lai wo iwe eko ki o si so eko ti o ri ko ninu re.
2. Ipin melo ni eko yii pin si?

3. So koko ipin kookan ati awon eko inu re.
4. So die ninu ohun ti awon eniyan naa padanu.
5. Awon to sala nibo ni won sa lo?

**MARCH 29, 2026 EKO 13**

# (OJO ISINMI IMO OPE)
# OMO KETEKETE TITUN KAN

***BIBELI KIKA:-*** *LUKU 19:28-40*

***ESE AKOSORI:-*** *"Wipe, E lo ileto ti o koju si nyin; nigbati enyin ba nwo o lo, enyin o ri omo ketekete kan ti a so, ti enikeni ko gun ri: etu u, ki e si fa a wa''. (Luku 19:30)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 22/3/2026 | Oba naa ti O nbo | Sekariah 9:8-10 |
| Ojo Isegun | 24/3/2026 | Oluwa ni fi won se | Matteu 21:1-11 |
| Ojoru | 25/3/2026 | E tuu, ki e si fa a wa | Marku 11:1-11 |
| Ojobo | 26/3/2026 | Hosanna! | Johannu 12:12-19 |
| Ojo Eti | 27/3/2026 | E jeki a fi ibukun fun Un | Orin Dafidi 118:26-29 |
| Ojo Abameta | 28/3/2026 | Olubukun ni Oba ti o nbo wa | Luku 19:28-40 |
| Ojo Aiku | 29/3/2026 | Oba naa fo Tempili mo | Luku 19:41-48 |

**ORO AKOSO**

Wiwo Jerusalem Jesu Kristi bi asegun ni a se iranti re ninu ile ijosin loni gebe bi isinmi imo ope. Ojo Isinmi imo ope je ojo isinmi pataki ninu itan Kristiani nitoriti o je ojo ti Jesu Kristi gun omo ketekete wo ilu Jerusalemu bi asegun. Ohun ni o bere Ose mimo titi wo ojo Isinmi Ajinde. Afojusun wa ti oni je eranko ti Jesu gun, ti Bibeli wipe, enikeni ko tii gun ri, eyi ni omo ketekete titun.

## EKO

### I. ISE TI A RAN LATI WA OMO KETEKETE TITUN - ESE 28-30

Ninu irinajo Jesu si Jerusalemu, O duro ni Betfage ati Betani li oke ti a npe ni Olifi. O ran awon omo eyin Re meji lo si ileto kan, ti o koju si won, ki won si o wa omo ketekete, ti enikeni ko tii gun ri. Eko kan wa ti Jesu Kristi fe ki a ko ninu Bibeli kika wa ti odun yi. Ohunelo ki ohunelo ti Olorun ba fe lo gbodo je titun, eyi ti o tumosi wipe, irufe eni bee gbodo je mimo. (Left. 11:44, Isaiah 52:11, Orin Dafidi 24:3-4,1 Pet. 1;15-16). O banilokanje loni wipe, opolopo awon ti o nsise ninu ijo lati oniwaasu si omo ijo ni ko je mimo. A le lero wipe Olorun ni o nlo won, sugbon ni igba ikeyin yi O so fun won wipe, ''…Emi ko mo won ri..''(Matt.7:21-23).

### II. ASE LATI TU OMO KETEKETE TITUN NAA - ESE 31-34

Jesu mo tele wipe; awon eniyan yio pe awon omo eyin nija nigbati won ba ntu omo ketekete. O so fun awon omo eyin lati so fun enikeni ti o ba pe won nija wipe, ''…Oluwa ni fi i se.'' (ese 31, 34). Nigbati won lo si ibe, a pe won nija, lesekese, won so ohun ti Jesu so pe ki won so, a si yonda omo ketekete naa fun won. A nilo lati se akiyesi lilo oro eniyan fun ohun ti ki i nse eniyan ni ese ikokanlelogbon ati lilo oro fun eniyan ni ese ikerinlelogbon ti a lo fun omo ketekete yi. O tumosi wipe, omo ketekete naa duro fun eniyan. Awon eko ti a fe mu jade ni wipe, Olorun ma nso okankokan ti o ba yonda ara re fun iwulo Re di ominira. O ko le sin Olorun ninu ide, O maa ntusile ki O to lo enikeni, ki o baa le tu elomiran sile. (Isaiah

61:1-4, Marku 16:17, 2 Kor. 3:17). Ti o ba si wa ninu ide gege bi ohun elo Olorun, ke pe E ni odun yi, yio so o di ominira ni tooto. (Johannu 8:32, 36) Bakan naa, ema se foju tembelu iranse Olorun ti a ran si yin; o wa nibe lati so yin di ominira. Gbagbo be e! Ki o si ni iriri re!

**III. A MU OMO KETEKETE TITUN NAA TO JESU KRISTI WA-ESE 35-40**

**(a) Won mu u to Jesu wa- ese 35a**

A mu omo ketekete naa to Jesu Kristi wa. A ko mo ajosepo ti o wa laarin Jesu Kristi ati eniti o ni omo ketekete naa, sugbon, otito ni wipe, o yonda omo ketekete naa fun Jesu.

Gbogbo iranse Olorun ti o ba fe gbadun ere ise iranse gbodo ni ajosepo ti o dara pelu awon eniyan ki o si ko ipa takuntakun lori won.A le gbe o kuro nibi kan, ki o si tun maa je oogun oju re nibe ti o ko ba ba ara re je.Eyin eniyan Olorun,e jeki a ma toju awon iranse Olorun nipa biba aini won pade l'akoko. O gbodo le e yonda awon ohun ini re fun Olorun ti O ni i.

**(b) A se omo ketekete naa l'oso- ese 35b-38**

Awon eniyan naa se omo ketekete naa l'oso; nipa tite awon aso won si ori re, beeni Jesu si joko le l'ori.(ese 35). Awon eniyan te awon aso won si oju ona, eyi ni a npe ni, tite aso ayesi loni (ese 36) A si bu ola fun Jesu ti o joko ka ori re pelu ariwo iyin gege bi ati sotele re ninu Orin Dafidi. (Orin Dafid 118:26; Ese 37-38). Ti o ba fe ki Olorun ki o lo awon eniyan lati se o l'oso ni odun yi, je mimo, ki o si yonda ra re fun Un.

**(d) Won ko ni agbara – ese 39-40**

Inu awon Farisi ko dun si bi won se nbu ola fun Jesu, nitorinaa, won so fun Jesu wipe ki o pa awon eniyan naa lenu mo. Sugbon, O so fun won wipe, ti awon eniyan naa ba pa enu won mo, awon okuta yio dide lesekese lati pariwo. Nigbati akoko titan re, ogo re ati ibu ola fun re ba de ninu Jesu Kristi, ko si ota ti o lee daa duro, nitoripe, won yio di alailagbara.

**AWON IBEERE**

1. Kini oye re nipa Ojo isinmi imo ope?
2. Bawo ni o se lee fi omo ketekete titun ko wa l'eko ?
3. Eko wo ni a lee ko lati inu titu omo ketekete sile?
4. Eko wo ni a lee ko lati inu mimu omo ketekete to Jesu Kristi wa ?
5. Eko wo ni a leri ko ninu sise omo ketekete l'oso?

**APRIL 5, 2026 EKO 14**

# (OJO ISINMI AJINDE)
# O TI JINDE! JI IGBAGBO RE DIDE.

***BIBELI KIKA:-*** *LUKU 24:1-12*

***ESE AKOSORI:-*** *"Ko si nihinyi, sugbon o jinde: e ranti bi o ti wi fun nyin nigbati o wa ni Galili.". (Luku 24:6)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 30/3/2026 | Obinrin L'akoko | Johannu 20:1-0 |
| Ojo Isegun | 31/3/2026 | Obinrin Onikaanu | Johannu 20:11-18 |
| Ojoru | 1/4/2026 | Okunrin se Iyemeji | Johannu 20:24-31 |
| Ojobo | 2/4/2026 | O Jinde! | Luku 24:1-6 |
| Ojo Eti | 3/4/2026 | Kii se Itan Aroso | Luku 24:7-13 |
| Ojo Abameta | 4/4/2026 | Ipongbe ninu Ifoju | Luku 24:14-21 |
| Ojo Aiku | 5/4/2026 | Ipongbe ninu Ailoye | Luku 24:22-27 |

### ORO AKOSO

Bi o tile je wipe opolopo ariyanjiyan ni o wa nipa ajinde Jesu Kristi lati ogorun odun akoko ti ijo bere. (Ka Matt. 28:11-15) Lai fi ti eyi se ati awon ariyanjiyan miran lodi is ajinde Re, otito ti o han gbangba ni wipe, Jesu Kristi jinde. Niwon igba ti o je wipe odoodun ni a maa se iranti ajinde Jesu Kristi, lekan si, a fe ran ara wa leti, ki a le so igbagbo wa ji si otito ti o daju nipa re. Ni pataki julo, eko wa ti oni yio dojuko ipa ti awon obinrin ko ni akoko ajinde Jesu Kristi laarin asa ti o fi owo yepere mu ise pataki awon obinrin. Eyi ni lati so di mimo fun wa wipe, okunrin ati obinrin se pataki ninu eto Olorun.

### EKO

**I. AWON OBINRIN LO SI IBOJI-ESE 1-3**

Ki a ba lee ni oye Bibeli kika wa, a gbodo pada si ori ti o saaju. E jeki a kaa Luku 23:48-49, 55-56, eyi ni yio ran wa lowo lati mo awon eniti oro aropo oruko ‘‘won ’’ ti o wa ni ese ikini duro fun. O duro fun awon obinrin ti a da oruko won ninu ori Bibeli yi ati awon miran ti a ko daruko. Awon Aposteli Jesu Kristi ko si ninu won. Ni kutukutu owuro ojo keta ti Jesu ti ku, awon obinrin lo si iboji pelu ikunra oloorun didun , (23:56, 24:1) lati fon si iboji Jesu Kristi ki ayika naa ba le maa run oorun didun. Nigbati won de ibe,enu ya won; nitori, a ti yi okuta iboji kuro, beeni won ko si ba ara Jesu Kristi nibe. Aare si mu won.(ese 4a). E jeki a beere. Nibo ni awon okunrin wa? A ko ri won. Ohunkan naa ni o nsele ninu ijo loni, ti a ba gbe eto kan kale ni oni,awon obinrin ni o maa yabo ibe, nigbati a lee maa ri awon okunrin kan kan tabi ki a ri die . Ti a ba woye iye awon eniyan ninu ile ijosin, awon obinrin l'opoju. Awon wo ni ogbontagiri ninu isakoso ijo? Awon Okunrin!Wo ayika, awon okunrin melo ni o wa nibi yi ni owuro yi ? Mama, nibo ni oko re ati omokunrin re lo? Awon obinrin gbodo fi owo gidi mu ise igbala oko won ati omokunrin won , ti won bafe gbadun aye won. Gbadura fun won, ki o si gba won niyanju.

**II. AWON OBINRIN RI AWON EDA KAN TI O DA BI ANGELI - ESE 4-8**

Awon obinrin wonyi ri awon okunrin meji ninu aso didan beeni eru ba won. Won fidi ajinde Jesu Kristi mule fun won. Won ran won leti ohun ti Jesu ti so fun won ki o to ku, beeni won si ranti. A ko gbodo maa beru ni gbogbo igba nitori olododo a maa laya bi kiniun. Nigba miran ewe, iriri ti o lee mu eru wa a maa wa, sugbon a gbodo dojuko pelu igboya ati igbagbo.

Gege bi awon obinrin se ranti oro Jesu Kristi, awa naa gbodo ranti awon isotele Jesu Kristi, ki a gbaa gbo, ki a si maa reti imuse re. O seni laanu; awon okunrin ti o ye ki o mu won lokan le ko si nibe pelu won. Eyin okunrin, bawo ni e se maa nti awon aya yin leyin nipa; ti emi,ti ara ati ti eto isuna? Awon okunrin kan wa ti won ko gbogbo eru idile won le awon aya won lori nitoripe won nsise. Eyi ko ye ki o ri bee. A ko so wipe ki awon obinrin ma ran awon oko won lowo, nitori oluranlowo ni eyin mejeji je si ara yin. E jeki a gbe oro yi yewo, ninu awon okunrin ati awon obinrin, tani eni emi ju? (Ejiroro oro yi ni yara ikeko yin)

**III. AWON OBINRIN FI IDI AJINDE JESU MULE FUN AWON OKUNRIN- ESE 9-12**

Awon obinrin naa kuro ni iboji lati lo so fun awon omo eyin mokanla nipa ajinde Kristi. Oruko awon obinrin ti a daruko niwonyi; Maria Magdalene, Joanna, ati Maria iya Jakobu. O yanilenu lati gbo wipe, oro tabi iroyin naa dabi itan tabi aroso lasan leti won, won ko si gba won gbo ayafi igba ti Peteru to wo inu iboji lati fi idi re mule. Pelu odun bi meta ati abo ti won lo pelu Jesu Kristi ati istotele ti o pin pelu won nipa ajinde re saaju iku re, sibe, won ko gbagbo. O han gbangba ninu ile ijosin loni wipe, okan awon okunrin saba ma nle si oro Olorun. Sugbon, nigbakugba ti won ba gba a, won saba ma nle koko nigbati awon obinrin a maa tete gbojegе. Won rorun lati fi awon afefe eko gba lo, paapaa isotele tabi iran. E jeki apari pelu akori eko ti oni bi a ti nse iranti tabi ajoyo ojo isinmi Ajinde ti odun yi. Jesu ti Jinde! Ji igbagbo re! Mase je Kristiani alaigbagbo mo, gba oro Olorun gbo, ati ohun ti Olorun so ninu re, yio si dara fun o.

**AWON IBEERE**

1. Eko wo ni a lee ri ko ninu , ‘‘ Awon obinrin lo si iboji’’?
2. Kini o sele nigbati awon obinrin ri awon eda ti o dabi angeli?
3. Eko wo ni a lee ri ko ninu “Awon obinrin ri awon eda bi angeli?
4. Daruko awon obinrin ti a daruko ninu eko wa ti oni.
5. Iha wo ni awon Aposteli mokanla ko si ohun ti awon obinrin so fun won nipa ajinde Jesu Kristi?

**APRIL 12, 2026** **EKO 15**

# IRIRA LOJU OLORUN

***BIBELI KIKA :-*** *ESEKIELI 8:1-18*

***ESE AKOSORI:-*** *“Pelupelu o wi fun mi pe, Omo eniyan, iwo ri ohun ti won nse? ani irira nla ti ile Israeli nse nihinyi, ki emi ba le lo jinna kuro ni ibi mimo mi? Sugbon si tun yipada, iwo o si ri ohun irira ti o ju wonyi lo” Esekieli 8:6.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 6/4/2026 | Nibo ni o wa? | Gen. 3:1-10 |
| OJO ISEGUN | 7/4/2026 | Olorun ri ohun gbogbo | Owe 15:1-5 |
| OJO RU | 8/4/2026 | Ma se feran aye | I John 2:15-17 |
| OJO BO | 9/4/2026 | Fi ara re fun Olorun | Romu 12:1-5 |
| OJO ETI | 10/4/2026 | A ti ra o ni iye kan | I Korinti 6:19-20 |
| OJO ABAMETA | 11/4/2026 | Gba Aanu | Heberu 4:10-16 |
| OJO AIKU | 12/4/2026 | Tani o le mo? | Jere. 17:9-10 |

**ORO AKOSO**

“Ti Oluwa Olorun wa ni ohun ikoko (Deu. 29:29a). Olorun mo ohun gbogbo, eyi ti o han ni gbangba si eniyan ati eyi ti a n pe ni asiri”. Gege bi Olorun se n ri awon ohun ti a se ni gbangba kedere bee naa ni o n ri awon ohun ti a se ni ikoko. Gbogbo re han kedere niwaju re. Ninu bibeli ti a ka a ri wipe Olorun nfi awon ohun ti o pamo fun awon eniyan han Esekieli. O fi ye wipe awon nkan wonyi ni awon eniyan se ni ikoko, nitori ti won ro pe Oluwa ko ri won, wipe o ti ko aye sile (ese 12d).

Bi a o se maa tesiwaju ninu eko loni, o se pataki ki o mo pe Oluwa nri ohun gbogbo, wipe o mo ohun gbogbo.

## EKO

### I. OLORUN TO MO OHUN GBOGBO

***(a) Olorun ri gbogbo nkan (ese 12)***

"Oju Oluwa nbe ni ibi gbogbo, o n wo awon eni buburu ati eni rere Owe 15:3. Idi ti a ko file ri opolopo nkan ni nitoripe gege bi eniyan a ni awon ohun ti o le se idiwo, eyi nii se pelu osuwon oju wa ati awon nkan ti o wa ni ayika ti o le se idiwo si irira jinna wa. Fun Olorun, ko si idiwo tabi idena kankan, Bibeli fi idi re mule pe oju Oluwa wa ni ibi gbogbo.

***(b) Ta ni o le mo o (ese 7-9)***

"Okan eniyan kun fun etan ju ohun gbogbo lo, o si buru jayi! ta ni o le mo on?" Jer. 17:10. Ko si enikan ti o le so ijinle ika ti o wa ninu elomiran bikose Olorun. Okan eniyan se apere ibi ogbon, ironu ati ibi ti ipinnu ti nwa, a ka si ibi tio pamo julo ninu eya ara eniyan. Sugbon bi o ti pamo to, ko pamo kuro ni oju Oluwa.

Ju ise re ti o dabi wipe o dara lodo awon eniyan ipo wo ni okan re wa? Olorun ko nife si ohun ti a se nikan sugbon ero okan wa bakan naa. Ka Orin Dafidi 19:14. A gbadura pe, nipa oro Olorun, Olorun yoo maa se ayipada okan wa loruko Jesu.

***(d) Mimo awon ohun ti Olorun (ese 6-8)***

Esekieli je okan lara awon eniyan Olorun ti o ku ni ile naa, o je woli Olorun ti o fi ara re jin fun Olorun, nigba ti opolopo tile yan orisa laayo. Idi niyi ti o fi ri oore ofe lati mo ohun ti Olorun. Awon eniyan ti won ti yan Olorun gege bi ini won, won ma n tele ona re. Awon omo Olorun yii ni oore ofe pataki lati mo awon ohun ijinle Olorun ti o ma fihan won (Deut. 29:29b). Omo Olorun ko le se alaini idari nigba ti won ba nilo re, nigba ti won ba fe se ipinnu kan tabi omi, Olorun ma n dari won. Olorun yoo fun o ni okan ti o le mo ohun ijinle ati idari re loruko Jesu.

### II. ORISA NI ILE ISREALI

***(a) Ibi irira ti Olorun ko le gbe (ese 6)***

Olorun kii gbe ile ti o kun fun iborisa, bakan naa ni Olorun ko le gbe okan ti o kun fun orisa nitoripe irira ni si. Kinni awon orisa re, kinni awon ohun ti o mu ni pataki julo, ju Olorun lo? Beere lowo Olorun pe ki O wo aye re, ki O so o di mimo ati ibugbe fun ara re loni.

***(b) Irira ti o tobi julo (ese 15)***

Niwaju Oluwa o ni awon ohun ti a ka si irira titobi julo, eyi ni mimu egbin ba ile Olorun, rire ohun ti Olorun gbega sile tabi ibi ti Olorun pe ni ibugbe. Sise ohun iyasoto ni yepere awon ise yii je iwa irira ti o tobi julo.

Usiah fi owo to apoti eri ni aito eyi si je irira loju Olorun (II Sam. 6:6-7).

Rire ilana ti on ri si akoso ni ile Olorun, fifi ohun ti emi sere, ati fifi ara eni wu iwa ese je irira ti o tobi loju Olorun.

"Tabi eyin ko mo pe ara yin ni tempili emi mimo, ti n be ninu yin, ti eyin ti gba lowo Olorun? Eyin kii si se ti ara yin, nitori naa a ti ra yin ni iye kan, nitori naa e yin Olorun logo ninu ara yin, ati ninu emi yin, tii se ti Olorun" Korinti kinni 6:19-20.

## AWON IBEERE

1. Daruko awon ohun ti o pamo loju Oluwa?
2. Eya ara eniyan wo ni a so pe o pamo julo ninu eko wa loni?
3. Awon nkan wo lo le je orisa ninu aye

onigbagbo?

4. Ki lo de ti Olorun fi fi awon ohun ijinle yii han Esekieli?
5. Awon kinni o ro pe o je irira ti o tobi jojo niwaju Olorun?

**APRIL 19, 2026** **EKO 16**

# MASE DURO DE OJO IDAJO KI O TO RONUPIWADA

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 9:1-11*

***ESE AKOSORI:-*** *"E pa arugbo ati omode patapata, awon wundia ati omo kekeke ati obinrin; sugbon e mase sunmo enikan lara eniti ami naa wa; e si bere lati ibi mimo mi. Beeni won bere lati odo awon agba ti o wa niwaju ile" (Esekieli 9:6).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| **Ojo** | **Deeti** | **Akori** | **Bibeli Kika** |
|---|---|---|---|
| OJO AJE | 13/4/2026 | Ibinu Olorun lori Sennakaribu | Isaiah 37:33-38 |
| OJO ISEGUN | 14/4/2026 | Ironupiwada a maa mu ibukun Olorun wa; sugbon ese n mu iparun wa | Isaiah 1:16-20 |
| OJO RU | 15/4/2026 | Gboran si Olorun ki o ma baa segbe | Iwe Owe 29:1-7 |
| OJO BO | 16/4/2026 | Ibinu Olorun lori Jerusalemu | Esekieli 9:1-5 |
| OJO ETI | 17/4/2026 | Iru awon wo ni o ye ki a da si? | Esekieli 9:6-8 |
| OJO ABAMETA | 18/4/2026 | Ile Israeli, Eese? | Esekieli 9:9-11 |
| OJO AIKU | 19/4/2026 | Je okan ninu awon ti o ronupiwada | II Chron. 7:11-15 |

## ORO AKOSO

Aanu Olorun n duro de awon eniyan ti won ronupiwada kuro ni ona buburu ti won wa si odo Oluwa; JESU KRISTI. Sugbon iparun ni fun awon okan ti o ba taku sinu ese won ti won si ko lati ronupiwada kuro ni ona buburu won. E gbo eyi:

*Olorun ni onidajo ododo, Olorun si n binu si eniyan buburu lojoojumo; Bi on ba yipada, yoo si pon ida re mu; o ti fa orun re le na, o ti mura re sile. O si ti pese elo iku sile fun un; o ti se awon ofa re ni onina. Kiyesi i o n robi ese, o si loyun iwa ika, o si bi eke jade. O ti wa ofin, o gbe e, osi bo sinu iho ti on na wa. Iwa ika re yoo si pada si ori ara re, ati iwa agbara re yoo si sokale bo si atari ara re (Orin Dafidi 7:11-16).*

Ronupiwada nisinsin yii, fi opin si gbogbo ririn ninu iwa ibi, bi iwo ba gbe igbese yii, iwo yoo ri ojurere Olorun (II Kronika 7:14).

## EKO NAA

**I. JERUSALEMU ATI IBINU OLORUN (Esekieli 9:1-6a)**

***(a) Jerusalemu: Ilu Olorun; ilu Alaafia***

Ki lo sele ti ilu ti Olorun yanfe fi wa di ilu ti Olorun n binu si? Ilu naa ti yipada kuro ninu eyi ti Olorun fe ki o je lati ibere wa. Ni ese keji, awon okunrin mefa ti awon ti ihamora ohun ija ogun ni owo won wa lati dojuko awon olugbe Jerusalemu (ese 1-4). Kinni o fa eyii? Nitori pe Jerusalemu ti ko Olorun sile. Fi eti sile si ikilo lati inu oro Olorun. Yipada kuro ninu gbogbo ona buburu re. Ibinu Olorun n bo wa si ori ile aye nitori awon ese ati iwa buburu ti o gba gbogbo aye ni akoko yii. Ko ye ki iwo ki o je alabapin ninu ibinu ti n bo naa.

***(b) Iru awon Eniyan kan pelu iru ami kan (ese 4-5)***

Iranti isele ile Gosheni ati iku akobi omo ti eniyan ati ti eranko ninu iwe Eksodu 12:29-33 se pataki nibi ti eko wa de yii. Awon eniyan ile Egypti nikan ni o fi ara gba ogun ofo ati iku akobi omo ti awon eniyan ati ti eranko, sugbon aabo Olorun bo awon omo Israeli ti o wa ni ile Goseni nigba naa, won ko si ni ipin ninu iyonu ati ibanuje naa. Bakan naa, ninu eko wa ti oni, nigba ti awon kan ye fun iku, Olorun pase pe awon ti iru ami kan wa ni ara won ko gbodo ku (ese 4). Gbogbo eni ti o ba wa ninu JESU KRISTI ki yoo ni ipa ati ipin ninu ibinu ti n bo sori ile aye. Nitori naa, mo eyii wi pe Olorun feran re ko si fe ki o wa laarin awon ti yoo ri ibinu re, bikose awon ti yoo ri ojurere RE.

**II. IPARUN GBOGBO-GBOO FUN JERUSALEMU (Ese 7-11)**

***(a) Pa Gbogbo won (ese 6-7)***

Iwo ki yoo ni ipa ati ipin ninu ibinu Olorun ti n bo wa si ori ile aye bi iwo ba lee ronupiwada ti o si wa si odo Jesu Kristi ti I se Oluwa ati Olugbala (Johannu 3:14-17).

***(b) Wa Ojurere Olorun; Mase wa Ibinu Re (ese 9-10)***

Iwo ni Ominira lati yan eyii ti o ba wu o, eniyan lee yan IGBALA, o si ni ominira lati yan nnkan miran. Gbo oro Olorun yii "Bi elese tile se ibi nigba ogorun, ti ojo re si gun, sugbon nitooto, emi mo pe yoo dara fun awon ti o beru Olorun, ti o beru niwaju re. Sugbon ki yoo dara fun eniyan buburu, beeni ki yoo fa ojo re gun ti o dabi ojiji, nitoriti ko beru niwaju Olorun" (Oniwaasu 8:12-13).

**<u>AWON IBEERE</u>**

1. Eese ti Alaafia Jerusalemu fi yipada si iparun?
2. Iru awon wo ni ki yoo ri iparun pelu oluse buburu ninu eko toni?
3. Ninu iwe Oniwaasu ori 8:12-13, so iru awon eniyan tabi egbe meji ati eke won.
4. So ohun ti o sele si awon omo Egypti ati eyii ti o sele si awon omo Israeli ti o wa ni ile Goseni ni Eksodu 12.
5. Nje o see se ki enikan bo ninu ibinu ti n bo wa si ori ile aye? So ohun ti iwo ro wipe iru eniyan bee yoo se ti o ba fe bo

**APRIL 26, 2026** **EKO 17**

# IRAN OLOGO TI A FI HAN WOLI ESEKIELI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 10:1-22*

***ESE AKOSORI:-*** *"Eyi ni eda-alaaye ti mo ri labe Olorun Israeli ni eba odo Kebari; mo si mo pe Kerubu ni won" (Esekieli 10:20).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Monday | 20/4/2026 | Ko si eni ti Oluwa ko lee farahan | I Sam. 3:1-4 |
| Tuesday | 21/4/2026 | Sora fun ohun ti yoo mu ki Emi Oluwa kuro lodo re | Onidajo 16:20 |
| Wednesday | 22/4/2026 | Gbogbo won si kun fun Emi-mimo | - Ise A.A. 2:1-4 |
| Thursday | 23/4/2026 | Ifarahan ni oju-ran nipase Ebi | Ise A.A. 10:9-15 |
| Friday | 24/4/2026 | Olorun ma n fara han nipase jije olufokan sin | Ise A.A. 10:1-4 |
| Saturday | 25/4/2026 | Aigboran le mu ki emi Oluwa fi eniyan sile | I Sam. 16:14-16 |
| Sunday | 26/4/2026 | Isipaya ti a fi han fun woli Esekieli | - Esekieli 1:1-5 |

### ORO AKOSO

A si woli Esekieli loju lati ri iranti o logo nibi kika wa ti oni. Eyi ti o nso nipa ohun ti yoo sele si awon omo Israeli ni ti Tempili Oluwa ti o wa ni Jerusalemu, wipe, ogo-Oluwa Olorun yoo so kale, yoo si bo ile naa fun igba kan, sugbon lati ipase ailee ronupiwada ese won, nigba ti o se, a o ka ogo naa kuro. Igbekele wipe Oluwa Olorun si wa pelu awon, yoo lo kuro. Eyi ti a ri ninu awon ese oro Olorun ti a ka loni (vs. 1-22). A fi isipaya yi han nipa aworan Kerubu ati keke. Eyi nje ki o ye wa wipe, ko si ohun ti Olorun ko lee lo lati fi ranse si eniyan ati lati kilo iwa (Num. 22:28-33).

### EKO

**I. OGO OLUWA OLORUN KUN INU TEMPILI (Vs. 1-15)**

Ogo Oluwa Olorun ni kikun inu Tempili n sapere oro Olorun ninu iwe Ise Awon Aposteli, ni ori-keji, lati ese kinni de ese ikerin (Ise A.A. 2:1-4) wipe gbogbo won si kun fun Emi-mimo, ina ti a ri laarin awon Kerubu nibi ti a ka loni ntoka si bi Emi-mimo se sokale ti o wa ni aworan ela-ahon, ti ina ti o ba le awon omo eyin Jesu ni yara oke ni ojo Pentikosti (Ise A.A. 2:1-4). Ti gbogbo won si kun fun Emi-mimo.

Ari isokale ogo Olorun bi oti se kun ile Olorun ti a mo si Tempili Olorun. Eyi ti o fi han pe, Olorun ngbe inu ile naa. Abajo ti Paulu Aposteli fi so wipe awa ni Tempili-Emi-mimo fun awon ijo Korinti (I Kor. 6:19). Fun idi eyi, a gbodo mo ohun ti a je, ki a si sora gidi-gidi ki a mase ba Tempili naa je, ki Olorun ma baa si kuro ninu aye wa tii se Tempili Emi-mimo, ibugbe Olorun ni a je, ki a mase ba ibugbe naa je.

**II. AISE-DEEDE MU KI OGO OLORUN SI KURO NINU TEMPILI (VS. 16-22)**

Isi-kuro awon Kerubu nsapere isi-kuro ogo-Olorun ninu Tempili. Eyi nse apere ohun irira ati ara ibaje awon omo-Israeli. Awon eni ti ogo Oluwa kuro laye won po ninu Bibeli. Die lara won ni a ti ri Samsoni eni ti o titori obinrin so agbara re nu, elomiran ni Saulu-oba, emi-igberaga, aigboran ati ijo'ra eni loju mu ki emi Olorun dagbere fun un (I Sam. 16:14). Bakan naa ni Emi otito sonu mo Anania ati aya re lowo; won seke si Emi-mimo, won ku iku aitojo, abbl. Ogo-Olorun si kuro ninu Tempili ni Jerusalemu. Kin ni awa naa nse tabi fe se, ti yoo mu ki Emi-mimo dagbere fun wa, eyi ti a fi se edidi wa de ojo idande (Efe. 4:30). E jeki a yago fun un. Aye wa ko ni di idakuda ni oruko Jesu Oluwa.

### AWON IBEERE

1. Ka ese akosori wa ti oni.
2. So ni soki, ohun ti isokale ogo Oluwa Olorun ntoka si ninu eko wa ti oni?
3. Kinni Aposteli Paulu pe ni Tempili ti

Olorun ni oni ati wipe ninu iwe wo ni a ti le ri apere re ninu Bibeli?
4. Kin ni ina laarin awon Kerubu nsapere ati irufee re ti a le ri ninu Majemu Titun?
5. Daruko awon eni-meji ti Emi-mimo Olorun fi sile ninu Majemu laelae, ati eni-kan ninu Majemu Titun?

**MAY 3, 2026** **EKO 18**

# NINU EGBE AWON ENIYAN BUBURU TABI TI AWON ENI IWA-BI-OLORUN

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 11:1-12*

***ESE AKOSORI:-*** *"Bi elese tile se ibi nigba ogorun, ti ojo re sigun, sugbon nitooto, emi mo yoo dara fun awon ti o beru Olorun, ti o beru niwaju re; Sugbon ki yoo dara fun eniyan buburu, beeni ki yoo fa ojo re gun ti o dabi ojiji, nitoriti ko beru niwaju Olorun" (Oniwaasu 8:12-13).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 27/4/2026 | Ere awon eni buburu ati ere awon eni iwa-bi-Olorun | Orin Dafidi 1:1-6 |
| Tuesday | 28/4/2026 | Iwa buburu awon eniyan buburu | Orin Dafidi 7:9-17 |
| Wednesday | 29/4/2026 | Angeli Oluwa yi awon eniyan re ka | Orin Daf. 34:1-12 |
| Thursday | 30/4/2026 | Sa fun awon ohun ti ise buburu; ko lati se rere | Orin Dafidi 34:1-12 |
| Friday | 1/5/2026 | Mase dara po mo awon oluse buburu | Esekieli 11:1-7 |
| Saturday | 2/5/2026 | Iparun lori awon asebi | Esekieli 11:8-12 |
| Sunday | 3/5/2026 | Se rere: Ka (Reap) rere | Ifihan 22:6-14 |

## ORO AKOSO

"Eniyan gbe oju re le; sugbon eni iduro-sinsin li o nmu ona re to" Owe 21:29). "Eni irele ati iberu Oluwa li oro, ola, ati iye. Egun ati idekun mbe li ona alayidayida; eni ti o ba pa okan re mo yoo jinna si won" Owe 22:4-5. "Eni ti o nni talaka lara lati mu oro po ti o si nta oloro lore, yoo di alaini bi o ti wu ki o se" (Owe 22:16). "Mase ja talaka li ole, nitori ti ise talaka; beeni ki oma si se ni oluponju lara niibode: Nitori Oluwa yoo gbija won, yoo si gba okan awon ti ngba lowo won" (Owe 22:22-23).

Se asaro daradara (meditate fully well) lori awon ese Bibeli oke yii, e o si ri dajudaju wi pe awon eniyan buburu ka eso ise buburu won ati pelu awon olododo ka eso ododo (eso rere) ise won. Egbe wo ni iwo wa ninu awon mejeeji? Ninu eko ti oni, awon ogun eniyan ya ara won si oto kuro laarin awon onise ibi (ese 1). Ikilo fun enikookan ni wi pe ki awa naa ya ara wa si oto kuro laarin awon oluse buburu, ki a ronupiwada ki a si jeki Emi mimo maa se akoso aye wa (II Kronika 7:14; Matteu 3:2).

## EKO

**I. AWON ENIYAN BUBURU ATI ISE WON (Ese 1-4)**

***(a) Egbe awon oluse buburu; nje un ko ha wa laarin won? (ese 2-3)***

Bibeli pe iye won ni meedogbon (ese 1). Ninu ijo Olorun ni oni, mase je okan ninu iru awon eniyan wonyii, ti n da rukerudo sile ninu ijo tabi ni awujo paapa laarin awon ti won duro deede ti won si je eni iwa-bi-Olorun.

***(b) Jaasania ati Pelatia: Awon olori ati adari awon oluse buburu (ese 1)***

Opolopo awon eniyan miran ni won laya tabi ti won gboya lati da ote sile ninu ijo Olorun tabi laarin awujo (society). Iru won a maa so orisiirisii oro buburu si awon iranse Olorun tabi si ijo. Iru won ti fi ara won jin patapata fun satani lati je ohun elo fun iwa buburu. Ko ye ki o wa ninu iru awon eniyan wonyii, ko ye ki oruko re han laarin awon ti okan won kun fun buburu sise.

***(d) Ise won (2-3)***

Won a maa ni ero iwa ika, won a maa gba awon ara ilu ni imoran buburu. Won ni ero wipe ko si ohun kan ti yoo sele ti o je bii esan tabi ere ise buburu ti awon n se. Opolopo naa ni n gbo oro Olorun ni akoko ti wa yii wi pe ki won yipada si Olorun, ki won wa si odo Jesu Kristi tii se Oluwa ati Olugbala, sugbon ti won ko eti didi si oro oore-ofe naa. Olorun je onife, o si n pe gbogbo eniyan lati wa sinu igbala ayanfe omo Re tii se JESU KRISTI.

***(e) Egbe rere ti o ye ki iwo ati emi o wa niyii (Orin Dafidi 119:63)***

***(e) Egbe buburu ko ye iwo ati emi (II Korinti 6:14-18)***

*E mase fi aidogba dapo pelu awon alaigbagbo; nitori idapo kili ododo ni pelu aisododo? Idapo kinni imole si ni pelu okunkun? Irepo kinni Kristi si ni pelu Beliali? Tabi ipin wo li eni ti o gbagbo ni pelu alaigbagbo? Irepo kinni tempili Olorun si ni pelu orisa? Nitori eyin ni tempili Olorun alaaye; gege bi Olorun ti wipe, Emi o maa gbe inu won, emi o si maa rin ninu won; emi osi je Olorun won, won o si je eniyan mi. Nitori naa e jade kuro laarin won, ki e si ya ara yin si oto, li Oluwa wi, ki e mase fi owo kan ohun aimo; emi o si gba yin. Emi o si je Baba fun yin, eyin o si je omokunrin mi ati omobinrin mi, li Oluwa Olodumare wi.*

**II. IBINU OLORUN LORI AWON ENIYAN BUBURU (Ese 5-12)**

Wo orisiirisi ona ti Olorun ni OUN yoo gba mu ibi wa si ori awon alaigboran ati Oluse buburu wonyii nitori wi pe won ko gboran si gbogbo ikilo Olorun,bee won yipada ni ona ibi won.

Ni akoko yii Oluwa n ke fun awa iran yii lati ronupiwada, Olorun feran re sugbon o korira ese ninu aye re. E jeki agbo ohun ti ELEDA wa n so; Eyin iranse Olorun, Alagba, Diakoni, Oluko ile Eko Ojo Isinmi, Akorin, Asona, Igbimo Ijo, Oloye Orisiirisii ninu ijo, omode ati agba, ati gbogbo ijo “Iwo ko gbodo to opolopo eniyan leyin lati se ibi, beeni iwo ko gbodo soro li oran ki o te si opo eniyan lati yi ejo po” (Eksodu 23:2) pelu asaro kikun ka Heberu 12:14).

## AWON IBEERE

1a. Awon melo ni awon eniyan ti won je oga awon asebaje ninu eko ti oni? So eko ti a lee ri ko ninu aye won.

b. Daruko awon eniyan meji ninu eko toni ti o wa laarin awon Egbe Oluse buburu naa ati eko ti a ri ko ninu ipo ti won di mu.

2. So awon ise ati ise awon egbe buburu yii ati eko ti o koni.

3. Se alaye awon olododo ati awon eniyan buburu ki o si so ere ti o wa

ninu okookan.
4. Nje ireti wa fun elese? Fi ese Bibeli gbe idahun re lese.
5. So awon ise Emi mimo gege bi ese karun ti wi ninu iwe eko wa ti oni ki o si so pataki ise ti Emi mimo n ko ninu aye ati irinajo Kristiani ni akoko yii.

**MAY 10, 2026** **EKO 19**

# OLUWA NBA AWON TIRE WI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 11:1-25*
***ESE AKOSORI:-*** *"Iberu eniyan buburu, nbo wa baa; sugbon ife olododo ni a o fi fun-un" Owe 10:21).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| **Ojo** | **Deeti** | **Akori** | **Bibeli Kika** |
|---|---|---|---|
| Monday | 4/5/2026 | Laisi ese, ijiya ko si | Owe 26:1-3 |
| Tuesday | 5/5/2026 | Ohun ti a gbin ni a o ka | Isaiah 3:10-11 |
| Wednesday | 6/5/2026 | Owo Oluwa ko kuru lati gba ni | Isaiah 59:1-4 |
| Thursday | 7/5/2026 | Ma se alainaani ibawi Oluwa | Heberu 12:4-9 |
| Friday | 8/5/2026 | Ma se fi aaye sile fun ota, ki o ma baa jare re | Jere. 50:7 |
| Saturday | 9/5/2026 | Ohun ti ese maa n mu wa | Gen. 3:7-10 |
| Sunday | 10/5/2026 | Sora fun idajo Olorun | Esekieli 11:7-12 |

**ORO AKOSO**

Yoruba bo ninu owe won, pe "Bi ina ko ba tan ni aso, eje kii tan ni eekanna". Iyen ni igbe aye awon omo Israeli. Bi Olorun ti nba won se bii baba si omo to, ise ni won nsubu sinu ese okan ko jo okan. Nibi ti a tun ye wo lonii, a rii ka wipe awon okunrin-agbani-ni 'moran-ika kan ko ara won jo ti won nda ilu ni imoran buburu (ese 1-3). Olorun ranse ohun ti yoo sele si won ni ese 4-13. Otito ni pe Olorun feran elese sugbon ko fe ese. Nitori naa, e je ki a ronupiwada aisedeede wa gbogbo. E mase je ki a duro de ibawi tabi idajo Olorun ki a to yipada. Iwe Owe je ki o di mimo fun wa pe "omo mi, bi awon elese ba n tan o, iwo mase gba (Owe 1:10). Bakan naa ni Paulu Aposteli je ki o di mimo pe "Egbe buburu ba iwa rere je" (I Kor. 15:33). Fun idi eyi, ejeki a mo irufee imoran ti a o maa teti si ati lati gba. A ko ni gba ibinu Olorun.

**EKO**

**I. AWON AGBANI NI IMORAN IKA ATI IBI (Ese 1-3)**

Ojo pe ti a ti nri awon agbani-ni imoran ika ati ibi. Yato si ibi ti a ka loni, irufee won ni ore-okan ninu awon omo Dafidi ti o fe ba aburo re ni asepo, ti ore re fun un ni imoran buburu (2 Samueli 13:1-16).

Bee ni ibi ti a ka loni, awon adani ni imoran fi okan olugbe orile-ede Israeli bale pe ko si ewu kan, awon ti wa nibi ipamo, laisi Olorun laarin won. Eko-nla ni eyi n ko wa lonii lati sora fun awon onimoran ika, ki a mase gba gbogbo emi gbo, sugbon ki a dan won wo bi iba se ti Olorun. L'oruko Jesu Oluwa, a ko ni fi ara gba idajo ati ibinu Olorun.

**II. IKEDE IRUFEE IDAJO ONIPELE MARUN TI N BO WA SORI AWON**

**OLUGBE JERUSALEMU (Ese 4-13)**

i. Nitori ti won so oku ti won pa di pupo ni ilu,
ii. Won fi oku kun igboro,
iii. Nitori ti won ko rin ninu ase Oluwa Olorun won,
iv. Won ko mu idajo Olorun se
v. Nitori ti won huwa buburu ati iborisa ju gbogbo awon orile-ede ti o yi won ka lo.

Nitori awon iwa buburu wonyii ati aigboran won, Olorun ni Oun yoo je won niya. Kinni awon iwa ati ise ti wa naa loni, ti yoo mu ki Olorun binu si wa? E jeki a tete se atunse, ki ojo ibinu Olorun to ro.

**III. AANU OLORUN FUN AWA OMO RE (Ese 4-21)**

Nitori ti Olorun fe araye to bee ge, ti o fi omo bibi Re kan soso fun ni... (John 3:16-17). Bee ni Olorun saanu fun awon omo Israeli lati da die si ninu won ti ki yoo parun tan.

Bee ni aanu Olorun yi wa fun awa naa lonii. E jeki a gbaa, ki a si ye.

**AWON IBEERE**

1. Ka ese akosori wa ti oni, ki o si fi ko wa ni eko laarin iseju meji.
2. Eni melo ni awon agbani ni imoran ti a ri kani ibere iwe ti a ka loni?
3. Daruko awon ijoye pataki meji ti a daruko ninu iwe naa?
4. Kin ni atubotan ere ese ninu eko wa ti oni?
5. So meta ninu ese marun ti awon omo Israeli da ninu eko wa ti oni?

**MAY 17, 2026** **EKO 20**

# KIYESI IKILO OLORUN

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 12:1-7*

***ESE AKOSORI:-*** *"Ibukun ni fun eniti o beru nigba gbogbo.. sugbon eniti o ba se aiya re le ni yio subu sinu ibi Owe 28:14.*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON. | 11/5/2026 | Nje iwo nkiyesi ikilo Wonyii? | Luk 21:34-36 |
| TUE | 12/5/2026 | Mase alaika ikilo Olorun si | Jak-1:22-25 |
| WED | 13/5/2026 | Sa asala fun Emi re, Gbo Ikilo | Gen.19:17-25 |
| THÚ | 14/5/2026 | Idiyele iwa Aigboran | Gen. 3:9-19 |
| FRI | 15/5/2026 | Igboran san ju Ebo ruru lo | I Sam 15:17-23 |
| SAT | 16/5/2026 | Igboran, ona si Ibukun ati Alaafia | Lef-26: 3-18 |
| SUN | 17/5/2026 | Ifoju Temi | Esk 12:1-6 |

## ORO AKOSO

Ile-aye kun fun opolopo ikilo. Eniyan ngba ikilo lati dena ohun buburu. Ikilo je ona ti a ngba fi aanu han fun eniti a ko fe ki o bo sinu ijiya tabi isoro nipase ohun buburu ti eniyan ba yan.Ikilo ma  nsaaju ki wahala to sele nigba ti akoko si wa lati se atunse .Kiko ikilo ma nyorisi wahala.

Olorun pase fun woli Esekieli lati fi oro asotele re se ere ori itage lati fi se Ikilo fun awon omo Israeli ti o ti wa ni igbekun ki won ki o le mo ewu ti o nbo wa sori awon yoku won ti o seku si ilu Jerusalemu. Pe laipe a o ko won ni igbekun ti won yoo si wa darapo mo awon ti o ti wa ni Babiloni. sugbon o seni laanu pe awon eniyan naa ko ka ikilo yi si titi asotele naa fi wa si imuse.

Olorun po ni anu, O feran elese sugbon o korira ese O ma nlo orisi ona lati so ife re di mimo  fun eniyan, O si ma nfi se ikilo ewu ti o le wa ninu kiko ife re. Oun ma nfi aye sile fun ironupiwada fun gbogbo eniti o ba ti setan lati yipada ki o ma ba ri ibinu Re. Olorun yii tun npe ikilo loni, nje iwo ngba ikilo Re? “Nitorinaa O ye ti awa iba ma fi iye gidigidi si ohun wonni ti awa ti gbo, ki a ma ba gba wa lo kuro ninu won nigbakan” Heb 2:1. Gboran, kiyesi ikilo Olorun gidigidi, mase fi ironupi wada kuro ninu ese re da ola.

## EKO

### I. AKAWE AWON IGBEKUN

**(a) Won je olote eniyan (ese 2)**

“Omo enia, iwo ngbe arin olote ile?” Ote didi tumosi yiyapa, lati tako ase kan. Olote eniyan ma n se atako ase, olote soro lati dari. Awon olote eniyan kii tele ase lati ibi orisun ase ijo, ibi ise, tabi awujo. Won gbagbo pe ogbon tiwon lo dara ju. Iwa ote je ese niwaju Olorun. Neh-9:26 o dabi ese afose 1Sam. 15 23. Opolopo apere awon olote lo wa ninu Bibel.i Oba Saulu. 1Sam15 22-23 Awon omo Israeli ni aginju. Orin Dafidi 78: 17-19 Kora, Datani, ati Abiramu. Num.16:1. Olorun pe awon igbekun wonyii ni olote eniyan nitoriti won ko lati gbo ikilo. Enikeni ti o ba ti ko idari Olorun ninu aye re je olote eniyan, Olorun yoo si da gbogbo eniti o ba ti tako ase Re lebi, nitorinaa, ma se je olote tabi darapo mo awon olote eniyan.O.D.68:6.

**(b) Won je alaimoye (ese 2)**

“ti won ni oju lati ri, ti won ko si ri; nwon ni eti lati gbo nwon ko si gbo- nitori olote ile ni nwon’’(ese 2).

Awon igbekun yii je aditi ati afoju ninu emi nitori iwa agidi ati iditi won, woli Esekieli nilati lo ere itage lati fi ba won soro. Jesu pa owe kannaa fun awon Farisi (ka. Matt. 13: 13-15) ati Isaiah 6:9, Jer 5:21). Opo lo tun je ope si oro Olorun loni, bi o tile je pe won mo pe idajo Olorun nduro de elese sibe won ko lati ronupiwada. Iha wo ni iwo naa nko si oro Olorun ti o ngbo? Ronupiwada loni mase se okan re le.

### II. ASE TI OLORUN PA FUN WOLI ESEKIELI (Ese. 3-6)

Olorun a maa ba wa soro ni oniruru ona bi o ba ti wu, O le ba wa soro nipase oro Re (bibeli) iran, ala, asotele, tabi awon isele ninu aye. Olorun pase fun woli Esekieli lati lo ere itage fun awon omo Israeli ni igbekun boya won yoo ni oye ohun buburu ti o nbo wa sele si awon eniyan won tï o ku ni ilu Jerusalem (ese 3).

A paa lase fun woli naa lati di eru re sinu apo ki o si ko jade ni osan gangan ki awon eniyan yii le ri ki o se bi eniti o nlo si irin-ajo ni ona jinjin.

Ni ale, nigbati ile ba ti su ki o gbe apo naa le ejika re ki o wa iho ni ara ogiri ki o se bi eniti o nwa ona lati salo, ki o fi aso bo oju re bi eniti ko mo ibi ti o nlo. Itan fi ye wi pe asotele yii wa si imuse lakoko isejoba Sedekiah oba ti o gbeyin ni ile Juda. Nigbati o ngbero lati salo kuro ni ilu o wa iho ninu ogiri ni aafin lati ri aye salo, sugbon o bo sowo awon omo ogun Nebukadnesari, won mu ni dide lo si Babiloni (2 Awon Oba 25:4-7).

Eredi ere itage yii ni lati ba awon eniyan Re soro nipa bi ese won se buru to ati iwa agbere ti o mu itiju wa pelu iwa aigboran yii se gbe won de ile igbekun. Eru inu apo ti o gbe si ejika re nsapere ese nigbati bibo oju tumosi itiju ti yoo de ba won nitori iwa aisoto won.O se Pataki fun won lati ronupiwada,ere itage yii je ikilo fun won.

**III. WOLI ESEKIEL GBORAN SI ASE OLORUN - Ese 7.**

Woli Esekiel se gegebi Olorun ti pase fun ni aiko ba Olorun jiyan. Igboran je amin omoleyin Kristi tooto, ife Re gbodo je ife tiwa. Gbogbo Kristiani ni o ye fun lati je onigboran si oro Olorun.

**AWON IBEERE**

1. Taani Olote?
2. Kinni ohun ti Olorun pe awon igbekun?
3. Ase wo ni Olorun pa fun woli Esekieli?
4. Kinni idi ti woli ni lati fi ere itage waasu?
5. Nje asotele naa pada wa se.

**MAY 24, 2026** **EKO 21**

# AWON AMI IDAJO OLORUN

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI.12:8-20*

***ESE AKOSORI:-*** *"Awon ilu ti a ngbe yio di ofo,ile na yio si di ahoro, enyin o si mo pe emi li Oluwa". Esekieli.12:20.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 18/5/2026 | Abayori iwa Buburu | O. D .1:4-6 |
| Ojo Isegun | 19/5/2026 | Opin Eni Buburu | O.D. 9:16-20 |
| Ojoru | 20/5/2026 | Ojo Oluwa | 2 Pet.3:9-12 |
| THU. | 21/5/2026 | Ojo Nla Oluwa | Joeli .2: 1-10 |
| FRI | 22/5/2026 | Olorun Onidajo ti kii soju saaju | Deut. 10:17-22 |
| SAT | 23/5/2026 | Gbogbo idajo je ti Olorun | Rom. 2:1-16 |
| SUN | 24/5/2026 | Idajo Olorun lori awon Olote Eniyan. | Esk 12:9-20 |

**ORO AKOSO**

Awon ami ko ipa pataki ninu Bibeli, o je eri ase ifowosi Olorun fun awon adari t'emi ati woli ti a yan. Nigba ti Olorun pe Mose, O fun un ni ami ti o fi idi ipe re mule (Eks 4:1-9) Jesu ati awon Aposteli se ise iyanu pelu awon ami to nte lee lati le fi eri ase at'oke wa han (Mk 2:32, (Ìk. 2:3-12; Ise. Áñï. 3:1-11).

Ami tun je ona lati pe ikilo lori ohun ti nbo. Ninu ibi kika wa loni, ami so nipa ikilo idajo Olorun ti o nbo wa sori orile ede Israeli. Ere-itage ti woli Esekieli se je ami fun won pe orile ede naa yoo lo si igbekun, won yoo mu oba won ni dide lo si igbekun ni Babiloni nibiti yoo ku si (ka imuse asotele yii Awon Oba Keji. 25:1-21).

Bibeli pe ikilo pe ki a ma sakiyesi awon ami igba ikeyin (Matt. 24. 3-31; Lk. 21:36, 2Tim. 3.1-5) Awon isele ti o n sele kakiri agbaye loni je awon ami igba ikeyin, Nje iwo n kiyesii awon nkan wonyii, E jeki a gboran si awon ikilo Olorun wonyii, ki ojo naa ma ba de ba wa lojiji.

**EKO**

**I. IHA TI WON KO SI ORO NAA - ESE 8-9**

**(a) Ibeere - ese 8-9**

Nigba ti o di owuro leyin ti woli Esekieli ti lo ere itage (drama) lati fi je ise Olorun fun awon Juu ti o wa ni igbekun. Won wa si odo re, won si fi awada beere lowo re itumo ere itage ti o se fun won tan nisinyii. Gbogbo ere itage ti woli se ko ni itumo kankan si won beeni won ko kaa si. Opo ni ko ka iwaasu igbala si ohun ti o se pataki loni, fun awon elomilran, won ti ka iwaasu bibo Jesu si iwaasu ti ko ba ode oni mu mo. Nitorinaa, a gbodo ma a kiyesi awon oro Olorun ti a n gbo ki a má ba ni ipin ninu ibinu Olorun. Heb. 2:1-3.

**(b) Idahun - ese 10**

"Wi fun won pe, Bayi li Oluwa Olorun wi; Eru yi han fun awon omo alade ni Jerusalemu, ati gbogbo ile Israeli ti o wa larin won" (ese 10) Olorun pa lase fun woli Esekieli lati je ki won mo iwuwo oro naa. Oro "Eru" ti a lo ninu ese yii nso bi oro naa se l'agbara tabi wuwo to niitori o kun fun ibinu Olorun, o nso nipa awon ti o se ku ni ilu Jerusalemu ati Sedekiah oba won. Jesu pelu sokun fun Jerusalemu nitori o ti ri iran iparun ti o nbo wa sele si ilu naa. (Lk-19:41) Nje awa Kristiani loni tile nri iran ibinu Olorun to o nbo wa sori aye? Nje a gba pe o kan wa lati kilo fun iran tiwa yii nipa idajo Olorun t'ohun bo? Akoko niyi fun wa lati ronupiwada, ki a si kede ikilo.

**(d) "Wipe emi ni ami yin, gegebi mo ti se beni a o si se won"**

Woli Esekieli je ami fun won, o ti fi ere itage se ami ohun ti o nbo wa sele si oba Sedekiah ati awon olugbe Jerusalemu to ku. Eleyii tumosi pe, won yoo ni irisi ere ori itage to o se fun won.

**II. ITUMO ORO NAA - Ese 11-15**

Niwon igbati won ko lati ni oye ninu ere itage naa, woli so itumo atupale oro naa.

1, Oba Sedekiah yoo di eniti won ko ni igbekun.
2. Yoo gbiyanju ati sa asala nigbati awon ota ba wo inu ile naa.
3. Yoo gbe eru re si ejika yoo gbiyanju ati lu iho lara ogiri afin lati sa asala fun emi re, yoo fi nkan boju ki won ki o ma ba daa mo, sugbon omo ogun Babiloni yoo da a mo, won o si mu u nitori gbogbo awon omo ogun re ni yoo ti tuka ti won o si mu u ni dide lo si Babiloni ni ibiti yoo ku si gegebi asotele woli Jeremiah. (Jer 35.18) Sora fun ese o nyorisi igbekun ati iku.

**III. AANU OLORUN - ESE 16**

Olorun a ma saanu ninu idajo ninu anu re, O gba awon die sile ninu ajalu ilu naa, ko je ki won ko won ni igbekun, ki won ki o le mo anu Olorun, ki won ki o si mo pe Oun je olooto nipa idajo Re. Awon eniyan naa lo si igbekun nitori ese won ti won ko lati ronupiwada kuro ninu re, nitorinaa Olorun ko jebi. A gbodo mo riri anu Olorun ti o mu wa ki a wa laaye pelu isele buburu ayika wa, o ye ki a si ma dupe lowo Re pelu ni si sin in ninu igboran wa.

**IV. IDAJO OLORUN ESE 17-20**

Olorun tun pa lase fun woli Esekieli lati tun se ere itage miiran lati fi se ikilo fun awon olugbe ilu Jerusalemu nipa iparun ti o bo wa sori Ilu naa., Yoo di piparun ti ki yoo si si olugbe nibe mo bi won ko ba yipada. Idajo yoo wa sori Ile naa nitori iwa buburu awon olugbe ilu naa. Eleyi je ikilo fun gbogbo oluse buburu pe idajo Olorun yoo wa dandan, nitorinaa, iwo oluse buburu yara lati yipada loni ki idajo to de.

Mase ro pe lati igbati iwo ti ndese yen ko si ohun buburu kan to sele, eleyi ko tumo si pe idajo Olorun ko ni de, Olorun nmu suru fun o pe boya iwo yoo ronupiwada lo anfani yii lonii (2 Pet 3.9).

**AWON IBEERE**

1. So awon pataki ami.
2. Iha wo ni awon eniyan naa ko si ere itage ti woli Esekieli fi waasu?
3. Kinni itumo ere itage naa?
4. Bawo ni Olorun se fi ife Re han si Israeli pelu iwa aigboran won?
5. Se alaye iwe 2 Peteru. 3:9. ni afiwe igba Ikeyin.

**MAY 31, 2026** **EKO 22**

# EWU IKEGAN ORO OLORUN

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 12: 21-28*

***ESE AKOSORI:-*** *"Ki e ko mo eyi pe, nigba ojo ikehin, awon elegan yio de pelu egan won, nwon o ma rin nipa ife ara won" 2 Peteru 3.3.*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 25/5/2026 | Otito ni oro Olorun | Rom. 3:1-8 |
| TUE. | 26/5/2026 | Awon Ileri Olorun Daju | Heb.6:13-20 |
| WED | 27/5/2026 | Olorun yoo se Awon ohun ti o seleri | Num. 23:17-24 |
| THU | 28/5/2026 | Akoko Olorun lo dara Ju | Gen.18:9-15 |
| FRI. | 29/5/2026 | Mase Kegan oro Olorun | 2 Pet. 3:1-9 |
| SAT | 30/5/2026 | Ko si Idaduro Mo | Esek. 12:23-25 |
| SUN | 31/5/2026 | Yoo wa si Imuse | Esek 12: 26-28 |

**ORO AKOSO**

Leyin igbati woli Esekieli tun se ere itage miiran lati fi kilo fun won nipa idajo Olorun ti ko le sai wa sori won, O gba won niyanju lati yipada si Olorun, ki won ko dekun lati maa gbekele awon woli eke ti won ntan won je pelu asotele eke pe alaafia ati ibukun pupo ni fun won nigba ti Olorun nkede idajo ati iparun. Won kegan asotele otito yii won n so wipe lati igba ti awon woli ti n so asotele idajo Olorun ti nbo ko si okan ti o wa si imuse-dipo bee nkan tun dara si fun awon. Nje iru iwa bee ko ha wopo ni awujo wa loni? A feran asotele eke ju otito oro Olorun lo. Ki o ye wa pe ko si ohun ti aye le ma so, Oro Olorun je otito titi lae (Rom 3:4; Owe.30:5) Awon ohun ti Olorun ti so nipa aye re, igbeyawo re, ayanmo re, yoo wa si imuse. Gba a ki o si gbeke lee.

**EKO**

**I. WON KEGAN ORO NAA**

**(a) Won wipe a fa ojo gun - 22**

"Omo enia, Owe wo li enyin ni, ni ile Israeli pe, A fa ojo gun, gbogbo iran di asan?" Nitoriti Olorun fa ojo idajo re seyin eyi mu ki won ko ro pe suru Olorun je ailagbara Re lati mu asotele naa se. Ni idi eyi won npa owe fun ara won pe Olorun ko le mu idajo Re se, won mu awon woli Olorun ni eke woli, sugbon Olorun je onisuru ati alaanu, O nmu suru boya won yoo yipada kuro ni ona buburu won. Iwo elese mase tan ara re je, suru Olorun ko tumosi ailagbara Re o fun o ni anfani lati yipada ni.

**(b) Won wipe gbogbo iran ni ko wa si imuse - 22.**

Won kegan oro Olorun pe gbogbo iran ati asotele ti a ti enu woli so ko si okan ninu re ti o se nibe, won kegan oro Olorun ,won ko si ka oro Re si. Nje iwo ha nsiyemeji awon ileri Olorun fun o bi? O si ti nsu o lati maa gbekele re lee. Mase so ireti nu bi o tile pe duro yoo wa si imuse. (Hab. 2:3).

**II . IGBESE OLORUN SI IWA IKEGAN**
**WON - ESE -23-25**

**(a) Olorun fagile owe egan won.**

Olorun fun won ni esi pe Oun yoo fi opin si owe egan ti won npa ki yoo si idaduro mo lati mu oro idajo Re se. Eleyii ni yoo fi opin si ise awon woli eke ti o wa larin won ti won nso asotele wipe asotele naa ki se fun iran won bikose iran ojo iwaju. Sugbon Olorun wipe Oun yoo mu ki asotele naa se ni iran won. E jeki a fi owo Pataki mu oro Olorun mase alaikasii (Matt. 24:35).

**III. ITESIWAJU LATI KEGAN ORO NAA**
**- Esek. 27-28**

**(a) Won wipe ojo idajo naa si Jina -**
**ese 27**

“Omo enia, kiyesii, awon ara ile Israeli wipe, iran ti o ri fun ojo pupo ti nbo ni o si so asotele akoko ti o jina rere” (ese 27). Won kegan Iran ati asotele naa, wipe iran naa ki yoo wa si imuse, bi yoo ba tile ma wa si imuse yoo gba Opolopo odun si asiko yii. Awon eniyan naa gbo asotele naa lati enu woli Olorun sugbon won ro ninu ara won wipe ko le sele. Opo eniyan lo wa loni ti won ngbo ikilo, sugbon ti won nso wipe awon si ni opolopo akoko si lati lo fun ara won ki won to yipada. Kinni ko je ki iwo pelu gbe igbese igboran loni ? Fifi akoko da ola ni ewu.

**(b) Idajo ki yoo je sisun siwaju mo**

“Nitorinaa wi fun won pe, Bayi li Oluwa Olorun wi: ko si okan ninu oro mi ti a o fa gun mo, sugbon oro ti mo ti só yio se ni Oluwa wi”. Suru Olorun ti d’opin Oun yoo si mu idajo Re wa sori won. Pinnu loni lati ronupiwada awon ese aye re ma se fi da ojo miiran, nitori iwo ko mo ohun ti yoo sele ni iseju die si akoko ti a wa yi, a ko mo ile ti yoo mo ola.

**AWON IBEERE**

1. Iru iha wo ni won ko si oro woli naa?
2. Kinni Igbese ti iwo nreti ki awon eniyan yen ko gbe leyin ti won gbo oro naa?
3. Idahun wo ni Olorun fi da won lohun owe egan ti won npa?
4. Bawo ni o se le se afiwe idahun naa pelu awon iha ti a ko si oro Olorun ni iran ti wa yii.

**JUNE 7, 2026** **EKO 23**

# IDAJO OLORUN LORI AWON WOLI EKE

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 13:1-16*

***ESE AKOSORI:-*** *“Eso won li enyin o fi mo won.Enia a ma ka eso ajara lori egun ogan? tabi eso opoto lara ewon ? Matthew 7:16.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 1/6/2026 | Sora fun Awon onise iyanu Eke | Deut.13:1-5 |
| TUE | 2/6/2026 | Mase jeki a tan o Je | Ifihan-13:7-18 |
| WED. | 3/6/2026 | Dan gbogbo Emi wo | 1 John 4:1-6 |
| THU | 4/6/2026 | Sora fun awon Woli Eke | Matt 7:15-20 |
| FRI- | 5/6/2026 | Ami awon Woli Eke | 2 Pet 2:1-3 |
| SAT | 6/6/2026 | Olorun koro oju si awon Woli Eke | - Esek. 13:1-7 |
| SUN. | 7/6/2026 | Olorun yoo se idajo awon woli Eke | Esek-13:8-16 |

### ORO AKOSO

Awon woli je gbohun gbohun Olorun, ti o ye lati ma so okan Olorun fun awon eniyan Re. Awon woli tooto ki soro nipase ase tara won sugbon won a ma soro bi Olorun ba ti fi fun won. Awon Omo Israeli wa ninu Idamu, nitoriti awon ota ti wo inu ilu won, opo ninu won ni won ti ko ni igbekun lo. Ni Iru akoko bayi won nilo idari emi fun ona abayo.

Sugbon Olorun ti gbe awon woli Re dide fun won bi woli Jeremiah, eniti o sotele si awon ti o seku ni Jerusalemu (Jer. 32: 26-30) ati woli Esekieli eniti Olorun ran si awon ti o wa ni igbekun lati yipada kuro ninu ese iborisa eyiti o gbe won de ipo ti won ba ara won. Awon woli Olorun yii ro won lati ronupiwada kuro ninu ese won.

Ibanuje nla ni o je pe awon eniyan wonyi ko tile t'eti si ikilo awon woli Olorun sugbon dipo eyi won ko awon woli eke jo ti o ntan won pelu awon asotele ati iran eke, won nseleri alaafia nigbati Oluwa kede iparun. Awon eniyan a ma fe gbo iro ju otito lo. Otito koro sugbon o ni ere. Olorun gbaye fun awon woli eke wonyi lati fi dan awon eniyan tire wo, lati mo ipo ti okan won wa si Oun Olorun. Jesu ti so asotele pe awon woli eke yoo po ninu aye ni igba Ikeyin. Bawo ni a o se da awon woli tooto mo yato si ti eke ka Deut 13: 1-5; matt 7:15 -20. Awon woli buburu yoo wa labe idajo Olorun, won yo si gba ere ise won ni keyin.

### EKO

**1. OLORUN TAKO AWON WOLI EKE**

**(a) Won je woli eke - Ese 2**

Bi o jile je pe awon woli eke yii je iran Israel sibe Olorun Israeli ko yan won, Olorun ko ran won nise beni won ko gba ase lati odo Re (Jer 23:21) Woli tooto gbodo je eniti Olorun ran. Nje iranse Olorun ti a ran ni iwo bi?

**(b) Won ko fi emi Olorun so asotele - ese 3**

Awon woli eke wonyii ko fi emi Olorun so asotele, won gba imisi nipa ero inu won,won nlo oruko Olorun lati so asotele eke. Siso asotele lai je ipase emi Olorun je ewu nla ti o le mu ki opo eniyan si ese gbe eyiti o le yorisi ijiya nla nikeyin.Sora, nitori iwo yoo jabo ise re niwaju Olorun (Ekun Jeremiah 3:27).

**(d) Eke ni won, won ko ri iran kankan ese 3**

Awon woli eke yi je akojopo awon opuro, won ntan awon eniyan je nipa ijewo pe iran won ti odo Olorun wa (ese 6 &7) Sugbon Olorun tako oro won pe Oun ko ran won. Fi ara re jin fun oro Olorun ki awon woli eke ma ba si o lona. Otito ti o ba mo ni yoo so o di ominira, mo otito. John. 8:32.

**II. ESUN TI A FI KAN AWON WOLI EKE**

**(a) Won kun fun iwa arekereke**

"Israeli awon woli re dabi kolokolo ni ijú" (ese 4).

Olorun fi won we kolokolo ni aginju. Kolokolo je alareke-reke eranko (Luk. 13:32) O ma nba eso inu ogba ajara je (Orin Solomoni 2:15, Ekun Jeremiah-5.18) Awon woli eke yi lo anfani ipo isoro lati tan awon

eniyan je, mase Jeki isoro ninu aye re ti o lo si ibi ti ko ye. Awon woll eke yi ti kun ita bayii, erongba won ni lati ti ipase isoro awon eniyan di olowo. Iwo yoo bori isoro re loruko Jesu.

**(b) Won ko gba ilu sile (ese 5 & 6)**

Ojuse awon adari ni lati dabobo ilu won,awon woli pelu je adari temi ti o ye ki o le dabobo ilu won nipa temi,won ye lati le di alafo ibi ese ti o fa ipinya laarin awon eniyan naa ati Olorun. Dipo ki awon woli yii se ikilo fun ironupiwada, won nmu ki won ni igbekele pe Olorun ko ni mu idajo wa sori won, Awon woli yii ko se ikilo tabi gbadura fun ewu ti nbo. Kristiani loni je oluso fun iran yii Olorun gbekele wa fun igbala iran tiwa loni, a gbodo dide lati se ikilo fun aye, ewu ti o wa ninu ese ati idajo Olorun fun elese (Esk 22:30).

**III. IDAJO OLORUN LORI AWON WOLI EKE - ESE 8-16**

**(a) Won yoo so ipo won nu - ese. 9**

Awon woli eke wonyii yoo so ipo won nu larin awon eniyan Olorun. Awon woli ni ile Israeli je eni ola sugbon nitori asotele eke, awon woli wonyii ki yoo je kika mo awon woli Israeli mo. Ese a ma mu itiju ati abuku wa. Kinni o da o duro ti iwo ko ni fi ronupiwada nisinyii ki ese to ko abuku ba o.

**(b) Won yoo so jije omo ilu nu ese 9.**

Awon woli yii yoo so anfani jije omo orile ede nu. Oruko won ko ni si ninu akosile awon omo Israeli Gbogbo opuro ni yoo ni ipin won ninu ina orun apadi nitori ki yoo si oruko won ninu iwe iye (ifihan 20:15).

**(d) Won yoo so eto won lati wo ile Israeli nu**

Won ki yoo ni eto lati ba awon yoku pada si orile-ede Israeli leyin ti aadorin odun ti won yoo lo ni igbekun ba pe, won yoo ku si ile igbekun. Elese ti o ba ko lati ronupiwada ki yoo le wo ijoba orun nikeyin.

**AWON IBEERE**

1. So awon idi ti Olorun fi doju ja ko awon woli eke wonyii?
2. Kinni idi ti Olorun fi gbaye fun awon woli eke lati maa so asotele eke?
3 Bawo ni a se le mo iyato laarin woli eke ati woli otito?
4. Bawo ni a se safiwe awon woli bi kolokolo ni aginju. Se alaye lona wo?
5. So awon ohun ti yoo je idajo Olorun lori awon woli eke wonyii.

**JUNE 14, 2026** **EKO 24**

# IDAJO OLORUN LORI AWON WOLI EKE OBINRIN

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 13 17-23*

***ESE AKOSORI:-*** *"Nitorina enyin ki yio ri asan mo, e ki yio si ma fo afose, nitoriti emi o gba awon enia mi kuro li owo yin, enyin o si mo pe emi li Oluwa. Esekieli 13:23*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 8/6/2026 | Awon Ebun Emi | 1 Kor. 12:4-11 |
| TUE | 9/6/2026 | Sise aferi awon Ebun Emi. | 1Kor.14: 14.1-6 |
| WED | 10/6/2026 | Pataki awon Ebun ise Iranse | Efesu 4:11-16 |

| | | | |
|---|---|---|---|
| THU | 11/6/2026 | Omobinrin kan ti o ni emi Afose | Ise Apo. 16.16-24 |
| FRI | 12/6/2026 | Woli ati Asotele. | IseApo. 21:10-14 |
| SAT- | 13/6/2026 | Sise isakoso oro Asotele | Ikor 14:29-33 |
| SUN | 14/6/2026 | Olorun se idajo awon Woli-Eke | Esek. 13:20-23. |

## ORO AKOSO

Ninu Bibeli, gegebi a ti ni awon woli okunrin bee gege ni a ni awon obinrin ni ipo woli. Fun apere; Miriamu. Eks 15:20; Debora Onidajo 4:4; Hulda 2 Awon Oba 22:14; 2Kro.34:22; Anna omobinrin Fanueli. Lk. 2:36; Awon omobinrin Filipi merin. Ise Apo 21:9; Awon woli eke obinrin bii Noadiah Neh. 6.14 ati Jesebeli Ifihan. 2:20. Bi a ti ni awon woli Olorun tooto loni beni a ni opo woli eke l'okunrin ati l'obinrin. A gbodo dan gbogbo emi wo. 1 John 4:1-3 A gbodo ma kiyesi iwa won. Matt 7:15. Awon woli tooto ma ngbo lati odo Olorun, won a si ma se ife Re, Woli eke a ma se ife ti ara re. Woli tooto a ma koro oju si ese, oun a ma ba ese wi, sugbon eke woli kii ba ese wi dipo bee yoo ma gbe ese laruge. Woli eke le sise iyanu ki o si ma riran, sugbon lati tan nije ni . Awon woli eke miran a ma lo afose, idan, emi aje ati oso eyiti Olorun lodi si. Eks 22:18; Deut 18:10; Ise Apo 8:11, ifihan 9:21.

Awon woli ninu ibi kika wa toni nlo agbara okunkun lati fi so asotele eke ti won si ti ipase eleyi pa opo okan run. Won se onde ati ifunpa (Charm & amulet) fun awon eniyan lati fi se abo fun emi won. Olorun yoo se idajo gbogbo awon oniro, atannije ati pelu gbogbo awon woli eke.

## EKO

**I. ESUN SI AWON WOLI EKE OBINRIN**

**(a) Won so asotele lati inu okan won ese. 17**

Olorun doju ija ko awon woli eke ti won so asotele lati inu ero inu okan ara won, sugbon won nso wipe Olorun ba awon soro, won nso asetele lati inu imisi eran ara dipo imisi ati odo Olorun wa. Nje awon iran, ala tabi asotele re je lati odo Olorun wa bi?O je ohun ti o dara lati ri iran tabi so asotele, o je okan ninu ona ti Olorun gba ba wa soro, sugbon, o gbodo je ohun lati odo Olorun.

**(b) Won kun fun ise itanje-ese 18.**

Won nse ise oso ati aje, won nso ohun elo fun ise afose, won fun eniyan ni igbadi, onde ati ifunpa (Charm & amulet) lati ma wo sara fun abo ara won, Olorun lodi si awon ise ba wonyii, O fi won gegun.Won je ajenirun ti o n de awon sile fun eye tabi eranko lati ko sinu re. Fi Jesu se abo re, mase lowo ninu iwa ibi wonyi nitori idajo Olorun yoo wa sori awon ti o ba nse iru ise ba wonyii.

**(d) Won nsotele fun owo - ese 19.**

Awon woli eke obinrin wonyii, so pe awon nsotele l'oruko Oluwa, sugbon iro ni, fun ikun ara won ni won se eyi. Won nlo anfani isoro awon eniyan lati filu won ni jibiti, won,nyi awon eniyan lokan kuro lodo Olorun nipa asotele, ati iran eke won. Dipo ki won pe elese si ironupiwada, won tun mu won sina, won nfi asotele won pa olododo, ti won si da awon eniyan buburu si. Nje asotele iran, ati ala re ngba emi la tabi pa emi run?

**II. IDAJO OLORUN LORI AWON WOLI EKE OBINRIN - ESE 20-23**

**(a) Olorun yoo fi opin si iran eke won**

Won ki yoo ri iran eke mo, nitori Olorun yoo mu opin de ba iran ati asotele eke won. Asiri ise won yoo tu, won yoo di eni itiju, won ki yoo si wulo mo.

(b) Olorun yoo fa awon ohun elo ise afose won ya, igbadi ati onde gbogbo ni a o si parun pata pata. Iyi ati ola won ni a o gba kuro nitori a o gba agbara afose won a o si dana sun won.

(d) Olorun yoo si gba awon eniyan Re kuro lowo won, Oun yoo si mu won pada si ile won. Eleyi nipa imu-pada awon omo Israeli si ile ini won leyin ti aadorin odun igbekun ba pe. Jesu Kristi yoo wa ni ojo kan lati

wa gba awon eniyan tire kuro ninu aye buburu yii ti yoo si mu won lo si ijoba Re ni orun John 14: 1-3, Ifihan. 21: 1-4 Nje iwo pelu yoo wa pelu Jesu nibe?

**AWON IBEERE**

1. Daruko awon obinrin merin ninu Bibeli ti won je Woli tooto.
2. Daruko obinrin meji ninu Bibeli ti won je woli eke.
3. Awon esun wo ni a fi kan awon woli eke obinrin ti inu eko yi?
4. So awon idajo Olorun lori won.
5. Awon eko wo ni o tun ti ko ninu eko toni gege bi o ti se ye o si?

**JUNE 21, 2026** **EKO 25**

# AWON ALAGABANGEBE ELESIN

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 14:1-11*

***ESE AKOSORI:-*** *"O dahun o si wi fun won pe, otito ni Isaiah sotele nipa ti enyin agabagebe, bi a ti koo pe, Awon enia yi nfi ete won bola fun mi, sugbon okan won jina si mi. Marku 7:6.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 15/6/2026 | Mase Je Alagabangebe Eniyan. | MK-7:5-13 |
| TUE | 16/6/2026 | Jesu ba awon Alagabangebe wi | Matt. 23. 23-29 |
| WED | 17/6/2026 | Sora fun Iwa Agabangebe | Mk. 12:38-40 |
| THU | 18/6/2026 | Je Oluse oro Naa. | Jak-1:21-26. |
| FRI | 19/6/2026 | Ore ti o se Itewogba | Matt. 6:1-4 |
| SAT | 20/6/2026 | Iborisa inu Okan | Esek 14:3-5 |
| SUN | 21/6/2026 | Idajo Olorun lori Alagabangebe | Esek-14:6-11 |

**ORO AKOSO**

Alagabangebe eniyan ni eniti o npe ara re ni ohun ti ko je. Alagabangebe a ma farahan lode bi olododo sugbon oun je eletan ninu. Nigbati o ba nsoro iro ni o nso. Oun ki fi awon ohun ti o ba nso sinu ise. Oto ni ohun ti o nse. Alagabangebe yoo so igbe aye ti o dara lati gbe, sugbon oun pelu ko ni se bee. Olorun korira ahon eke. Owe 26.28. Jesu ba awon Farisi ati awon akowe wi fun iwa agabangebe won, O pe akiyesi won si eto ijosin ti won kun fun nigbati won ko ka idajo ododo si. Won ni imo nipa iwe mimo ti won nfi koni sugbon awon tikalara won ko se awon ohun ti o wa ninu re. Opo ni won nyin ara won pe awon ti di atunbi, won si mo Bibeli sugbon igbe-aye won je odikeji ohun ti won so pe awon je, iwo nko loni?

Awon agbagba ile Israeli to woli Esekieli wa lati gbo ohun Olorun lori isoro ti o dojuko ilu won, sugbon orisa wa ninu okan won. Won farahan gegebi elesin tooto ni ode sugbon won je aborisa ninu okan won.Olorun mo okan wa, a ko le fi ohunkohun pamo fun un (Gal 6:7) A le tan eniyan bi tiwa, sugbon Olorun ni enikeni ko le tan.

**EKO**

**I. IWA AGABANGEBE AWON ALAGBA NAA**

**(a) Won wa itoni Olorun - ese 1**

Awon alagba gegebi asoju awon omo Israeli wa si odo woli Esekieli, lati bere ona lowo Olorun nipa isoro ti o de ba won ni ile igbekun ti won wa, ati awon yoku ni Jerusalemu. Gegebi eko wa ati eyin wa, won ba ara won ninu isoro yii nitori ese iborsa eyiti o mu won wa ni igbekun nile ajeji. Nisinsin yii won ranti Yaweh Olorun won. Nibo ni iwo pelu ma nsa lo nigbati isoro ba de ba o? Nje iwo mo Olorun nigbati gbogbo nkan ba nlo dede fun o? Wa Oluwa ni gbagbogbo ki o le gba o, mase duro de igbati isoro ba de ba o. (O.D. 34:4; 119:2).

**(b) Won wa Olorun pelu orisa ninu okan won - ese 3-4**

Oluwa kii wo bi eniyan se nwo, awa eniyan a ma se idajo lori irisi ni ita, sugbon Oluwa a ma wo okan (1 Sam. 16:7) Olorun je olumo ohun gbogbo, Oun mo awon ero inu wa. Nitooto ni awon alagba wonyii ti won je asiwaju esin wa si odo woli lati mo ohun Olorun lori oro won,won je adari ti o ye ki won ni iwa mimo ninu aye won. Won wa si iwaju woli gegebi eniti won fe mo otito oro Olorun, won se bi eniyan mimo, sugbon eke ni won, orisa nbe ninu okan won. Won farahan bi olujosin tooto, sugbon ninu won, aborisa ni won.

Orisi ona iborisa lo wa, awon orisa ti a le fojuri ati eyiti a ko le fojuri. A le ma ni ere gbigbe gegebi orisa ninu ile wa ti a nsin eyiti a le fojuri, sugbon opolopo igba ni a n sin awon orisa aifojuri yii, ohunkohun ti a ba ti gbe soke ju Olorun lo ninu aye wa, fun apere ife ara eni, owo, ise, idile wa, ere idaraya, ero ayelujara, abbl. awon wonyi ti di Olorun laye wa. Olorun bere fun ifi ara eni jin pata pata wa, Je ki Olorun je akoko ninu aye re.

**II. IDAHUN OLORUN SI IBEERE WON - ESE 4-6.**

**(a) Olorun fun won ni idahun**

Olorun se ileri lati da awon alagba Israeli wonyii ti won wa si odo Re pelu orisa ninu okan lohun bi o tile je pe, won pa ese mo sinu okan won, ti won si se bi eniyan mimo niwaju Oluwa. Olorun jeki o di mimo fun won pe, ko si ohun ti o pamo fun Oun, won yoo si gba esi ibere won gegebi o ti to. Olorun so di mimo pe ni gbigba orisa laye ninu okan won tumosi pe won ti fi orisa ropo Oun Olorun. Ko gbodo si ifagagbaga tabi orogun laarin orisa ati Olorun alaaye. Taani Oluwa okan re? Lati fe ara eni, owo, oro aye ju Olorun lo ninu okan wa tumosi pe ati fi awon nkan wonyii, ropo Olorun, nitorinaa, Olorun onife npe wa bi a ti nko eko yii lati fi Oun se akoko ninu aye wa.

**III. IPE SI IRONUPIWADA ESE 6-7.**

**(a) Ipe lati yipada.**

Olorun je alanu, O gba awon eniyan Re niyanju lati ko awon olorun eke wonyii sile,ki won si yipada sodo Oun. Bi o tile je pe, won dese, Olorun ko ko won sile, o fe ki won ronupiwada. Ore! Ipe ironupiwada ndun si eti elese loni lati yipada kuro ninu ese si odo Olorun bi o ti wu ki ese naa buru to, Oun yoo gba o (Isaiah.1:18) O feran re, ko fe ki o segbe, fi aye re fun loni.

**IV. ABAYORI IWA IBORISA WON - ESE 8-11**

**(a) Olorun yoo ko won sile**

Bi O tile je pe awon eniyan naa wa si iwaju Oun Oluwa pelu orisa ninu okan won lati wa bere ona abayo, Oun Oluwa pelu yoo ko won sile gegebi won se ko Oun sile lati sin orisa. Olorun ni agbara sibe ko si ohun ti ko le se ni akoko ti o ba yan, ese ninu okan wa ni o ndena isegun wa.(Isa.59:1).

**(b) Olorun yoo pa won run**

Abayori iwa Iborisa ni wipe, Oun Olorun yoo pa awon woli eke won run ati gbogbo awon ti o tele oro won. Oun yoo fi titobi han lori awon orisa ti won gbekele, Oun yoo si gba awon eniyan Re. Mase gbaye fun oro aye lasan laaye,ki o dipo Olorun ninu okan re. Maa ronu oro(wealth) ti o wa loke. (Kolosse 3.2).

**AWON IBEERE**

1. Taani Alagabangebe eniyan?
2. Kinni idi ti awon agbagba Israeli se lo si odo woli Esekieli?
3. Se alaye orisa aifojuri ati orisa ifi oju ri.
4. Kinni idahun ti Olorun fun awon agbagba naa?
5. Kinni Olorun so pe yoo je atubotan abayori ese won ti won ko ba ronupiwada?
   So itumo oro yii.

**JUNE 28, 2026** **EKO 26**

# IDAJO OLORUN DAJU LORI JUDA

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 14 12-23*

***ESE AKOSORI:-*** *"Bi a tile fi owo so owo, enia buburu ki yio lo laijiya, sugbon iru omo olododo li ao gbala. Owe 11:21*

**<u>BIBELI KIKA OJOOJUMO</u>**

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 22/6/2026 | Ibinu Olorun lori Gbogbo aiwa bi Olorun | Rom 1:18-23 |
| TUE | 23/6/2026 | Ibinu Olorun si Alaigboran | Efesu 5:1-7 |
| WED | 24/6/2026 | Olorun nbinu si Eni buburu | Owe 15:8-9 |
| THU | 25/6/2026 | Sa asala fun Emi re | Gen.19:14-17 |
| FRI | 26/6/2026 | Sa fun Ibinu ti nbo | Matt 3: 7-10 |
| SAT | 27/6/2026 | Ojo Idajo ti a ti yan. | Ise Apos. 17:22-31 |
| SUN | 28/6/2026 | Idajo Nbo | Esk-14:12-21 |

**ORO AKOSO**

Ninu eko ti o koja, a ko bi awon agbagba awon eniyan naa se wa si odo woli Esekieli lati mo okan Olorun lori ipo wahala ti ilu Jerusalemu wa. Bi o tile je pe won mo otito oro naa, won ko lati ronupiwada, won fi ese pamo sinu okan, won se bi eni mimo. Nihinyii, Olorun so di mimo fun won iru idajo ti Oun yoo ran si awon eniyan Juda fun titesiwaju ninu ese won, ti ki yoo si ona abayo. Awon eniyan wonyii lero pe Olorun le yi ipinu Re pada ki o si da idajo re duro bì o ba ri awon olododo ninu ilu naa. Sugbon Oluwa wipe bi awon olododo bii Noa, Danieli, ati Jobu tile wa ninu ilu naa, won ki yoo le gba enikeni la bikose emi awon tikalarawon. Idajo naa yoo je ipele merin, iyan, eranko buburu, ogun ati ajakale arun. Eleyii so bi ese dida se buru to ati ijiya ti ma tele e.

Sibe ninu eyi, Olorun yoo tun fi anu Re gba awon kan la ninu ewu naa kii se nipa didara won, bikose nipa anu Olorun nikan. Won ki yoo ku tabi ni ipin ninu gbogbo ewu wonyii Sugbon a o ko won ni igbekun lo si ile Babiloni. Bibeli se ikilo, pe idajo ti o daju nduro de elese ti o ko lati yipada won yoo lo ayeraye won ni orun apadi, nitorinaa yipada loni fun igbala okan re.

**EKO**

**I. ALAYE IRU IDAJO NAA - ESE 13-21**

**(a) Idajo Iyan. ese 13-14**

Olorun ti se ikilo fun orile-ede naa nipa ewu ijiya ti yoo ba won ti won ba se aigboran si ofin Oun ti won ba da a. Deut 28:15-40 Olorun yoo ran iyan si ile naa. Tele awon eniyan wonyii lero pe bi Olorun ba ri awon olododo ninu ilu naa ao gba ilu naa sile nipa ododo won. Olorun so fun won wipe bi Noa, Danieli ati Jobu tile wa ninu ilu naa ododo won ki yoo le da idajo duro. Awon eniyan meteta ti a daruko wonyii je awon eni igbagbo, ati olooto ti won si fi ji je olododo won han ni igba aye won. Kinni awon eniyan yoo so nipa iwa ati igbe-aye re ni igbati iwo ko ba si laye mo?

**(b) Idajo nipa eranko buburu - ese 15-16**

Olorun ran won leti oro Re ninu iwe Lefitiku. 26 :22 wipe Oun yio ran eranko buburu sarin won tì yoo pa awon omo won, ti yoo si je awon ohun osin won, ti won ba kuna lati pa ofin Oun mo. Nihinyii Olorun yoo mu ki eranko buburu ki o ma pa won ninu ilu won, kii yoo si enikeni ti yoo le lo si irin ajo tabi jade nitori awon eranko buburu yii yoo ti gba ilu won ,a o si so ilu won di ahoro.

**(d) Idajo nipa ogun. ese 17-18**

Olorun yoo tun gba awon orile-ede ajeji laaye lati wo ile won, won yoo pa won ati awon ohun osin won gbogbo laisi anu. Bakannaa, Olorun tun so wipe bi awon olododo meta wonyii Noa, Danieli ati Jobu tile wa ninu ilu naa, won ki yoo le gba a sile, won ki yoo le gba omo won okunrin tabi obinrin pelu bikose emi awon tikalarawon. Igbagbo oko re, aya re, tabi awon obi re ko le gba o la. Olukuluku ni o gbodo sise fun igbala emi ara re.

**(e) Idajo nipa ajakale arun - ese 19-21**

Olorun tun wipe Oun yoo tu ibinu jade nipa riran aisan ati ajakale arun si ile naa. Ajakale arun yoo tun pa opolopo eniyan ati eranko, awon opopo ona ni adugbo yoo kun fun oku eniyan ati eranko. Bakannaa Oluwa tun tenumo pe bi awon olododo meteta wonyii ba wa ninu ilu naa iwa ododo won ki yoo le gba idile won sile bikose emi awon tika lara won. Jesu se ikilo fun awon alaigbagbo Juu pe ki won mase gbekele ododo baba nla won Abrahamu lati gba won, sugbon won gbodo yipada kuro ni ona buburu won, ki won ki o le wu Olorun. Johanu 8:39-47. Olorun ti so pe olukuluku yoo ru aise dede tire. Lef.5:17; 7:18, Gal. 6:5.

Awon idajo ipele merin yii ti ko le sai wa sori ilu Juda gegebi a ti so asotele lati enu woli Jeremiah bi idajo naa yoo ti buru to, ti o si daju pe yoo sele si won ti won ba kuna lati yipada. Eleyi nran wa leti pe Olorun yii kanaa ti yan ojo kan ti yoo se idajo aye ese yii, Jowo tete gbo ikilo ki o si yipada loni lati le bo ninu idajo ti nbo (Ise Aposteli 17:22-31).

**II. AANU LORI IDAJO - ESE 22-23**

**(a) Igbala awon ti yoo ku sile.**

Olorun ninu anu Re yoo da awon kan si ti won ko ni pin ninu ajalu ti yoo pa awon eniyan ile naa, sugbon won yoo ri anu gba. Awon eniyan wonyii yoo bo ninu ewu naa kii se nipa ododo won, sugbon won je apere elese ti o ri anu gba nigba idajo. Nitorinaa, niwon igbati o si wa laye, lo anfani oore - ofe yii lati fi aye re fun Jesu mase fi igbala re da ola.

**(b) Idalare Olorun ese 23:**

Awon ti won mu ori bo ninu ajalu naa ni won yoo ko ni igbekun lo si Babiloni lati dara po awon ti o ti wa nibe tele Nibe, awon igbekun yoo ri daju pe Olorun se olooto ni idajo Re, won yoo si ri iwa buburu ti awon eniyan naa wu ti o mu dajo wa si ori won.

## AWON IBEERE

1. Daruko ipele idajo ti yoo wa sori ilu Juda
2. Awon olododo meta wo ni a daruko ninu ibi kika toni.?
3. Awon eko wo ni a le ri ko inu aye won?
4. So idi ti Olorun ko fi ni bu ola fun wiwa awon olododo meteta naa lati ma pa ilu naa run.
5. Nje a le da Olorun lebi fun bi o se mu idajo wa sori awon eniyan wonyii?

**JULY 5, 2026** **EKO 27**

# IGI AJARA TI KO WULO

| | |
|---|---|
| ***BIBELI KIKA:-*** | *ESEKIELI 15:1-8* |
| ***ESE AKOSORI:-*** | *"Ati nisisiyi pelu, a ti fi ake le gbongbo igi na, nitorina gbogbo igi ti ko ba so eso rere, a o ke e lule ao si wo ju sinu ina. Matteu 3:10* |

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 29/6/2026 | Igi Alaiseso | Luk.13:6-9. |
| TUE | 30/6/2026 | Awon Olusogba Buburu | Luk 20:9-19 |
| WED | 1/7/2026 | Nipa Eso Won la o Fi mo won | Matt 7:15-20 |
| THU | 2/7/2026 | Awon Eso T'emi | Gal.5:22-24 |
| FRI | 3/7/2026 | Nje iwo nso eso rere | John 15:1-5 |
| SAT | 4/7/2026 | Igi Ajara ti ko Wulo | Esk. 15:1-5 |
| SUN | 5/7/2026 | Idajo lori Igi Ajara Alailleso | Esk15:6-8 |

## ORO AKOSO

Idi pataki ti a n fi gbin igi eleso ni ki o le so eso ti o dara, sugbon ti igi ba kuna latí so eso ohun ti o ye ni ki a ge iru igi be lule. Olorun yan orile-ede Israeli lati je orile-ede tire. A fi Israeli we igi ti a gbin si ile ti o ni ora lati so eso ti o dara. Olorun mu won jade kuro ni oko eru ni Egypti O si gbin won si ile Kenani lati jogun ibe. Olorun kilo fun won gidigidi lati mase lowo si isin awon orisa ile naa nitori Olorun owu ni Oun. Orile ede Israeli je igbadun opo ibukun Olorun ni akoko Oba Dafidi niwon igbati won ngboran si ase Re. Leyin eyi ni Solomoni omo re ko esin iborisa wo orile ede naa nipase awon ajoji obinrin ti o fe ni iyawo. Fun idi eyi, pupo ninu awon oba ti o je leyin re ni won je aborisa ti won ti ipa be se aigboran si Olorun. Olorun nreti ki won so eso igboran, sugbon, eso ote ni won so, Olorun nreti ijosin tooto sugbon emi iborisa ni o kun okan won. Israeli di orile-ede ti ko wulo lodo Olorun nitoriti won kuna lati kun oju osuwon. Fun idi eyi , Olorun yoo yo won kuro ni ile naa, gegebi agbe ti se fa irugbin ti ko so eso kuro ti yoo si dana sun won . Eleyii ye ko je eko fun wa loni pe a gba wa la lati le gbe igbe aye ti o wu Olorun ni, nitorinaa a gbodo Kiyesi ara bi a se nlo ile aye wa.O ye lati bi ara wa lere nje mo ngbe igbe aye ti o wu Olorun bi ko ba ri bee, e jeki a tete yipada ki a ma di eni itanu ni ikeyin.

**EKO**

**I. IGI AJARA TI KO WULO**

**(a) Afiwe igi Ajara - ese 3.**

"Omo enia, kini igi ajara fi ju igikigi lo, tabi ju êka ti o wa laarin igi igbo?" Idi ti a fi gbin igi naa ni lati so eso iru re, igi ajara yii niye lori ju gbogbo igi inu igbo yoku lo, a ko gbin fun idana sugbon fun eso dara dara fun agbe lati le je. Igbe aye kristiani tooto ye ki o kun fun eso iwa rere, a yan wa lati le so eso gegebi imole o ye ki aye ma ri iwa kristi lara wa. (Johanu15:16) Nje iwo ti di atunbi bi? Nje igbe aye re nso eso emi Olorun bi a ti se ka sile ni ninu iwe Galatia 5:22-23 Lati le so eso rere, a gbodo ma gbe inu kristi nitori yiya ara wa kuro lodo de Re a ko le se ohunkohun. (Johanu 15:5-6).

**(b) Ko wulo-fun ohunkohun, ese 3**

"A ha le mu igi lara re se isekise? tabi enia le mu ekan lara re lati fi ohunkohun ko sori re?" Orile-ede Israeli ti a yan, ti a gbin, ti a si se itojù di ohun ti ko wulo mo lowo Olorun nitoriti o kunna lati so eso ti o dara. Nitorinaa, ibinu nla Olorun yoo wa sori orile-ede ti o ko lati yipada. Igi inu igbo lasan ni iwulo ju igi ajara ti a gbin ti a toju sugbon ti ko so eso , ko tile wulo fun ikole, ohun kan soso ti o wulo fun ni idana. Kristiani ti ko ni iwa rere amuye ko yato si alaigbagbo tabi kenferi . Mase Je kristiani lasan je onigbagbo ti o wulo, yonda aye re fun Olorun lati lo. (2 Tim 2:21). Je kristiani ti o kun fun eso t'emi (Gal.5, 22-23).

**II. IDAJO IGI AJARA TI KO WULO - ESE 6-8**

**(a) Iyasoto fun ijona**

Niwon igbati igi naa ti kuna lati so eso, ko wulo fun agbe, ohun kan ti o ku fun agbe ni lati gbe iru igi bee ju sinu ina. Niwon igbati Israeli ti kuna lati wulo fun Olorun, Oun Pelu ti pinnu lati gbee junu si owo ota ti yoo fi ina kun ilu re. Beeni, elese ti o ko lati ronupiwada kuro ninu awon ese re, ki o si yipada si Olorun yoo pari ere-ije re sinu ina orun apadi (Ifihan-21.8).

**(b) Ilu naa yoo di ahoro**

Igi ajara ti ko so eso ko ye ki o tun ma gbile lati tun ma fi ora inu ile sofo tabi ki o tun ma gba ninu ora ti o ye ki awon irugbin dara dara ma je lati le dagba, o ye fun iparun. Olorun ti pinnu lati so ile Israeli di ahoro ti enikeni, ki yoo gbe ninu re mo nitori ese aije olododo re. Iwo onigbagbo ko gbona ko tutu, yipada loni ki o si ni ibasepo rere pelu Oluwa.

**AWON IBEERE**

1. Se alaye bi a se fi orile-ede Israeli we igi Ajara.
2. Bawo ni o se di alaiwulo?
3. Iru awon eso wo ni Olorun nreti lodo wa loni?
4. So idajo Olorun lori igi alaileso naa
5. Awon eko wo ni o tun ri ko loni?

**JULY 12, 2026** **EKO 28**

# EKUN RERE OORE-OFE OLORUN

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 16:1-19*

***ESE AKOSORI:-*** *"Nitori Ore-ofe Olorun ti nmu igbala fun gbogbo enia wa ti farahan, Titu2:11*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 6/7/2026 | A gba wa la nipa Oore-Ofe | Efesu 2:1-13 |
| TUE | 7/7/2026 | Ife Kristi si Ijo Re | Efesu 5:25-27 |
| WED | 8/7/2026 | Ife Alailegbe | 1 Johanu 3:1-9 |
| THU | 9/7/2026 | Idalare nipa Igbagbo | Romu 5:1-9 |
| FRI. | 10/7/2026 | Oore Ofe Olorun | Ise Apo-14:1-3 |
| SAT- | 11/7/2026 | Idi pataki oore - ofe Olorun | Titu 2:1-15 |
| SUN | 12/7/2026 | Olorun ntoju wa | Esek-16 :1-14 |

### ORO AKOSO

Nibi kika loni, a fi orile-ede Israel we omo ti a sese bi ti a gbe sonu si ita gbangba nipa awon obi re lai ko bikita bi o ba ku. Omo naa ko ri itoju obi ti irufe omo bee ye ki o ri, fun idi eyi o le ku ti ko ba ri itoju ni kiakia. Oluwa nkoja O ri omo naa O gbe O si toju re titi o fi di odomobinrin. Nigbati omo naa dagba Oun fe Oluwa O si di aya Re, Oluwa pelu feran aya Re to bee ti Oun fi see loso gidigidi.

Sugbon ohun iya lenu ni pe aya Oluwa ti a fe, ti a se loso yi jeun yo tan o si di agberaga ati alailope obinrin o bere si se agbere pelu awon okunrin miiran, nikeyin o fi oko re sile lati lo ba awon okunrin miran. Owe yii nso nipa orile-ede Israeli ti Olorun fi anu yan lati je eniyan Re.(Deut 7:7-8) Olorun gba kuro ninu oko eru Egypti, Oun si mu wa si ile kenani ti o nsan fun wara ati oyin. Olorun da lola pelu golu ati silifa (wura ati fadaka) nikeyin, Israeli lo awon oso wonylii lati fi bo awon orisa nitori iwa agbere ati igberaga re, Oluwa tii se oko re pinnu lati bawi. Eko nla ni eleyii je fun wa, o pe fun olukuluku ki o ye ara re wo bawo ni a se nlo ebun tabi talenti ti Olorun fun wa, Nje fun ogo Olorun ni tabi ti aye? A gbodo ranti ibere aye wa iru eniyan ti a je tele ki Olorun ki o to gba wa. Niwon igbati a ba ti fi aye wa fun Jesu ati di iyawo Re, a si gbodo ma gbe igbe aye wa fun un nikan-Efesu 2:1-8.

### EKO

**I. OORE OFE TI A KO YE FUN - ESE 1-2**

**(a) Omo ti a bi ti a gbe sonu. ese 1**

Oluwa pa lase fun woli Esekieli lati je ki ilu Jerusalemu mo ese re nipa riran leti Ibere re. Abrahamu baba nla re wa lati iran aborisa. Iran Amorite ati Hitte ni baba nla ati iya nla re, ki Olorun to fi anu pe jade kuro ninu iborisa. Olorun lo aworan yii lati fi Israeli we omo titun ti a bi ti a si gbe sonu si ita gbangba lati ku ti Oluwa rii ti o si toju re. Olorun yan Israeli ni eniyan re ki ise nipa didara re larin awon yoku sugbon nipa anu Re. Opolopo lo ti idile aborisa ati iran buburu jade, sugbon ti a gba wa la loni nipa oore-ofe Kristi fun idi eyi e jeki igbe aye wa fi ogo fun un.

**(b) Olorun gbaa la - ese 2.**

Olorun gba orile-ede Israeli kuro lowo iparun nigbati o fi wa ni oko eru ni Egpti dipo ti ki ba fi parun pata pata lati owo ota re Olorun si mu ki o ma bi si nikeyin ni Olorun gbaa. (Eks 1:7).

**II. IFE ALAILEGBE TI A KO YE FUN - ESE 3-14**

**(a) Aya ti o rewa ese 8**

Omo naa (Israeli) dagba o si di odomobinrin ti o ti ye fun ile oko.Oluwa se ise iwenumo lori Jerusalemu, O we O si fi ororo kun ki o le je iyawo ti o rewa ti o si dun un wo nikeyin o di aya Olugbala re. Idi ti Olorun fi yan Israeli ti o si see loso ni lati le fi didara ogo Olorun han ki o le je orile ede ti a o ti ipase re bukun gbogbo aye. Bawo ni Olorun se se ijo re loso loni ? Ef. 5 25-27, kol. 3.12-14 Ronu lori oore-ofe Olorun lori iwo ati idile re, Nje Iwo ngbe igbe aye re fun un ?

**III. AYA ALAIMO OOREE SE 15-19**

**(a) Igbekele ewa ati okiki - ese 15**

Igbekele ewa re nibiyi tumosi gbigbekele ogo ara re. Eleyi nso nipa igberaga ati iwa mo ti to tan Jerusalemu, sugbon o ti gbagbe orisun ibukun re (Deut 3215) Mase gba igberaga laye ninu aye re, Olorun ni orisun ibukun ti o ni Deut 8 :18;O.D.75: 6; Jak. 1:17)

**(b) Asilo ewa Olorun - ese 15.**

Olorun wo Jerusalemu (Israeli) ni aso ewa, sugbon o fi ara re fun agbere nipa lilo ewa ti Olorun fun un lati se agbere awon orisa. Bawo ni iwo pelu se nlo ewa Olorun ti o fun o? Eniyan melo ni o ti fi ewa re gbe subu nipa awon aso ti o nwo? Ronu lori ijiya ti o le de ba o nipase iwa re wonyii.

**(d) Asilo ebun Olorun ese 16-19.**

Olorun fun ni ebun golu, wura, fadaka ati aso olowo iyebiye sugbon kinni o fi gbogbo awon ebun wonyii se? O fi gbogbo nkan wonyii se ere lati ma sin gege bi Olorun re. Awa pelu jebi iru iwa yil nigbati a ba nlo awon ibukun ti Olorun fun wa bii talenti fun awon ohun ti ko to. Olorun fun wa ni awon nkan wonyii lati fi ogo Re han kii se fun imo-tara eni. Nje awon ebun Olorun kan wa ti a fi fun o sugbon ti iwo nlo lodi si ogo Re? Re ara sile nisinyii, ki o si gba Olorun laye lati ma a dari aye re.

**AWON IBEERE**

1. So ajosepo Israeli pelu Olorun ninu ibi kika toni.
2. So bi Oluwa se fo Jerusalemu mo.
3. So die ninu awon ebun ti kristi fun ijo Re?
4. Bawo ni o se ye ki a ma lo ebun ti Olorun fun wa?

**JULY 19, 2026** **EKO 29**

# AYA ALAISOOTO

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 16: 20-34*

***ESE AKOSORI:-*** *"Enyin omo mi e pa ara nyin mo kuro ninu orisa" - 1 John 5:31.*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| **Ojo** | **Deeti** | **Akori** | **Bibeli Kika** |
|---|---|---|---|
| MON | 13/7/2026 | Iwa omugo bibo orisa | Isa.-44:9-17 |
| TUE. | 14/7/2026 | Sa fun Ifekufe | 2 Tim. 2:22-26 |
| WED. | 15/7/2026 | Atubotan iwa Ifekufe | Matt. 5:27-30 |
| THU. | 16/7/2026 | Mase ifekufe ohun buburu | I Kor. 10:6-12 |
| FRI | 17/7/2026 | Mase fi aidogba pelu Alaigbagbo | 2 Kor. 6.14-18 |
| SAT | 18/7/2026 | Agbere T'emi | Esk. 16:20-25 |
| SUN | 19/7/2026 | Irepo Alaimo | Esk. 16:26-34 |

**ORO AKOSO**

Iwa agbere Israeli ni a le tumosi aisooto temi. Israeli beresi sin awon orisa dipo Olorun alaaye, awon orisa bii baali ti o je orisa awon ara kenani ti won gbagbo pe o nmu ojo ro ti nkan oko si ndara. bakannaa ni orisa Ashera, orisa kennani, Moleki orisa awon omo Ammoni eyiti won ma boo pelu sisun omo ninu ina eyiti Olorun lodi si. (Deut 18:19-Deut 18.9-12; Lef- 18:21) Orile ede Israeli gbiyanju lati sin Olorun otito pelu awon olorun eke. Iwo ko le sin Olorun ati esu. (Matt. 6:24).

Orile-ede Israeli tun darapo pelu awon orile-ede alagbara ti o yii ka; awon bi Egypti ati Assyria fun abo dipo ati gbekele Olorun fun abo re. Opo igba ni awa pelu ti ko Olorun alaaye sile lati gbekele agbara aye

ti ko le gba wa. Awon miran gbekele owo, ipo tabi ohun ini won fun abo. Gbekele Olorun, Oun yoo mu o duro (O.D..20:7& 8 :56;9:10; 34:5). Ninu eko ti o koja a ko bi Olorun se ka awon ese orile-ede Israeli fun un, a o tun tesiwaju lati tun wo die ninu awon ese orile-ede naa ti Olorun fi esun re kan an.

**EKO**

**I. AWON ISE BUBURU ISRAELI - ESE 20**

**(a) Esun ipaniyan ese 20-21**

Orile-ede Israeli beresi jinle ninu ese, nse ni o nburu sii. Iwa iborisa re buru tobe ti o mu awon omo re okunrin ati omo re obinrin lati fi se irubo ninu ina, si orisa Moleki tii se orisa awon ara kenani eyiti Olorun ko. (Lef- 18:21) Ona ti won ma gba bo orisa yi je eyiti won yoo fi irin ro ere, won yoo mu ere naa duro ninu ina ti a ti da, won yoo wa gbe omo ti won o fi se irubo laaye sowo ere ninu ina naa awon olujosin orisa yii yoo ma lu ilu won yoo si maa jo nigbati omo naa yoo ma kerora titi yoo fi ku. Eleyi je asa buruku. Nigbati eniyan ba ti sa kuro niwaju Oluwa, iru eni bee yoo ma jinle si ninu ese. Israeli ko Olorun sile lati bo orisa. ka (Isaiah 44:9-18) orisa ko je nkankan, ki kuro lodo Olorun nyori si iparun.

**(b) Gbigbagbe ibere - ese 22.**

Israeli ti gbagbe ipo ijiya ti o wa ni ile Egypti ki Olorun ki o to s'awari re ti o gba ninu iya oko eru ti o si mu wa si ile ileri re. O wo ni aso iyi, ola ati agbara sugbon nigbati oun di eni nla o sote si Olorun. Gbigbagbe oore ofe ati jije olooto Olorun ninu aye re le mu ki o sako kuro lodo Oluwa nitorinaa, ma ranti oore ofe Olorun ki o si ma dupe lowo Re nigba gbogbo (O.D103:1-5).

**(d) Si sin awon olorun eke. ese 23-24**

Orile-ede Israeli fi oniruru aworan ere orisa kun ile re, o si ko opo ibi ijosin fun awon olorun eke wonyii, si opo opopona re. Esin iborisa yii, le je pe o bere pelu oba Solomoni nigbati o fe awon omobinrin olori ilu awon aborisa wonyii eyiti won mu iborisa wo ile naa. (1Awon oba. 11:1-7) bakannaa ka 2 Awon Oba 17:7-18. Awon ohunkohun ti o ba ti fe ju Olorun lo ti di orisa ti o nbo.

**II. IBASEPO TI KO TO. ESE 26**

(a) Nini Ibasepo pelu awon orile-ede, iborisa tun je okan ninu ese ti Israeli jebi re niwaju Oluwa. O darapo mo awon orile-ede kenferi bi Egypti ti o ti ko won leru ri, bakannaa ni o tun sin awon orisa Assiria, o npongbe fun awon olorun eke. Didarapo mo aye fun abo tabi oro (wealth) le mu ki Kristiani jinle ninu ese, sora fun didarapo mo awon alaigbagbo nitori oro, gbekele Olorun fun abo ati ipese.

**(b) Iwa agbere ti ko wopo.**

Lodi si iwa awon alagbere obinrin, won a ma ko bere owo lowo okunrin ti won jo fe da ese agbere, sugbon ni ti agbere Israeli oun ni o tun fun alagbere okunrin re ni ebun. Orile-ede Israeli ko awon ebun rere ti Olorun fi se loso fun awon orile-ede aborisa yii nitori ai je olooto re. Nje awa pelu ko jebi iru iwa ese yii loni, bawo ni a se nlo awon ebun Olorun bii talenti, owo, akoko, okun (Strength) ati awon ebun miran ti Olorun fun wa? E je ki a lo won fun awon ohun ti yoo mu ogo ba Olorun ati imu gboro Ijoba Re dipo lilo fun awon ohun ti o le mu wa jinna si i.

**AWON IBEERE**

1. Daruko awon orisa ile kenani ti awon omo Israeli sin.
2. Awon ese wo ni awon omo Israeli tun da?
3. Bawo ni o se ye ki a ma lo ebun ti Olorun fun wa?
4. Ona wo ni awa pelu ngba sin olorun miiran loni?
5. Kinni awon ohun ti o tun ri ko ninu eko toni?

**JULY 26, 2026** **EKO 30**

# IDAJO ATI IMUPADA SIPO AYA ALAISOOTO

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 16:35-63*

***ESE AKOSORI:-*** *"Emi o si mu awon onidajo re pada bi igba isaju, ati awon igbimo re bi igba akobere lehin na a o pe o ni ilu ododo, ilu otito - Isaiah 1:26.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 20/7/2026 | Ojo Oluwa | 2 Pet 3:10-13 |
| TUE | 21/7/2026 | Ojo nla ojo Idajo | Juda 5-7 |
| WED | 22/7/2026 | Olorun kii soju saju | Rom. 2:1-16 |
| THU | 23/7/2026 | Olorun nse idajo ni Ododo- | O.D. 98:1-9 |
| FRI | 24/7/2026 | Jesu: Olumu ofin Se. | Rom 104-13 |
| SAT | 25/7/2026 | Olorun Onidajo Ododo | Esk. 16:36-59. |
| SUN | 26/7/2026 | Olorun ti o npa majemu mo. | Esk-16:60-63 |

**ORO AKOSO**

Ninu eko ti o koja, a ko nipa iwa aisooto orile-ede Israeli si Olorun gegebi iyawo si oko re. Loni eko wa yoo da lori Idajo lori aya alaisooto naa. Sibe Olorun tun se ileri igba pada re eyiti o da lori majemu ayeraye ti Oun yoo da pelu re. Kii se lori jije olooto Israel, bikose lori oore ofe ati anu Re. Ileri majemu yii ni a muse ninu kristi Jesu eniti a fi se etutu fun ese. Ifi ara Re rubo lo fun wa ni idarijin ese ati Israeli (Juu) ati awa iran kenferi. Gbogbo onigbagbo ninu kristi ni o ni ipin ninu majemu laelae yii. A gba wa , kii se nipa ise ,bi ko se nipa oore ofe Re (Efesu 2:8-9).

**EKO**

**I. TITOBI IDAJO OLORUN NAA.**
**ESE 35-36**

**(a) Aya alaisooto yoo gba ibawi**

Nitori iwa aisooto re, Israeli yoo gba ibawi fun ese re. "Nitoriti a da egbin re jade, ti a si ri ihoho re nipa pansaga re pelu awon olufe re ati pelu gbogbo orisa irira re, ati nipa eje awon omo re, ti iwo fi fun won" ese 36. Israeli huwa agbere ati iborisa tobee ti o fi awon omo re se irubo fun olorun eke. Eleyii ni o nran wa leti oju kikoro ti Olorun fi wo ese ti O si fi anu pe fun ironupiwada ati jije oloto wa si I.

**(b) Ijiya re lati owo awon alagbere**
**re - ese 37-44**

Olorun so di mimo fun Israeli pe awon orile-ede aborisa ti o ba ni ibasepo ti o si sin awon orisa won ni Oun yoo lo lati je Israeli niya. Won yo bo si ihoho, won yoo si dana sun ile re. Beeni o si ri nitori orile-ede Egypti, ati Assiria pelu Babiloni ti Israeli ba dowo po fun abo ati agbara pada fi ina sun ilu Jerusalemu. Eleyii pelu je eko fun wa loni, pe a gbodo sora, awon ohun ti a fi igbekele wa sinu re dipo ninu Olorun le di ohun ti esu le lo lati pa wa run. Nitori idi eyi e jeki a fi igbekele wa sinu Olorun nikan, ki a mase gbekele ohun aye ti o le pani run.

**II. A FI ESE JUDA WE SODOMU ATI**
**SAMARIA- ESE 45-59**

**(a) A fi Jerusalemu we sodomu ati**
**Samaria ese. 4.6**

Jerusalemu ilu mimo ti a yanfe ti Tempili Olorun wa o nsapere wiwa laye Olorun laarin awon eniyan Re. Nisinyi wa di ilu ti a fi we awon orile-ede kekeke ti a ko mo nitori iwa aisooto re. Samaria nihinyi ti a pe

ni arabinrin re je olu ilu ariwa ijoba Israeli. Ilu yii kun fun Iborisa eyiti a pada dana sun ni 722 B.C lati owo awon omo ogun Assiria . Sodomu arabinrin re le je ilu Sodomu ni akoko Abrahamu (Gen.19) A mo ilu yii pelu awon ese buburu won si Olorun eyiti o mu ki a pa ilu naa run pelu ina a t'oke wa o se pataki gegebi onigbagbo lati gbe igbe-aye ti o nfi wa hàn gegebi omo Olorun.

Ese Jerusalemu buru ju ti Sodomu ati Samaria lo.

Olorun so wipe bi o tile je pe ese ilu Sodomu ati Samaria je ilu ti won kun fun iwa ote ati buburu si Olorun, sibe ilu Jerusalemu wa ninu ese ju awon ilu yii lo. ilu Jerusalemu ni opo oro (weath), eto ilana ijosin tooto si Olorun, bakannan Tempili Olorun wa nibe, o ni opo awon woli ti Olorun ran si pelu ikilo ati igbaniyanju, iru anfani ti Sodomu koni. Onigbagbo! Nje awa pelu ko jebi awon iwa wonyii, awon ese ti alaigbagbo ti o wa lode nda ni awa naa nda, ilu Sodomu ko ni Bibeli, ile ijosin tabi oniwaasu sugbon awa ni anfani awon nkan wonyii loni, Awon ojise Olorun npe ikilo sibe a ko yipada, abalajo ti aye ko fi ka ijo Olorun si mo loni nitori awon ese agbere, fifi eru ko owo je, owo (business) aisooto ninu re iwa ififipa banilo (rape) ati irufe awon iwa buburu bee ni o wa lowo ti awa naa. Jesu pe o ni imole aye je ki aye ri Jesu ninu re.

**III. IRETI ATI IMUPADA SIPO - ESE 60-63**

Pelu iwa ai je olooto Israeli, Olorun tun yan lati ranti majemu ti Oun da pelu re ni oke Sinai nigbati Oun so won di eniyan Re Olorun Je olooto si ileri Re. Nisinyi nitori Ikuna won Olorun seleri majemu miiran ti yoo je laelae eyiti ki yoo je fun awon omo Israel nikan, sugbon fun gbogbo eya ati ede ni agbaye, eleyi ni wa si imuse nipase Jesu kristi. Bibeli so di mimo pe Jesu Kristi ni alarina majemu titun ti a nso yii eyitii a fi lele pelu ileri ti o dara ju. (Heb 8:6) Iku Jesu lori igi agbelebu ni o pari ise idarijin eyiti majemu laelae ko le se, fun idi eyi a di eniyan Olorun nipa igbagbo ninu Jesu kii se nipa agbara wa.

**AWON IBEERE**

1. Se alaye bi idajo Olorun yoo se lagbara to lori ilu Jerusalemu.
2. Bawo ni a se fi ilu Jerusalemu we Sodomu ati Samaria?
3. Kinni yoo mu ki ijiya Jerusalemu ko po Ju Sodomu lo?
4. Se alaye nipa majemu titun ti a ko ninu eko yii

**AUGUST 2, 2026** **EKO 31**

# OLUWA RE AGBERAGA SILE

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 17:1-21*

***ESE AKOSORI:-*** *"Enikeni ti o ba gbe ara re ga, li a o re sile;enikeni ti o ba si re ara re sile li a o gbe ga''. Matteu 23:12.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 27/7/2026 | Olorun Yago Fun Agberaga | Orin Daf. 138:1-6 |
| Ojo Isegun | 28/7/2026 | Agbara Majemu | Deut. 7:7-9 |
| Ojoru | 29/7/2026 | Yago fun Awon nkan Wonyi | Matt. 5:33-37 |
| Ojobo | 30/7/2026 | Olorun Ko Oju Ija si Agberaga | 1 Peteru 5:5-8 |
| Ojo Eti | 31/7/2026 | Ni Okan Kristi | Filipi 2:3-8 |
| Ojo Abameta | 1/8/2026 | Owe Idi ati Ajara 1 | Esekieli 17:1-10 |
| Ojo Aiku | 2/8/2026 | Owe Idi ati Ajara 2 | Esekieli 17:11-21 |

## ORO AKOSO

Okan ninu awon ohun irira ti Olorun korira ni igberaga. Igberaga je ese nla niwaju Oluwa. Igberaga le e yorisi awon ese miran bii; fifi oju tembelu awon elomiran, siso oro eyin, oro egan, gbigbe ara eni ga ati fifi oju tembelu Olorun ati agbara Re. Igberaga le yorisi ipaniyan abbl. Olorun korira agberaga eniyan ati orile ede. Eko ti oni fi igberaga Israeli han wa ati ohun ti o sele si i.Woli Esekieli so nipa re li ona ewe. Eyi ni a mo si owe tabi alo,sugbon won ni itumo. O so nipa eye idi meji ati ajara ti o gbile. (Esek. 17: 1-24). Abala ikini ninu ori yi se afihan ibere owe naa. (ese 1-10); alaye tele (ese 11-21) ati leyin re ni a se afikun ileri adun ojo iwaju ti o tayo gege bi o ti farahan ninu owe naa. O dabi pe Olorun fe ki a ka abala Bibeli yii ninu imole awon isele pataki ti orile ede naa ti o ti koja, ti o nsele lowo ati itan ojo iwaju.

## EKO

### I. OWE NAA - 17: 1-10

Owe naa bere pelu sise apejuwe eye idi nla. Eye idi yi ba le ori igi Kedari ni Lebanoni. Ibi yi je ile Kenani tabi Juda. (Jos. 1:14; 2 Awon Oba 14:9). Eye idi naa ge ori omunu eka igi Kedari kuro, o si mu u lo si ile owo kan, nibi ti o ti gbin in sinu ilu awon onisowo.Eye idi naa mu irugbin ni ile naa, o si lo gbin si ile olora ti o si ni opolopo omi, beeni o si wu jade, o wa di ofin, ati igi ajara nla ti o gbile. Ni ona miran ewe, awon eka re, dojuko o, sugbon gbongbo wa ni abe re(ese. 3-6). Leyin ifarahan eye idi akoko, eye idi miran farahan. Eyi ko ni ogo bi ti akoko. Ohun kan ti akiyesi ni wipe, a ko gbin i si ibi ti o pe, nibi ti o ti le ni ohun gbogbo ti o nilo fun fun igbasoke ti o l'ogo. Ajara naa se ohun kan; '' o yi ite gbongbo re sodo re, ki o le ma b'omi si I ninu aporo ogba re''. Igbese yi ni ipa. Looto, ipinu re lati fi eye idi keji se orisun igbadun re ni ayorisi ti o le, nitori a o fa ajara naa tu beeni a o si ka awon eso re kuro. Ki o le ro. (ese 9a). Eyi tumosi wipe, ajara naa ki yio hu jade mo, beeni ki yio si ye, labe bi o ti wu ki a se itoju re to, opin re yio de laipe. Nje o le ni afojusun opin buburu re?

### II. ITUMO OWE NAA - 17:11-21

Leyin ti Woli Esekieli so owe naa tan, Olorun pase fun wipe ki o so itumo re fun awon eniyan naa (ese 11) nitori o ni i se pelu oro idite. Sedekiah, Oba Judah ngbiyanju lati dite lodi si Oba Babiloni (2 Awon Oba 24:20, Jer.37-38) o si dabi eni wipe irokeke idite yi n ru ireti eke soke fun awon ti o wa ni igbekun wipe won ko ni pe pada sile. Nitori naa, Woli Esekieli se alaye owe naa fun awon eniyan wipe, eye idi akoko duro fun Nedukadnessari ti Babiloni ti o ko '' awon olokiki'' lo si igbekun. Awon olokiki nibi yii duro fun Oba Jehoiakini ti Judah ati awon borokini re ti a ko lo si Babiloni. Eyi waye ni 597BC (ese 12; woo 2 Awon Oba 24:8-17). Nigba ti Nebukadnessari ko won ni igbekuun, o fi Mattaniah (eniti o je ibatan Jehoiakini okunrin) si ori ite Judah, o si yi oruko re pada si Sedekiah (2 Awon Oba 24:17-20). Ninu owe naa, Sedekiah ni irugbin ti agbin si ile olora ti o dagba di ajara eleso.

Adehun wa laarin Nebukadnessari ati Sedekiah nigba ti a fi si ori ite labe ibura. Eredi Nebukadnessari fun ibura tabi adehun yi ni lati fi Sedekiah ati Judah si abe Babiloni. (17:13-14). Sugbon, ni akoko naa, okan Sedekiah fa si eye idi keji- eyi ti nse Egipti . O ye adehun naa lai to Oluwa lo, o si ran owo eniyan ati awon omo ogun si Egipti. (ese15). Idite yi buru jai, fun awon idi kan, awon omo ogun Egipti ko tete de lati ran Sedekiah lowo nigba ti o nilo re. Nitori idi eyi, Sedekiah pada ba ara re ni Babiloni. (ese 16,20-21; Jer. 52:3-11). Ohun ti o ya wa lenu nipa ise iranse naa ni bi Olorun se da Sedekiah lebi fun yiye adehun re pelu Oba Babiloni. (17: 18; ese 15-16). Olorun nreti ki enikookan, awon idile, awon ilu , ati awon orile ede, lati pa ileri won mo. (Num. 30:2; Deut. 23:21-23; Oniwaasu 5:4-7). Ninu Orin Dafidi 15: 4 eniti "o pa adehun tabi ibura re mo, nigba ti o npa lara" ni Onisaaamu bu iyin fun.

Ninu Esekieli 17:18 Olorun so nipa Sedekiah gege bi eniti o gan adehun Olorun, ti o si ye majemu Re. Idi ni wipe, adehun ati majemu ti a da laarin Sedekiah ati Nebukadnessari ni a da ni oruko Olorun. (2 Kro. 36:18). Nitori idi eyi, a mu gege bi ileri ti a se fun Olorun. Eyin ara, e sora nigba ti a ba nse ileri, da majemu tabi se adehun ni onakona, boya nipa oselu, ofin, esin abbl . A gbodo ri daju wipe a setan lati se e, ki a to se ibura tabi da majemu. O san ki a ma se ileri, tabi da majemu tabi bura ju wipe ki a se e, ki a ma mu se.

**AWON IBEERE**

1. Se alaye owe tabi alo naa.
2. So itumo owe naa.
3. Oba Judah wo ni o ye majemu, ki sini ayorisi re?
4. Kinni idi ti a fi ri Majemu laarin Sedekiah ati Nebukadnessari gege bi majemu pelu Olorun?
5. (a) Akeko kookan gbodo so eko ti o ko.
   (b) Imoran wo ni o le e fun awon adari ati enikookan?
   (d) Se alaye idahun re.

**AUGUST 9, 2026** **EKO 32**

# OLUWA GBE ONIRELE GA

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 17:22-24*

***ESE AKOSORI:-*** *"Gbogbo igi inu igbe ni yio si mo pe, emi Oluwa li o mu igi giga wale, ti mo ti gbe igi irele soke, ti mo ti mu igi tutu gbe, ti mo si ti mu igi gbigbe ruwe: emi Oluwa li o ti so ti mo si ti see". ( Esekieli 17:24).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 3/8/2026 | Jije Onirere Eniyan | Numeri 12:1-5 |
| Ojo Isegun | 4/8/2026 | Jije Onirele fun Ete Kan | Deut. 8:1-5 |
| Ojoru | 5/8/2026 | A re Onigberaga Sile | Jobu 40:6-12 |
| Ojobo | 6/8/2026 | Igbe Onirele | Orin Dafidi 9:9-12 |
| Ojo Eti | 7/8/2026 | Ife Okan Onirele | Orin Daf.10:16-18 |
| Ojo Abameta | 8/8/2026 | O gbe Onirele Ga | Orin Daf. 147:1-6 |
| Ojo Aiku | 9/8/2026 | A Gbe Igi ti o rele Ga | Esekieli 17:22-24 |

**ORO AKOSO**

Ojo iwaju onirele dara nitori Oluwa gbe eni ile ati oniwatutu ga. Olorun ni inu didun ninu oro awon onirele ti o fi ireti won sinu Olorun, ti won si fi igbekele won sinu Oluwa. Lai fi ohun ti ota ti se se tabi iwuge agberaga, eto Olorun fun awon Omo Re yio wa si imuse. Nitori naa, ohunkohun ti o ba nla koja loni gbekele Oluwa, re ara re sile li ese re. O ni ojo iwaju ti o dara fun o. Eko wa ti oni da lori ojo iwaju ologo fun awon omo Israeli, bi o tile je wipe ati re won sile, sibe, Olorun ni eto rere fun won. Idi meji naa (eyi ni awon alagbara aye) ti won gbiyanju lati lo ase ijoba won lori awon eniyan Olorun sugbon Olorun so wipe " beeko".

**EKO**

**I. IDASI LATI ORUN WA. - 17: 22-23**

1. Olorun fun ra re yio sise.
2. Yio mu ninu eka ti o ga julo, ninu igi Kedari giga; yio si lo o.
3. Yio gbin sori oke giga kan ti o si han.

   Ti Olorun ba se eyi fun ra re nje iwo lero wipe ota kan ni agbara lati se lodi si I? Rara.

4. Awon ‘‘oke giga ti Isareli’’ yi lee je oke Sioni, ti awon woli ri gege bi aarin gbungbun ijoba Messaiah. Kaa; Esekiel 20:40, Orin Dafidi 2:6 Mika 4:1.

**II. OGO IGI KEDARI TI OLORUN GBIN - 17:23b-24**

1. Igi Kedari ti Olorun gbin yio yo eka. Mo wipe ohunkohun ti Olorun ba se ni o dara, yio si ni ayorisi rere. Eto Re fun aye re, yio mu awon esi rere jade.
2. Igi naa yio je aabo tabi iboji fun awon oniruru eye. (ese 23b). Eyi tumosi, bi o tile je wipe ati gbagbe re tele, ati pe a ti, kegan re, ati fi o se eleya abbl., nigba ti ogo Olorun ba han lara re (Isa. 60:1-8) awon eniyan yen, yio maa wa iranlowo re.
3 Yio han gbangba wipe ise Olorun ni, nitori yi o se afihan ayipada ninu eyi ti igi giga yio dagbasoke (Esek. 17:14) ti igi tutu yio si gbe nigba ti igi gbigbe yio gbile. (ese 24).
4. Igi giga ati igi tutu nibi yii le duro fun awon alagbara ijoba(oselu) ti o ti gbiyanju lati je gaba lori awon eniyan Olorun. O tun le duro fun awon ti o ngbogunti itesiwaju ati ogo awon eniyan Olorun. Awon alagbara ati alase ti o ngbogun ti ojo iwaju awon eniyan Olorun. (Efesu 6:12). Sugbon, nigba ti Olorun ba dide fun awon eniyan Re, awon agbara wonyi yio teriba.
5. Nigba ti Olorun ba mu agbara yi wa - igi giga ati igi tutu ni a ke lule, yio wa gbe awon eniyan Re ga, gbogbo igi ni ile ni yio mo wipe Oun ni Oluwa. Ranti eri Hannah ninu Bibeli ninu 1 Sam. 2:1-10 ati eri Mose ati Miriamu nipa ise iyanu Olorun ninu aye won. Eksodu 15:1-21.
6. Eyi ni ohun ti Olorun ti yan, ti o si ti se ileri. Abala Bibeli nla yi, ti o so nipa ireti ati imupadabosibo pari pelu atenumo, “Emi Oluwa ni o ti so, maa si se “. Nitorinaa, iwo naa gbodo

gba ohun ti Olorun ba so gbo ati ohun ti o se ileri lati se fun o, idile re ati orile ede re. Gbeke le E, se ife Re, ki o  si ma tele pelu irele.

**AWON IBEERE**

1. Se apejuwe ohun ti Olorun fe se fun Israeli.
2. Kini yio sele si igi  giga ati igi tutu?
3. Daruko awon eniyan meta ti o so eri iriri won nipa idasi Olorun ninu eko ti oni.
4. Idaniloju wo ni Olorun fun awon eniyan Re?
5. Kinni yio sele si Isreali ni akoko ti Olorun ba se asepe ileri re fun Israeli?

**AUGUST 16, 2026 EKO 33**

# AWON BABA TI  JE ESO AJARA KIKAN, EHIN AWON OMO SI KAN

***BIBELI KIKA:-*** *EZEKIEL  18:1-4*

***ESE AKOSORI:-*** *"Kinni enyin ro ti enyin fi npowe yi niti ile Israeli, pe, Awon baba ti je eso ajara kikan, ehin awon omo si kan''. (Esekieli 18:2).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 10/8/2026 | Enikookan Ni | Deut. 24:16-18 |
| Ojo Isegun | 11/8/2026 | Idajo Iku fun Awon Oloote | Number 14:26-28 |
| Ojoru | 12/8/2026 | A da Awon Omo Si | Number 14:29-34 |
| Ojobo | 13/8/2026 | Ese ni Ere | Romu 6:21-23 |
| Ojo Eti | 14/8/2026 | Jesu nikan ni O ru Ese Wa | Heberu 9:24-28 |
| Ojo Abameta | 15/8/2026 | Olukuluku ni O ma Ku fun Ese Re | Jere. 31:27-35 |
| Ojo Aiku | 16/8/2026 | Owe Atijo | Esekiel 18:14 |

**ORO AKOSO**

Ori bibeli yi je okan ninu itokasi bibeli ti o maaa nfa ariyanjiyan laarin awon ojogbon ninu bibeli nipa ibasepo  ojuse agbajopo ati enikookan ninu igbesi aye awon eni majemu Olorun. Sugbon, ori bibeli yi ko tumosi wipe, ojuse enikookan tako ojuse agbajopo orile ede naa niwaju Olorun. Sugbon, o se afihan wipe awon Israeli gege bi agbajopo ati enikookan ni ojuse si majemu Oluwa. Owe yii " , Awon baba ti je eso ajara kikan, ehin awon omo si kan''o ti wa laarin awon omo Israeli lati igba ti won ti wa ni igbekun. Olorun fun awon omo Israeli ni esi ti o yanilenu nipa owe naa.

**EKO**

**IDAHUN OLORUN SI OWE NAA**

**I. IPILESE OWE NAA  ( ESE 1)**

Oro ti o bere fihan gbangba wipe, ariyanjiyan ti wa laarin Olorun ati awon eniyan Re ninu igbekun. Kaa ese1, Jeremiah 31:29 naa so nipa oro yi, eyi ti o tumosi wipe o wa ni okan awon ti o wa ni igbekun ni igba naa. Ohun ti awon eniyan naa kun tabi soro nipa re ni wipe, awon nje iya ayorisi awon ese awon baba nla

won. A tun oro yi so ni Ekun Jeremiah 5:7 wipe “Awon baba wa ti se, nwon ko si si; awa si nru aisedede won’’. Aroye awon eniyan wonyi tumosi pe Olorun je alaisododo lati je oro ki o lo bee; wipe ojusaaju ni. Ijiya tabi isoro iriri ibi lo mu ki eniyan ro wipe Olorun se ojusaaju, ati alaisododo si awon eniyan kan, nigba ti o si je wipe ko ri bee.Gbogbo igbese ti Olorun gbe ni o ni idi.

**II. IDAHUN OLORUN**

Olorun soro nipa iranse Re ni ona ti o rorun wipe, “Oluwa Olorun wipe bi mo ti wa, enyin ki yio ri aye lati pa owe yi mo ni ile Israeli “ (Esek. 18:3). Eyi tumosi wipe Olorun ti fi opin si i. Nitori, yiO se atenumo ipilese otito meji ti o ti oro re gege bi Oba leyin . Ni akoko, O je ki won mo wipe Oun ni O ni ohun alaaye gbogbo. Oun ni o da wa, nitori idi eyi, gbogbo wa la je ti Re. Oro nipa ajogunba ko sele rara nitori “gbogbo okan ni t’emi” , nitorinaa gege bi enikookan, ti Re ni a je. Otito ikeji ti o fidimule ni wipe “okan ti o ba se, on o ku”. Eyi tumosi wipe, olukuluku wa ni yio wa niwaju Olorun fun awon ohun ti a se, ati iwuwasi wa. Eyi ti o tumosi pe, a ko le fara pamo sabe awawi, tabi ki a da awon baba nla wa lebi, tabi awon obi wa orisun bi a se to wa dagba, aini, ailoye, ayika tabi ohun miran lebi ibi ti o de ba wa. A gbodo mo wipe Olorun nse idajo ise eniyan, o si mo ohun ti o wa ninu wa ki a to gbe igbese, nitorinaa, ye ero okan re wo, ki o to mu ohunkohun wa si ise.

**AWON IBEERE**

1. Kinni ariwisi awon omo Israeli ninu igbekun.
2. So owe naa, ki o si se alaye itumo re
3. Kinni idahun tabi esi ti Olorun so si owe naa ?
4. Nje a ni irufe Owe bee ni Afrika? Ti o ba je wipe beeni, so o.

**AUGUST 23, 2026** **EKO 34**

# AYANMO WA, WA LOWO WA

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 18:5-18*

***ESE AKOSORI:-*** *“Sugbon bi enia kan ba se looto, ti o si se eyiti o ye” (Esekieli 18:5).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 17/8/2026 | Gbo Ikilo | Owe 1:8-12 |
| Ojo Isegun | 18/8/2026 | Fi Ogun Rere Sile | Owe 13:21-24 |
| Ojoru | 19/8/2026 | To Omode ni Ona ti yio to | Owe 22:1-6 |
| Ojobo | 20/8/2026 | Ba Omo Re wi | Owe 29:15-17 |
| Ojo Eti | 21/8/2026 | Awon Omo ni Ini Oluwa | Orin Daf.127:1-5 |
| Ojo Abameta | 22/8/2026 | Baba Olododo | Esekiel 18:5-9 |
| Ojo Aiku | 23/8/2026 | Omo Buburu | Esekiel 18:10-18 |

**ORO AKOSO**

Ninu eko wa ti oni, Olorun fihan fun Esekieli pe, ayanmo awon eniyan re wa lowo won bakanaa ni o wa fun wa loni. Owo won lo wa lati yan iye tabi iku. Eyin ara, a gbodo mo wipe awon ise wa ninu ise je ayorisi anfani ti a ni lati yan ohun to wu wa, eyi ni o si maa nso ohun ti o kan. Fun awon eniyan Israeli lati ni oye ohun ti Olorun nso, O se agbekale irufe eniyan meta: Baba, Omo ati Omo Omo.

**EKO**

**I. ORO NIPA BABA OLODODO NAA-18:5-9**

Olorun se agbekale igbesi aye okunrin kan ti o je Baba. Okunrin yi ni Omo kan. Baba yi je olododo eniyan. O fi ododo re han ninu ohun ti o nse.(Esek. 18:5). Tito leseese awon ise tabi igbese re dabi akojopo iwa rere. Iwa rere naa ni nse pelu:

a. Esin ati oniruru ise ibalopo (ese 6)
b. Ibasepo pelu Oro aje, eto isuna ati ofin (ese 7-8).

Gbogbo re ni se pelu ohun ti o ye ni sise ati ohun aigbodo se. Eyi ni awon ohun ti o ye ki olododo se ati ohun ti ko gbodo se. Ona igbesi aye re ni akopapo ni ese 9a, ‘‘ Ti o ti rin ninu ase mi, ti o si ti pa idajo mi mo’’. Agbeyewo Olorun nipa okunrin naa ni wipe ‘‘ okunrin naa je olotito, yio si ye.’’ (ese 9b).

A nreti gbogbo omo Olorun lati gbe igbesi aye ododo. Ododo ni o ngbe orile ede soke. Bi o tile je wipe, awujo wa lode oni nbaje si lojojumo, sugbon awon omo Olorun ko gbodo rin ona awon eni ti aye. A gbodo pa ofin Olorun mo ki a si gboran si I.

**II. ORO NIPA OMO BABA OLODODO NAA- 18:10-13**

Okunrin naa ni omo okunrin ti o ye ki o rin ni ona Baba re, sugbon ko dabi Baba re rara. A se apejuwe re gege bi “ipanle omo, ti o maa nta eje sile’’. (ese10-11b). A to leseese awon ohun ti omo yi nse ati eyi ti ko se ninu Esek 18:11b-13a. Ti to leseese yi dabi ti awon iwa rere ni ese 6-8 sugbon odi keji ohun ti Baba omo yi se ni oun se. Kini Baba yen yio maa ro nipa ti omo yi? Awon obi gbodo sa ipa won ni kiko awon omo won, ki won si ma gbadura fun awon omo won. Nje o ye ki a da Baba omo yi lebi fun iwuwasi omo re? Omo yi wuwa lodi si iwa Baba re. Bi o tile je wipe tito leseese naa su mo ara won, onidajo aye (Gen 18:25), ki I nlo osuwon kan fun enikan ki o si lo omiran fun elomiran. Orisun ilana idajo Olorun ni awon ase ati ofin ti o wa ni ese ikesan ori ikejidinlogun iwe Esekieli. Olorun so di mimo wipe Baba Olododo yio ye, nigbati Omo alaisododo yio ku. Omo naa ko le da enikeni lebi fun ikorita ti o wa, nitorinaa, ‘‘ eje re yio wa lori oun fun ra re’’.

**III. ORO NIPA OMO OMO BABA AGBA OLODODO NAA - 18:14-18**

Abala yi da lori omo omo ti idile ti a ngbeyewo. Omo omo yi, “ri gbogbo awon ese ti Baba re ti se, ko si se awon nkan wonyi “ (ese 14). Eyin omo, ki nse ohun gbogbo ti awon obi yin se ni o ye ki e se tabi tele. Rin ni ona rere ati tito. Omo yi ri awon iwa buburu ti Baba re wu, sugbon o pinu lati yago kuro ninu iwa buburu ati aito. Ko kan tele apeere buburu Baba re bi afoju. Omo omo yi lo agbara lati ya ti Olorun fun un ‘‘ lati ma se ohun ti ko to’’. A ko so fun wa boya o mo Baba agba re ti o gbe igbeaye ododo, sugbon o pinu lati ma tele ona buburu Baba re. Oro ti Olorun so nipa omo omo yi ni a ri ninu ese 17b “ o mu idajo mi se , o si rin ninu ase mi tabi o pa ofin mi mo,o si tele ase mi’’. Fi ese yi we ese 9. Abajade igbesi aye omo omo yi ni a la kale ni ona wonyi: ki yio ku fun ese Baba re. Nitori eso kikan Baba re ki yio kan lehin. Omo yi ‘‘ yio ye’’. itumo re ni wipe, Baba re yio ku fun ese oun fun ra re nitori o se ilonilowogba, o si ja arakunrin re lo le, beeni o si se eyi ti o buru fun awon eniyan re. (Esek. 18:18).

O le ka Esek. 18:19-32 fun awon ohun ti Olorun tun so.

**AWON IBEERE**

1. So ariyanjiyan laarin awon omo Israeli ati Olorun.
2. Se alaye owe ti Olorun lo lati se afihan fun Israeli nipa ojuse enikookan.
3. Kini idi ti Olorun fi pe Omo omo naa ni olododo?
4. Kini imoran re fun awon Obi ati Awon omo?
5. So awon eko ti o ko ninu eko ti oni.

**AUGUST 30, 2026** **EKO 35**

# PIPOHUN- RERE EKUN FUN AWON ADARI ISRAELI

***BIBELI KIKA:-*** *EZEKIELI 19:1-14*

***ESE AKOSORI:-*** *"Pelupelu iwo pohun-rere ekun fun awon omo-alade Isareli", (Esekieli 19: 1)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| | Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 24/8/2026 | Owe Kiniun | | Esekiel 19:1-9 |
| Ojo Isegun | 25/8/2026 | Owe Ajara | | Esekiel 19:10-14 |
| Ojoru | 26/8/2026 | Abajade Iwa Buburu Jehoahasi | | 2 A. Oba 23:31-35 |
| Ojobo | 27/8/2026 | Isofo Oba Sedekiah | | 2 Awon Oba 25:1-7 |
| Ojo Eti | 28/8/2026 | Ipohun-Rere Ekun Dafidi | | 2 Sam. 1:17-27 |
| Ojo Abameta | 29/8/2026 | Ipohun- Rere Ekun Lori Israeli | | Amosi 5:1-6 |
| Ojo Aiku | 30/8/2026 | Jesu Pohun-Rere Ekun Lori Tempili | | Luku 19:41-44 |

## ORO AKOSO

Oro ti a mo si ipohun rere gege bi*Oxford Dictionary of English* tumosi lati ni imolara tabi se afihan ibanuje nla tabi ijakule nipa enikan tabi ohun kan. O tumosi orin, ewi tabi sise afihan ibanuje nla fun enikan ti o ku tabi fun ohun kan ti opin de ba. Ninu eko wa ti oni, ipohun-rere ekun je (iro orin meta pelu iro orin meji) orin aro ti a saba maa nko fun isinku awon adari ti o subu loju ija gege bi a ti rii ninu 2 Sam. 1:17-27. Sugbon orin aro yi ni awon woli majemu lailai maa nlo ni ona ewe lati pohun -rere ekun tabi kede iku orile ede, awon omo alade, awon oba abbl. (kaa Isaiah 14:21; Amosi 5:1-3; Esek. 2:10). A kiyesi wipe, o seese ki woli Esekieli maa sokun fun awon oba buburu ti ile Juda paapa julo Sedekiah, sugbon o soro fun woli yi lati ri bi idile/ijoba Dafidi yio se wa si opin laisi okan ikaanu rara. Awon woli tabi awon eniyan Olorun melo ni o nkedun ibi ti o de ba Naijaria loni? Awon eniyan melo ni o nkerora ninu adura fun orile de naa? Esekieli pohun-rere ekun fun awon adari orile ede ati orile ede re pelu.

A pin ipohun-rere ekun naa si meji nipa lilo apejuwe awon kiniun ati abo kiniun (19:1-9) pelu ajara (19:10-14)

## EKO

### I. AWON ABO KINNIUN ATI AKO KINNIUN -19:1-19

Woli lo kinniun lati duro fun awon enikookan, orile ede tabi idile oba. Awon omo Israeli mo ohun ti kinniun duro fun. Itumo re ye won (kaa Gen. 49:8-10; Num. 23:24; Mika 5:8). Kiniun je okan ninu awon eranko ti o le, ti o si lagbara, ti awon eranko iyoku si ma nberu re. Bi bu re maa deruba awon eranko iyoku. Ninu ese bibeli yi, abo kiniun ti o je iya yi, o toju okan ninu awon omo re lati di ako kinniun ti o lagbara. Ni ibi ayoka wa, abo kiniun yi, duro fun orile ede Israeli kii nse iya kookan. (Esek. 19:1-3). Eyi ti o tumosi wipe, okan ninu awon omo Israeli di alagbara. O ko bi a tii ja (eyi ni bi a see nfa ije ya perepere) ati bi a se nje awon eniyan (iyen ni pipa je), awon orile ede miran gbo nipa re, won si so o mu beeni won si ju sinu ewon won. Eyi ti o tumosi wipe ko kiyesara. Agbara ati igberaga re subu, a si fi iwo gbe lo si ile Egipti (ese 4). Kinun yi ni a ri gege bi oba Jehoahasi ti Juda ti oba Farao Neko ko nigbekun ni odun 609BC, o si gbe lo si ile Egipti, o si ku sibe (kaa 2 Awon Oba 23:31-35).

Oniruru ipo adari ti o ba ba ara re, re ara re sile laarin awon adari iyoku. Mase je ki awon ohun ti o ni, agbara abbl ko si o ni agbari tabi ki okun fun igberaga. Iru ise bayi maa ni atubotan ti o buru.

Nigbati ireti abo kiniun ti pin lori ako kiniun ti a bori , o toju omo kiniun miran lati di ako kiniun ti o l'agbara ju asiwaju re lo. Ki nse wipe o kan fa awon ounje re ya, se ni o nje won, a si maa rin laarin awon kiniun iyoku. Nitori okun re, o fo ibi giga awon kiniun yoku tuutu. O si so ilu won di ahoro, de bi wipe, bi bu ramuramu re dayaja awon olugbe ilu naa (ese 6-7). Nitori idi eyi, awon orile ede ati agbegbe ti o yii ka de awon won sile fun un. Beeni a si mu oun naa gege bi asiwaju re, sugbon a ko fi iwo mu u, sugbon a ju sinu apoti kan, a si gbe lo si odo Oba Babiloni (ese 8-9). A re sile patapata lai saanu fun un. Eniti a nso

nipa re ni Jehoiakini ti a ko lo si Babiloni ni odun 597 BC tabi Sedekiah, oba Juda ti o gbeyin ti afoloju, ti a si ko lo si Babiloni leyin isubu Jerusalemu ni odun 587 BC (kaa 2 Awon Oba 25:1-7).

**II. AJARA KAN - 19:10-14**

Israeli ni oye ami ajara ka Esek. 15:1-6; 17:1-10; Orin Dafidi 80:8-16; Isa. 5:1-7; 27:2-6.Ninu Bibeli kika yi, iya ti o duro fun orile ede ti o dabi ajara ti a gbin si ipa odo.O ni eso, beeni o si kun fun awon eka, awon eka re si l'agbara, o si ye fun opa alade (ese 10-11) eyi ti o mu ite Oba wa. Gigun ajara naa ko kuru, sugbon a se apejuwe re wipe a mu wa sile. Eyi ti o tumosi wipe a ri igberaga ninu re, ti o si yorisi isubu re. A faa tu ninu irunu, a wo lule.(ese 12a). Afefe ila oorun wa, o si tun gbin si aginju, ninu ile gbigbe ati ongbe (ese 13). Ile aginju duro fun Babiloni ti o mu ki awon eka re ti o l'agabra gbe, ti a si fi ina sun. (ese 12d). Sugbon o seni laanu wipe, okan ninu eka ajara naa fa isubu re gege bi a ti rii ni ese ikerinla wipe "Ina si jade lati inu opa kan ninu eka re, ti o si jo eso re run'' (ese 14). Eka yi ni Sedekiah, Oba Juda ti o gbeyin ti isote re fa ikolosi igbekun ni Babiloni. Woli naa wa pohun -rere ekun wipe, ko si eka kan ti o l'agbara ti o ku lori re fun opa alade.

**AWON IBEERE**

1. Se alaye ohun ti abo kiniun se fun awon omo re.
2. Se alaye ohun ti awon omo kiniun ti a ko se, ati ohun ti o sele si won leyin re.
3. Tani o ye ki a da lebi fun ohun ti o sele si awon kiniun?
4. Kinni afefe ila ooru ati ile aginju duro fun?
5. Awon eko wo ni o ko?

**SEPTEMBER 6, 2026** **EKO 36**

# OLORUN SAFIHAN OKAN RE FUN AWON OLUSEWADI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 20:1-9*

***ESE AKOSORI:-*** *"Fun olokan-mimo ni iwo o fi ara re han ni olokan mimo; ati fun olokan wiwo ni iwo o fi ara re han li onroro" (Orin Dafidi 18:26).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| | Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 31/8/2026 | Wa Oluwa Nisinsinyi | Isaiah 55: 1-6 |
| Ojo Isegun | 1/9/2026 | Yipada si Oluwa ni tooto | Isaiah 55: 7- 11 |
| Ojoru | 2/9/2026 | Bi O ba se ri beeni Olorun yo ri si o | Orin Dafidi 18: 20-26 |
| Ojobo | 3/9/2026 | Ma se je alagabagebe eniyan | Matt. 15: 7-9 |
| Ojo Eti | 4/9/2026 | A fi aidunnu Olorun han | Esekieli 20: 1-4 |
| Ojo Abameta | 5/9/2026 | A fi ife Olorun han si awon eniyan re | Esekieli 20: 5-7 |
| Ojo Aiku | 6/9/2026 | Ma se sote | Esekieli 20: 8-9 |

**ORO AKOSO**

Nigba ti awon omo Israeli ti wa ni igbekun ni Babiloni fun odun meje, ti o si ti pe odun meji leyin ti woli Ezekieli bere si ni sotele, awon agba kan ti a ko mo oruko won wa lati gbo lati odo Olorun nipase woli re. Ko daju boya awon agba wonyi wa lara awon igbekun naa tabi pe won wa lati Jerusalemu fun ibeere na. Won wa gege bi eni ti n wa lati mo okan Eleda won nipase woli re, sugbon ki i se pelu okan to to. Ibeere won je ti alagabagebe ati pe ki i se otito lati inu okan won wa. Se eyi ki i se ipo ti okan opolopo wa niwaju

Olorun ati ninu ise re lonii? Nitorinaa, Iwe Mimo so pe, “Awon enia yi nfi enu won sunmo mi, nwon si nfi ete won bola fun mi; sugbon okan won jina si mi.” (Matiu 15:8).

**EKO**

**I. WIWA SIWAJU OLORUN LATI SE IWADI (Esekieli 20: 1-3)**

O je ohun to lola lati lo siwaju Olorun lati mo ife re lori gbogbo apa igbesi aye enikan. Opo awon eniyan mimo igbaani lona kan tabi omiiran lo lati mo okan Olorun yala fun ra won tabi nipase awon iranse re. Mose ba Olorun soro lori oke Sinai, nibe ni Olorun fi itosona fun un (Eksodu 19: 3-8). Nigba orisirisi ati akoko ni igbesi aye Dafidi, o ba Olorun soro, o si ri itosona ati itoni (1Samueli 23:1-5; 30:1-19; 2 Samueli 2:1-3; 5:17-25). Sugbon ko ye ki enikan ko bere irinajo ti ko nife si lati ri opin re. Wiwa si iwaju Olorun lati mo ife re pelu okan ti o ti pinnu lati tesiwaju nipa ife ara eni je ifi akoko eni sofo, ifi akoko awon iranse Olorun sofo, ati ifi ore-ofe Olorun lori awon iranse re sofo. O san lati mase lo si iwaju Olorun lati mo ife re Lori ohun kan ju ki a lo pelu okan ti ko setan lati gba itoni re. Nitorinaa, o da bii pe Olorun ko ni fe si ati so ohun kan fun won nitori pe o mo pe won ko je olotito ninu okan won fun wiwa ti won wa siwaju Oun fun iwadi (Ezekieli 20: 3).

**II. OLORUN BINU SI AWON ENIYAN RE (Ezekieli 20: 2-4)**

Nigba ti o daju pe awon to wa se iwadi tabi bere nkan je awon alagabagebe, Olorun pase fun woli lati so okan re fun won. Nipataki, a pase fun un lati se Idajo won. Ni oro mii, woli naa gbodo doju ko won pelu otito okan won ti ko yato si ise ati iwa awon baba won. O ni lati doju oro na ko won lona to lagbara. Olorun a maa binu si isote, laiwo bo se kere tabi tobi si. Itan yi fi han pe Olorun binu si awon eniyan re. Aidunnu si ati ibinu Olorun tun je idi ti ko fi fe ki won wa bere ibeere tabi se iwadi ohunkohun lodo Oun. Bibeli so pe Olorun n binu si elese ni gbogbo ojo (Samu 7: 11). Pelu, elese ti wa labe idajo Olorun na ayafi to ba ronupiwada (Ezekieli 18: 20). Ma se gbe ninu ese ati isote ti o ko ba fe ki ibinu Olorun ba o. Ronupiwada kuro ninu awon ese re lonii ati nisinsinyi ki o to pe ju.

**III. A SO FUN WOLI NA AWON OHUN TI YO SO (Esekieli 20: 5-9)**

A gbodo mo pe gbogbo ohun ti woli yo so gbodo je ohun ti Olorun so fun un (Ezekieli 20: 2, 3). Awon iranse Olorun gbodo ko lati duro niwaju Olorun titi ti won yo fi gbo ohun ti Olorun fe ki won so fun ijo ati awon eniyan re. Ki i se pe ki won maa mu oro ti tara won wa sibi ijosin ni ori pepe, sugbon ki won mu okan ati ife Olorun wa lati ite aanu re. Won gbodo so ni kedere, lai beru tabi lai se ojusaju. Won gbodo je alagbara, ti ko ni beru, sugbon pelu iwa pele, irele ati okan ti o mo wipe a gbe ojuse nla le ohun lowo, ni fifi oro Olorun han fun awon eniyan. Arakunrin Stefani je apeere rere ninu oro yi (Ise awon Aposteli 6, 7). O se pataki ki a ba a se itankale oro Olorun ni ibamu, bii onise omo kekere ti n je wara (1Peteru 2: 2-3), onise to ti dagba ninu igbagbo ti n jeun onje to lagbara ati egungun (Heberu 5: 12-14; Johanu 6: 53-61), ati oro ebe ati riro ni fun awon eni to ti sonu ti a n gbiyanju lati mupadabo sinu Kristi (Matiu 9: 2; Johanu 8: 10-11; Luuku 15: 20-24; Ise awon Aposteli 13: 43; 2 Korinti 5:11). Ninu gbogbo re awon iranse Olorun ti n mu okan Olorun wa fun awon eniyan gbodo se e pelu ife. Laise aniani, oro Olorun to awon olusewadi wa. A so fun won bi Olorun se ba awon baba won to wa saju won se, ati iha buburu ti awon baba won ko si ife Olorun, gege bi ati se afihan re ninu awon koko ti o wa ni isale wonyi:

1. Olorun yan Israeli lara gbogbo orile-ede aye. Anfani nla wo loto eyi!
2. Si Israeli nikan ni Olorun fi ara re han fun (Eksodu 6: 3). Anfani nla wo loto eyi!
3. Olorun se ileri igbala kuro ni igbehun Egipti ati fifi ile ti a se ileri fun won (Ezekieli 20: 6; Deuteronomi 8: 7; 11: 12). Gbogbo ileri wonyi ni iwe mimo se afihan re wipe o wa si imuse.
4. A fun won ni ase Olorun lati mu gbogbo awon orisa ati ere kuro. Sugbon won ko, won si sote (Esekieli 20: 7, 8). Se o ti mu awon orisa inu okan re ati igbesi aye re kuro? E je ka daruko die ninu awon orisa wonyi ti n se idena ibasepo wa pelu Olorun lonii. Olorun je Olorun owu, ko fe ki elomiran tabi ohun kohun

ba pin aye (space) re ninu aye re (Eksodu 20: 3; Deuteronomi 4: 23). Je ki Olorun ni gbogbo akoko re, agbara re ati ohun ti o ni.

5. Nigba ti ko si ohun miiran lati se, Olorun pinnu lati je won niya. Sugbon ko se be fun ola oruko re (Ezekieli 20: 8, 9). Idajo Olorun lori awon ti n ko lati teti si Olorun ati awon ti n sote si, je ohun to daju, ohun ti ko le sai sele, to si n bo laipe, sugbon o n mu suru pe ki awon ti won n gbe ninu iyerira le wa si ironupiwada (2 Peteru 3: 9).

Awon ohun ti a ti gbe yewo wonyi ni Olorun pase fun woli re lati so fun Israeli nitori iwa aimoore ati isote won. Irufe igbe aye ti a n gbe gegebi bi Kristeni yo fihan boya a moriri gbogbo ohun ti Olorun ti se fun wa ati awon anfani ojoojumo ti o n mu wa fun wa. Bi a ba je eniti o moriri awon ohun ti Olorun n se, a o bowo fun a o si gboran si awon itosona ati ase re, ati pe sise awon ohun ti O ba so ki yoo je ise to nira fun wa (1Johannu 5: 3). Woli naa so jise gege bi a ti ran an, ko fi kun un, ko si yokuro ninu re. Ko si idi kankan fun fifikun. A gbodo jise Oro Olorun ni kikun, laisi a n dogbon si tabi ayinike kankan. Awon iranse Olorun gbodo sora nipa yi.

Se ijosin re niwaju Olorun je lati inu okan otito wa? Se o ti mura sile fun ibawi ati atunse lati ori pepe tabi o wa lati safihan wiwa ati irisi re nikan? Re ara re sile ki o gboran si awon oro re ti o n to o wa lati inu asaro ninu oro Olorun nigbati ti o n ka bibeli re tabi lati ori pepe wa lonii.

**IBEERE**

1. Ta ni woli ti won ba soro?
2. Awon wo lo wa ba woli soro?
3. Ki ni ohun to wa ninu okan won niwaju woli?
4. Bawo ni o se ye ki iranse Olorun se agbekale iwasu re?
5. So meta ninu awon ohun ti a so fun woli ki o so fun awon to wa sodo re fun ibeere tabi iwadi.

**SEPTEMBER 13, 2026** **EKO 37**

# ISRAELI KEGAN AWON ILANA AT'ORUN WA

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 20:10-17*

***ESE AKOSORI:-*** *"Nitoripe isote dabi ese afose, ati agidi gege bi iwa buburu ati iborisa. Nitoripe iwo ko oro Oluwa, on si ko o li oba". (1 Samueli 15:23)*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| **MON** | 7/9/2026 | Aigboran lewu pupo | Awon Oba Kinni 13: 20-26 |
| **TUE** | 8/9/2026 | Mejeji lo lere | Isaiah 1: 18-20 |
| **WED** | 9/9/2026 | Gbogbo oro ati ise la o dalejo | Owe 12: 13-14 |
| **THUR** | 10/9/2026 | Kii se olugbo bikose oluse | Jakobu 1: 21-25 |
| **FRI** | 11/9/2026 | Isote dabi Aje sise | Samueli kini 15: 22-26 |
| **SAT** | 12/9/2026 | Te le ase Olorun | Esekieli 20:10-12 |
| **SUN** | 13/9/2026 | Mase sote | Esekieli 20:13-17 |

**ORO AKOSO**

Olorun ko dekun fifi ese Israeli han an, bere lati ona igbesi aye won ti o bere lati igba ti won wa ni Egipti, ni tito ka si awon baba won gege bi a ti gbe ye wo ninu eko isaaju. Oro ti a fi fun woli Esikieli lati so

fun orile-ede Israeli nipase awon agbagba ti won n foro wa oro wo lenu re ntesiwaju nigba ti Olorun n soro nipa ona ati ihuwasi awon baba won ni oniruru akoko igbesi aye won. Bayi, awon ihuwasi won si awon ilana re lakoko ti won rin ninu aginju ni eko yi gbeyewo. O je ohun ti ko dara lati ri ki awon baba ma huwa tabi ni awon iwa aibikita si Eleda won ati awon ilana re. A tun gbodo keko lati inu itoni ti a fun woli lati mu wa si iranti isote awon baba won ti fi aye sile fun nkan bi edegbeta odun o le seyin pe ko si ohun ti a n se lonii ti a ko ni mu wa si iranti bo pe bo ya. Otito yii ye ki o saakoso awon ihuwasi ati awon ise wa lojoojumo lati gbe igbe aye to to ati huwa lona ti a le gba gba igboriyin yala nipa temi tabi tara (Oniwasu 12: 14).

**EKO**

**I. OLORUN FUN ISRAELI NI IPO RE (Esekieli 20: 10-12)**

Lati se afihan bi Olorun se ni ife pataki ninu awon eniyan re o fun won ni awon ofin lati to won sona. Ko fe ki won gbe aye won ni ona aibikita ati aniijanu. Ko fe ki won ma gbe bi awon orile-ede miran ti won ko ni ati ti won ko sin Olorun kan na. O fe ki won yato ki won si dawa ya to larin awon gbogbo orile-ede agbaye. Ko fe ki won kan ma gbe bi awon elomiran lasan, nitoripe won je iran ti a yan, olu alufa, eniyan oto ti o n fi iyin Eleda ati Eni ti o pe won han (1 Peteru 2:9). Nitorina, awon ofin ti a fun won wa fun idi yi, pe ti won ba gboran si won patapata, ti won n fi won sinu ise, ninu irinajo ojoojumo aye won, ise won, ati ninu ohun gbogbo to je ti esin won, awon eniyan layika won yo ri wipe eniyan oto ni won, won a si ma bawon lo gegebi eniyan oto ti won je. A ni lati mo wipe oro Olorun ohun ni ofin re fun wa. Ohun kan ti o mu wa yato si awon alaigbagbo ni yi. Oro re ni o ma n ya wa soto nitori wipe a n reti wipe ki a gbe igbe aye wa ni ibamu pelu oro re (Orin Dafidi 119: 9; 11, 72). Ni pataki, Olorun je ki o di mimo lati enu woli re pe ti enikan ba tele awon ofin re ti o si n se won, yo mu iye wa fun irufe okan be (vs. 11). Lati ba Olorun gbe ni lati pa awon ase re mo (Johanu 14: 15). Kini idakeji iye? Kini yo sele ti enikan ba yan lati gbe igbe aye re laisi tabi lona ti o tako awon ofin Olorun? Ti o ba je wipe gbigbe nipa oro Olorun jasi iye, a le so wipe, gbigbe lodi si oro re jasi iku pelu. Igboran je gbogi si wiwa laaye. Nigbati okunrin ati obinrin akoko se aigboran si itona lati oke wa, won pe iku wole, sugbon ni won igba ti won si n gbe ninu igboran, won ye. Awon ojo Sabaati (Ojo Isinmi) je ojo ti Olorun yan lati ya soto, ti a so di mimo, ti a ya soto fun ise isin Olorun ati isinmi ti ara eni lati inu ise ojoojumo laarin awon omo Israeli. Awon ojo isinmi ran Israeli leti majemu Olorun pelu won, gege bi Olorun won ati awon, awon eniyan re. Pipa Sabaati mo ni a tumo si pe ki a tele e gege bi omo Israeli. Eyi lona kan, fi owo ati ola won han si Olorun won ati awon ase re bi won se n mura tan ti won si n segboran tokantokan. Lati se afihan pataki ati agbara ti Ojo isimi, awon ijiya wa fun ikuna ni pipa a mo bo tito ati bo tiye (Eksodu 35: 2, 3; Lef. 23: 3; 26: 35). A se akiyesi pataki oro naa “Awon Ojo isimi” ti o n fihan wa wipe kii se Ojo isimi kan nikan, bikose awon ojo isinmi, ti o n toka si awon apejo laarin ose. Lonii, ninu irinajo wa gegebi eniti o wa ninu ijoba re pelu, a ni ju awon ojo isinmi ti a toka si laarin awon omo Israeli lo lati sakiyesi gege bi awon ti o wa labe majemu tuntun ti o si dara ju majemu laelae lo. A ni lati bu ola fun awon apejopo ati awon ijosin gegebi ara, gege bi eto ijosin ati awon akoko ti a ti la kale fun ijosin gegebi afikun si ijosin Ojo Oluwa ti o je asa ati eyiti ati mo ni aigbodo mase (Heb. 10: 27). Iwonyi ni awon ojo isinmi wa lonii labe majemu tuntun. Awon onigbagbo ninu Kristi gbodo sora lati maa farahan leekan lose nigba ti awon isin abenu ose ba wa tabi awon isin pataki laarin ose, bi awon eto ati akoko ba se pe fun won. A gbodo wa larowoto fun awon eto isin ati ijosin gbogbo wonyi nitori wipe awon ni gbogbo ohun ti o duro fun pipa awon ojo isinmi wa lonii, nitori wipe a n reti wipe ki a gbe igbe aye wa lona ti o daraju, ki a si se daradara ju awon ti o wa labe ofin Mose lo ni gbogbo ona gege bi awon ti o wa labe majemu tuntun ti o si dara ju (Ise 2: 42, 46, 47; 3: 1, 2).

**II. AIBIKITA ISRAELI FUN IPO OLORUN (ESI. 20: 13-16)**

Aibikita ti Israeli se fun ipo Olorun ni a ka si isote. Isote je kiko lati gba ase tabi ilana tabi agbekale. O je ilodi si ase tabi isakoso. Israeli ko ase ati idari Olorun sile, nipa saigboran si awon ofin ati ilana re. Lati

je olote ki se ohun ti o nira, o kan ti le pe fun aigboran kekere si awon ilana. Ni pataki, isote naa ni a se akiyesi ninu awon ise wonyi:

(a) **Kiko ati ikuna lati rin ninu awon ofin Olorun** - nigba ti awon ofin tabi itoni kan lati odo Olorun ko ba bawa lara mu, se ki n se wipe a ma n ko won sile ni? Nje a ko yan awon ona tiwa ni opolopo igba dipo tire (Isa. 55: 8, 9). Yala itoni Olorun fun wa dara tabi bee ko, a gbodo ko bi a se n teri ba fun won, ki a ma si se ko won.

**(b) Egan fun awon ilana/ase Olorun** - owo wo ni a fi n mu awon oro Olorun ti o n to wa wa lati orii pepe ati awon aga iwasu lonii? Nigba ti awon iranse Olorun ba n tu okan Olorun jade si wa bawo lo se n ri lara wa, iha wo ni a n ko si? Se a ko si lara awon to n soro lodi si oro Olorun to n jade lori aga iwasu nigba kan naa bi won se n so oro Olorun lowo? A ni lati so ise ati ihuwasi wa si oro ati ilana Olorun.

**(d) Biba awon Ojo isimi je** - won se lodi si awon ilana Olorun nipa bu ola fun ati sise awon Ojo isimi ni mimo fun Oluwa. Won kuna lati pa awon Ojo isimi mo bi o se to ati bi a se n reti lati odo won. Nibo ni o wa nigbati awon ipe ba dun fun awon eniyan Olorun lati pejo fun ijosin? Se o wa lara awon ti won so pe won ko ni akoko lati farahan fun ipade eko Bibeli ati awon ipade adura ni apejo agbegbe/ijo re sugbon to ni akoko lati lo si awon ayeye ati awon ode ti o n gba opolopo akoko, owo ati awon ohun elo miran lowo re dipo igba ju eyi ti o n lo ninu ijosin niwaju Oluwa re lo? Ronupiwada lonii, ki o ma se ba awon Ojo isimi je mo.

**(e) Iborisa ninu okan** - won n so pe won si je ti Olorun sugbon jinle ninu okan won ni ife lati tele awon orisa (Esekieli 20: 16d). Eniyan melo ni o wa lonii ni ile ijosin sugbon okan won wa ninu ati pelu nkan miiran. Awon orisa ti owo, ise, okiki, aseyori ni gbogbo ona, ati bebe lo, ti wa ni ipele ti o jinle ninu okan wa. Eleda n wo ohun ti o wa ninu okan wa ati bi won se se deede pelu ife re, e je ki a sora.

## III. ETO OLORUN LATI FIYA JE ISRAELI ATI ANU RE LEYIN NAA (ESI. 20: 13-17)

**(a) Ipinnu Olorun lati fiya je awon eniyan re**

Isote Israeli si ilekun fun ipinnu Olorun lati fiya je awon omo re ayanfe. Wonyi ni awon ijiya na:

**(b) Olorun pinnu lati tu ibinu re jade si won (Es. 20: 13g)** - tani o le duro ni ibiti ibinu Olorun gbe wa?

**(d) Olorun yi okan re pada lori mi mu won wa si ile ileri (Ez. 20: 15)**. O ye ki a sora nitori iwa aiseedeede wa le fa ki Olorun yi okan re pada lori awon eto ti o lewa re fun igbesi aye wa. Eli ati idile re lugbadi eyi (I Sam. 2: 27-30).

**(e) Olorun pinnu lati je won run - o se ileri lati se be ninu ibinu re (Esekieli 20: 13h)**. O je, O si tun n je ina ti n jonirun, e je ki a sora (Heb. 12: 29).

**(f) Anu Olorun**

Bi o ti le je pe inu Olorun ko dun si iwa ati ona won, ti o si seleri lati fiya je won, sibe o saanu won. Olorun pinnu lati ma se fiya je won gege bi o ti so tele fun idi pataki kan pe: Nitori oruko re - Olorun n sakiyesi, o si bikita nipa ohun ti a o so nipa oruko re laarin awon keferi nitorina o jawo ninu ijiya ti o fe fun won (Esekieli 20: 14). A gbodo bowo fun oruko Oluwa lona ti o ga nipa sisa fun ohunkohun ti yoo fun awon alaigbagbo lanfani lati soro lodi si oruko Kristi.

Gbogbo ohun ti a ti gbeyewo loke ni oro Olorun si Wolii Esekieli nipa fifi aidunnu re han si isote Israeli. O mu wa si iranti ohun to sele ni aginju nigba ti won kuro ni Egipti. O dara lati ko eko lara awon asise awon ara iwaju ki won si je itosona ti yo ran wa lowo lati mase bo sinu ofin kanna tabi irufe re. Ko eko lara awon asise awon omo Israeli lonii ki o je ki igbesi aye re gba ona ti o yato fun rere.

**IBEERE**

1. Ni bo ni awon asise awon omo Israeli ti a so nipa won yi ti sele?
2. Kini abajade gbigbe nipase ofin Olorun gege bi a ti ko ninu eko naa?
3. Kini ofin Olorun fun wa lonii?
4. Bawo lo se ye ki awon omo Israeli se si Ojo Isinmi?
5. So ijiya meta ti Olorun se ipinnu fun awon omo re alaigboran ati ohun to da Olorun lowo ko.

**SEPTEMBER 20, 2026** **EKO 38**

# BI AWON OBI; BE NI AWON OMO

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 20:18-26*

***ESE AKOSORI:-*** *"To omode li ona ti yio to: nigbati o si dagba tan, ki yio kuro ninu re. (Owe 22:6).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| | Ojo | Deeti Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| **MON** | 14/9/2026 | Eyin obi e kiyesara | Gen. 27: 5-13 |
| **TUE** | 15/9/2026 | Eto awon omo yin ni ona ti Olorun | Owe 22: 6 |
| **WED** | 16/9/2026 | Ki won Mase dabi awon baba won | Orin Dafidi 78:1-8 |
| **THUR** | 17/9/2026 | Yago fun ibinu Olorun | Orin Dafidi 78: 30-38 |
| **FRI** | 18/9/2026 | Won pehinda bi awon baba won | Orin Dafidi 78:54-64 |
| Ojo Abameta | 19/9/2026 | Mase rin ni ona aiwabi Olorun awon obi | Esekieli 20:18-20 |
| Ojo Aiku | 20/9/2026 | Isote nmu iku wa | Esekieli 20:21-26 |

**ORO AKOSO**

Ninu eko to saaju, a ri bi Olorun se binu si awon eniyan re ayanfe nitori isote won. Isote awon baba ni a soro re ninu eko naa. Iran ti o saaju, ti ise awon baba, mu Olorun binu nipase aigboran ati ise won ti o kun fun ife inu ara eni, debi ti Olorun ti pinnu lati pa won run bi ko se fun aanu re. Ninu eko ti tonii, awon omo ni Olorun n bawi fun titele iwa aigboran ati isote awon obi. Nje idi ti eyi fi ri be ha soro mo bi? Agbekale eko to nise pelu ijijadu larin iseda ati itoju gegebi imoijinle saikoloji (eko nipa okan ati ihuwasi eniyan/eranko) le ran wa lowo ni ikorita yi, ti o ba dabi eni pe oro na fe da bi aditu. Agbekale eko na se alaye nipa ohun meji ti o je okunfa ihuwasi eniyan: ajogunba, ati agbegbe. Eko naa salaye pe gbogbo iwa ti enikan ba n gbe jade tabi hu je ohun ti eni na jogun latodo awon obi re ati ohun ti o ko ni ayika re. Awon obi je awokose fun awon omo won. Boya lona taara tabi aise lona taara, awon obi n se apeere ona igbesi aye ti awon omo won yo tele. Eyi ni idi ti awon obi gbodo wo awon ona won, awon oro ati awon igbesi aye won ni ayika awon omo won ati ni ibikibi ti won ba ri ara won. Pelupelu, agbegbe wa, eyiti o n so nipa ibi ti a n gbe ati awon ohun ti o wa ni ayika wa ati awon ohun ti o n se le ni be, ni agbara lati sakoso iwa ti enikan n hu. Awon obi tun gbodo se a mo ju to daradara ayika ti awon omo won ma n lo si, awon eeyan ti won n ba won soro, fiimu ti won n wo, orin ti won n gbo ati ti won n ko, ati irufe awon ore ti won n ba rin. Won ko gbodo ko iha kokanmi tabi se aibikita nipa gbogbo nkan iwonyi.

**EKO**

**I. ASE OLORUN FUN AWON OMO WON (Esekieli 20: 18-20)**

Awon ase Olorun nihin-in je ikilo ati itoni pe bi won ba tele won yoo mu ire wa fun won. A ri bi Olorun se nifee won to, o si saniyan nipa won eleyi ti o mu ki O fun won ni ikilo ati itoni gege bi Baba onifee ati olutoju ti ko fe pa awon omo re lara. Olorun kilo fun awon omo awon baba olote naa, o si fun won ni awon itoni wonyi:

* **Mase rin ninu tabi tele awon ofin awon obi re** (Es. 20: 18a-d) - iyen je itokasi ti o han gbangba pe awon ofin awon obi won yato si awon ofin Olorun. A ko gbodo tele eyikeyi ofin ti o tako awon ofin Olorun laibikita ibiti o ti wa. Ranti itoni Nebukadineseri fun gbogbo eniyan lati foribale fun aworan wura re. Awon omo Heberu meteeeta naa ri itoni yen gege bi eyi ti ko ba ohun ti won mo pe o je itoni Olorun tiwon mu, nitorina won dagunla si, bi o ti le je wipe won mo wipe didagunla si tumo si ijiya iku (Dan. 3: 10-30). Beeni, awon omode ni lati gboran si awon obi won sugbon a ko gbodo gbagbe pe “ninu Oluwa nikan” (Ef. 6: 1). Baba re alaigbagbo ti o ni imoran alaiwa-bi-Olorun fun o ni a gbodo ri gege bi eni ti n sun o lodi si awon itoni mimo Olorun, bakan naa ni o ri pelu awon obi re ti won so pe Kristeni ni won, sugbon ti won fun o ni imoran alaiwa-bi-Olorun. Awon obi ti won ma npe de si awon isin ile ijosin ye ki o sora, won nko awon omo won lati ma se bakanna laimo. Awon obi ti ma nwa si ile ijosin leekan pere lose n so fawon omo won lona taarata pe awon ijosin ati eto kan ninu ijo ko se pataki, won ko si nilo lati wa nibe, ni irufe ise bayi tumosi. Gbogbo wa ni a n gbin awon irugbin ti yoo dagba lati so eso ni ola. Awon eso wo ni iwo yoo fe lati rii irugbin ti o n gbin loni so ninu aye awon omo re ni ola?
* **Mase so ara re di elegbin pelu awon orisa awon obi re** (Esekieli 20: 18d) - awon obi won ti se agbekale awon ona orisirisi lati sunmo Olorun nipa sise awon aworan ati siso won di orisa ti o lodi si awon ofin Olorun si won (Eksodu 20: 1-5). Lati ba asa buruku yii je, Olorun kilo fun awon omo won pe ki won ma se dara po mo iwa aigboran ati isote naa. O kilo fun won nipa jije ki won mo pe sise bee yoo tumo si egbin emi ati okan won ti yoo si jasi egbin ara won nikeyin. Leekansi, a ranti awon omo Heberu ti won pinnu lati mase so ara won di elegbin pelu ounje adidun oba (Dan. 1: 8). O si je ikilo kan naa fun wa titi di oni olonii gege bi omo Olorun, a gbodo sora lati so emi, okan ati ara wa di alaimo pelu orisa awon obi wa tabi awon ti a ti se fun ara wa.
* **E mase rin ninu awon ilana/ofin awon obi yin** (Esekieli 20: 19a-d) - won ko ni lati rin ninu ilana awon obi won tabi awon ilana ti ara won sugbon ninu ti Olorun. Dekun lati ma a rin ninu awon ona tire, ki o si wa tele awon ona Re ti o n yori si iye (Owe 14: 12; 16: 25).
* **Gbe nipa awon ofin Olorun** (Esekieli 20: 19d) - iyen ni, ko lati se ife Olorun. Kristi so pe, ife re ni ki a se ni aye bi ti orun (Matth. 6: 10). Gbigba awon ilana Olorun je tite riba fun ife re, eyiti a n reti lati odo gbogbo awon onigbagbo ninu Kristi. Sayeewo ipo re ninu imole oro yi.
* **Pa awon Ojo isimi Re mimo** (Esekieli 20: 20) - Olorun fe ki awon omo olote di onigboran si pipa awon ojo isinmi mo, ki won ma si so o di alaimo bi awon obi won. Bibu ola ati bibowo fun gbogbo igba ati akoko lati wa niwaju Olorun je ibowo fun ojo isinmi wa loni, eyi si je ami pe a mo on ni Oluwa wa. Oro ti a n pe ni “Oluwa” n soro nipa jije Oni nkan. Ti o ba je Oluwa wa nitooto o gbodo je oluwa lori ohun gbogbo ti a ni. Owe kan ni ede Yoruba se agbekale re daradara ni gbati o so pe: Eni ti o ni eru ni o ni eru. Bi Olorun ba je Oluwa re, ko ni soro fun o lati wa niwaju re nigbakugba ti o ba pe e.

## II. AWON OMO SOTE GEGE BI AWON OBI WON.

O da bi ekun bi Olorun se tu irora okan re jade ninu oran awon omo awon obi olote/alaigboran. O fi han ni ona kan pe Olorun n reti igbesi aye to dara ju ti awon obi won lo lati odo won sugbon won je ijakule fun un.

Awon ohun ti ibanuje okan Olorun na je:

* Won sote si Olorun (Esekieli 20: 21).
* Won kuna lati rin ninu awon ofin Olorun (Esekieli 20: 21).
* Won ko lati gboran si awon ase Olorun (Esekieli 20: 21).

* Won se iselu awon Ojo isimi (Esekieli 20: 21).
* Won ni oju ati okan won lori awon orisa baba won (Esekieli 20: 24).

**III. IPINNU OLORUN LATI FIYAJE AWON OMO WON (Esekieli 20:21-26)**

**(a) Ipinnu Olorun ti ko rewa**

Ninu imoijinle Fisisi (Physics), Ofin Newton Keta ti isipopada so pe: Fun gbogbo ise, ise dogba ati idakeji wa. Fun ona isote ti awon omo tun ti pinnu lati rin gege bi awon obi won na ti se, Olorun ni okan lati fiya je won ni ona kanna bi awon obi won:

Olorun se ileri lati tu ibinu re le won lori (Esekieli 20: 21).

Olorun fe tu won ka saaarín awon orile-ede Keferi (Esekieli 20: 23).

Olorun ba won lo lona buburu, o si fun won ni awon ofin ti ko le fun won ni ire ati iye (Esekieli 20: 25).

Olorun mu ki won se ohun irira, ni fifi awon omo won rubo si orisa (Esi. 20: 26) - eyi je iriri to ga nigbati won ko lati gboran si Olorun.

Nigba ti Olorun ba jawo ninu igbesi aye enikan, ti O si fi I sile lati se ohunkohun to ba fe se tabi wu, apere wipe ina n be lori orule irufe eni be ni yen. E je ki a ka awon ese Iwe Mimo wonyi, ki a si so ero wa ni ibamu pelu koko ti a n yannana yi: Roomu 1: 18-32. Ohun ti o buru jai ni ki Olorun fi eni kan ti o gba iyerira laye ninu aye re fun ife ti ara re. A mo ohun ti abayorisi irufe iri be yoo je - iparun.

**(b) Olorun alaanu** (Esekieli 20: 22)

Bi o ti le n binu, O si tun n wo ola ati ise iyebiye oruko re paapaa julo laarin awon keferi. Olorun ko fe ki won fa oruko re sinu ere. O saniyan nipa ohun ti awon orile-ede alaigbagbo ti won ti ri bi Olorun won se buru to ati bi o se n ja fun won lati mu won lo si ibi ti o ti se ileri, yoo so nipa re (Deu. 9: 25-28). Nitorinaa, ko ni se gbogbo ohun ti o so pe oun yoo se gege bi ijiya fun isote won. Aanu Olorun si wa lonii. Mase fi aanu re ta tete, mase fojurena anu re. Olorun feran re, jowo ara re ki o si teriba fun un ati awon ilana re.

Ki Olorun to le so fun awon omo pe ki won ma se tele ona igbesi aye awon obi won tabi ki won rin ninu awon ofin ati ilana won fi han ni kedere pe, ihuwasi awon obi ati ona igbesi aye won ko ye fun iyin nitorinaa, ko ye fun afarawe. O ye ki awon obi kiyesi igbesi aye won, ki won wo ibi ti o ti le ni ipa ti o lodi ninu aye awon omo won. Je ki awon obi ki o yipada si iwa bi ti Kristi ninu ohun gbogbo fun awon omo won lati le tele apere rere, ki awon omo wonyi ma ba nipa ninu ijiya kanna ti o le subu sori awon obi won.

**IBEERE**

1. So meta ninu awon ase ti Olorun pa fun awon omo awon obi to se aigboran wonyi.
2. So meta ninu awon ona ti Olorun fi ni ijakule ninu awon omo na.
3. Ona meta wo ni Olorun n pinnu lati fi iya je awon omo won?
4. Kinni o mu ki Olorun o yi ipinnu lati fi iya je awon omo won pada re?
5. Kinni ipa ti igbeaye ti obi n gbe le ni lori awon omo won?

**SEPTEMBER 27, 2026** **EKO 39**

# YIYAN ISRAELI LATI DABI AWON ORILE-EDE MIIRAN

***BIBELI KIKA:-*** *Esekiel 20: 27-32*

***ESE AKOSORI:-*** *"Nitoripe enia mimo ni iwo fun Oluwa Olorun re: OLUWA Olorun re ti yan o lati je enia oto fun ara re, ju gbogbo enia lo ti mbe lori ile." (Deuteronomi 7:6).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 21/9/2026 | Mase jowu awon elese | Orin Daf. 73:1-11 |
| TUE | 22/9/2026 | A fi otito han ninu ago mimo | Orin Daf. 73:12-17 |
| WED | 23/9/2026 | Opin awon alaiwa bi Olorun | Orin Daf. 73:18-28 |
| THUR | 24/9/2026 | Yato nitoripe eni oto ni o | Deu. 7: 1-7 |
| FRI | 25/9/2026 | Mase safarawe awon orilede miran | Deu. 12: 28-32 |
| SAT | 26/9/2026 | Ewo ni | Esekieli 20:27-28 |
| SUN | 27/9/2026 | O ko gbodo dabi awon keferi | Esekieli 20:29-32 |

## ORO AKOSO

Olorun si n ba woli re, Woli Esekieli soro lakoko ibewo awon alagba kan ti won wa gbo lati odo re gege bi a ti salaye tele ninu okan lara awon eko to saaju. Ninu eko tonii, a maa sawari pe Olorun soro soki lori ihuwasi won ni ile ileri ati leyin naa, awon ise won titi fi di akoko Esekieli ti won wa ba ni gbolohun. Lapapo, inu Olorun ko dun nitori pe ona igbesi aye won ati ise won ko yato si awon orile-ede Keferi to yi won ka, nitorinaa o ka wiwa won si odo re fun iwadii laisi ironupiwada tooto ati igbesi aye olododo gege bi etan. E je ki a kiyesi pe Olorun nife si gbogbo abala igbesi aye wa lati mo ki ni o nsele nibe. O nife si ohun ti a n so ati bi a se n so, bawo ni a se n rin, ise wa ati bii a se n se. Olorun n se akosile ohun gbogbo ti o n se, nitorina, ma a gbe igbe aye re ni ona ti o to, ki o si ma a gbe igbe aye ti o wu Eleda re.

## EKO

### I. ISOTE NI ILE ILERI (Ezekiel 20:27-28).

#### (a) Ase lati soro leekan si (Ezekiel 20: 27a-c)

Olorun n soro, o n soro lori oro isote ati aigboran kan naa. Kilode ti Olorun ko dake? Ki ni idi ti itenumo fi wa lori awon oro kan naa ti ese Israeli? Nitori pe dipo ki won ronu piwada ki won si tun ona won se, won tubo buru si i. Titi di igba ti Olorun yo o fi ri iyipada rere ti o fe yoo tesiwaju lati fi awon oro ati ikilo ranse si awon omo re. Woli Isaiah ninu okan lara awon asotele re so pe, "Nitori Sioni, emi ki yoo dake, nitori Jerusalemu, emi ki yoo simi, titi ododo re yoo fi jade bi titan imole, ati igbala re bi fitila ti n jo," (Isa.62.1). Awon iranse Olorun, gege bi oluso agutan, won ko gbodo je ki o su won lati ma sa mojuto awon agutan ti won wa ni ikawo won, won gbodo tesiwaju ninu iwaasu, kikoni, imoran, ibawi, ikilo, atunse, titi ti a o fi seda Kristi ninu awon ti Olorun fi si ikawo won. Won le ma feran re, won le korira won sugbon iyen ko ye ki o pa awon iranse Olorun lenu mo gege bi awon ti a ti gbe kale fun idi yen ati gegebi awon ti yoo jabo ise iriju won fun Olorun (Titu 2: 15; Heberu 13: 17; 2Pet. 3: 16, 17).

#### (b) A so nipa Isote awon baba (Ezekiel 20: 27d-28)

Awon baba ti o ye ki won mo awon ofin Olorun ki won si tele fun anfani awon iran to n bo kuna patapata. Awon gan ni won tun wa n te awon ofin na mole, ti won si ti so won di ohun ti ko ni ipa kankan. Awon esun ti Olorun fi kan won ni wonyi:

(1) **Won so oro odi si Olorun (Esekiel 20: 27e-f)**

Kin ni oro odi? O je sise aibowo fun Olorun. O tun je fifi iwa mimo Olorun dun. Jesu soro nipa oro odi nigba kan ninu awon akosile awon Ajihinrere (Matt. 12: 31). Lati ko Eleda eni sile je iwa aibowo fun ni ti o ga ju lo. Awon baba ko Olorun tooto ati alaaye sile, eni ti o tobi ti o si lagbara ninu igbesi aye won, aarin, ati irin ajo won, fun awon olorun eke ati oku. Won se Olorun. Nje o ranti kiko Kristi fun igba die ti Peteru (Luku 22: 54-62). Won da a. Ronu nipa bi o se ma n ri lara nigbati enikan ba ni iriri iwa odale eniyan. Eje ki a ranti iwa odale nla ni igba aye Jesu ati ise iranse re (Matt. 26: 48-50). Won ko Olorun. Won fi owo yepere ati aikasi mu awon oro ati ilana re. Ise yii je ibanuje si Eleda ati Baba won onife ati olutoju. E je ki gbogbo wa dahun awon ibeere wonyi si inu: Eyin baba, owo wo ni e fi mu Olorun ati awon oro re loni? Se ki n se owo yepere le fi mu awon oro ati ilana re, tabi pelu okan isaroye nla? Eyin iya ati eyin odo, bawo ni e se n se ati dahun si awon oro ati ilana Olorun? Nje o ko ti se Kristi tabi dale re nipase awon oro re, irisi re, awon egbe to n ko, igbesi aye re, iwa re, ati bebe lo, loni? Se atunse awon ona re loni saaju ki o to pe ju.

(2) **Won kun fun iborisa (Esekiel 20:28)**

Won kopa ninu gbogbo oniruru ijosin ati irubo si oniruru olorun - olorun ikore, olorun ibimo, olorun ojo, ati bee bee lo. Gbogbo eleyi bere leyin ti a mu won wa si ile ileri tan. O ya ni lenu bi won ti se tete gbagbe awon ikilo Oluwa (Deu. 8: 10-20; 12: 1-14). Irufe ise ati iwa bayi ni a n ri ninu opo ti o je ara Kristi loni. Won di ohun miiran nigbati aseyori ba de. Won ri ise tuntun, ile titun, igbega, ati bebe lo, leyin naa won di apehinda, awon kan a tile ko Olorun si le patapata. Ki ni orisa ti o sese segbeyawo pelu re, ti n ba ipo Olorun dije ninu igbesi aye re? Ye ara re wo ki o si fi ijanu si.

**II. IFE LATI DABI AWON KEFERI (Ezekiel 20: 29-32)**

**(a) Olorun ko ri idi fun Israeli lati ba a soro**

Lopo igba, Olorun soro nipa aigboran awon omo Israeli ati ibinu re ti o mu ki o ma se mura tan lati faye sile fun ibara eni soro po. Ni pato:

(1) **Olorun beere ibi ti won n lo fun ijosin (Esekiel 20: 29)**

Ibe ni won n pe ni *Bamah*, to tumo si ibi giga. Ibi orisa ni. A gbodo sora lati lo si ibi gbogbo ati ibikibi ni oruko pe a nlo fun eto adura tabi awon ikorajopo temi kan. Opo awon ibi adura je ojubo orisa gangan ti a gbekale ni irisi ile ijosin tabi awon oke adura, nitori awon ise ti o lodi si irisi Kristi. Opo irufe awon ibi bayi ni okun fun adalu esin taarata tabi lona ero. Olorun ti kilo fun awon omo re tele pe awon ko le lo sibi eyikeyi fun ijosin ati ore ebo, ayafi ibi ti o yan ti o si daruko fun won (Deu. 12: 5-7). Ko bi a ti nduro labe Olusaguntan oniwa-bi-Olorun ati Kristi, ki o losi ibi ti o ba ran o lo, ki o se ohun ti o ba so fun o pe ki o se, eyi ti o wa ni ibamu pelu ifihan otito oro Olorun ti o pe.

(2) **Ibaje ati agbere/pansaga ninu ijo Israeli (Es. 20: 30-31)**

(3) **Won tun fesun kan awon baba (awon obi) pe won kopa ninu awon ise/ise to n ba orile-ede ati ijo ti Olorun yan je.**

Awon ohun ti won se niwonyi:

* won fi awon ebun fun awon orisa
* won je ki awon omo won la ina koja gege bi awon orilede keferi ti n se. Iyen je irubo si olorun awon ara Amoni ti won n pe ni Moloku/Moleki/Milikomu/Malikamu (Amosi 5: 26; Lef. 18: 21; 20: 2-5; 1 Awon Oba 11: 5, 33; Sefu. 1: 5). Olorun yii ni a n pe ni Kemosi laarin awon ara Moabu (Awon Oba 11: 7; Numu. 21:

29). Lati Lev. 18: 21; 20: 2-5) a le ri i ni kedere pe eyi je okan lara awon ikilo Olorun fun won lori ise iborisa ati iwa buburu yii.

* won kopa ninu owo nabi sise ati pansaga, paapa, lona ti esin; sise agbere esin.
Awon alagbere esin ye ki o sora ni alo yi.

**(b) Ife lati dabi awon keferi (Ezekiel 20: 32)**

Israeli ni ainiye ibasepo pelu awon orile-ede meloo kan ti won ka si orile-ede Keferi pelu awon asa aiwabi-olorun ati iborisa won. Lati Egipti nibiti won ti fere lo edegbeta odun si awon orile-ede ti o yi won ka ni ibi ibugbe titun won, ile Kenaani, won sii ju si awon ona ise ati igbesi aye awon keferi, ti a ti soro le lori saju, fun apere, bi asa awon ara Amoni ati Moabu, laiso awon miiran. Ibasepo pelu ati ife lati dabi eyikeyi ninu awon orile-ede wonyi ni a ti kilo lodi si lati odo Olorun won (Deu. 7: 1-6, 25-26; 12: 28-32). Sugbon o se ni laanu pe won npongbe lati dabi awon eniyan ati orile-ede ti won dara, ti won si tobi ju lo.

E je ki a se akiyesi wipe o je ife ninu okan won, ti won n tojusi ni ikoko, lati se ni kikun nigbati akoko ba to. Olorun ko fowosi nitorinaa ni o se so wipe erogba ti ko le wa si imuse ni. Olorun kede re gege bi ife-okan ti ko ni ri imole ojo ni. Kilode? O je Olorun owu ati onifee ti ko ni je ki won ta awon eniyan re fun igi ati okuta gege bi olorun. Ife wo ni o wa ni ikoko okan re, ti o nse asaro le lori lodi si Kristi ati ijoba re? Se ko si awon eto ti o ni ni ikoko okan re ti ko si ni ibamu pelu ife Olorun fun igbesi aye re? Olorun so pe oun o ni joko ma wo ki won wa si imuse nitori Ife re si o. Nitorinaa, jowo ara re ati Ife re fun un ati fun ife re loni.

Mase fe lati dabi awon alaigbagbo boya nitori o lero pe won nse daradara nigba ti iwo ti o so pe o ni Kristi n jiya. Mase se ilara awon ona ti awon alaiwa-bi-Olorun; mase fe ona igbesi aye won. Sayewo iriri onisaamu ati oro re ti o so pari ninu Orin Dafidi 73: 1-28. Je ki Kristi ati awon oro re to fun o, ko si igbesi aye tabi anfani to dara ju lo laisi ninu Jesu.

**IBEERE**

1. Ki ni idi ti awon iranse Olorun ko fi gbodo siwo ikilo fun ijo?
2. Se aseyori ye ki o je ki enikan yipada ninu ifaramo re si Olorun? Salaye.
3. Ki ni oruko ibi ti awon omo Israeli yoo ti lo josin? So itumo oruko naa fun wa.
4. Daruko awon orisa ti won n rubo si nigbati won ba n mu awon omode la ina koja.
5. Ki ni eto ikoko ninu okan awon omo Israeli ati Kini idahun Olorun si eyi?

**OCTOBER 4, 2026** **EKO 40**

# A O MU ISRAELI PADA BO SIPO

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 20: 33-44*

***ESE AKOSORI:-*** *"Emi o gba nyin pelu orun didun nyin, nigbati mo mu nyin jade kuro laarin awon enia, ti mo si ko nyin jo lati ile gbogbo nibiti a gbe ti tu nyin ka si; a o si ya mi si mimo ninu nyin*

*niwaju awon keferi," (Esekieli 20:41).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| **MON** | 28/9/2026 | O je Olorun alanu | Deu. 4: 29-31 |
| **TUE** | 29/9/2026 | Ibi ti a yan | Kronika keji 7: 12-16 |
| **WED** | 30/9/2026 | Sioni ti a mupadabosipo | Orin Dafidi 126:1-6 |
| **THUR** | 1/10/2026 | Awon Olujosin tooto | Johanu 4: 21-24 |
| **FRI** | 2/10/2026 | Ebo tooto | Romu 12: 1-3 |
| **SAT** | 3/10/2026 | A o we Israeli mo | Esekieli 20: 33-38 |
| **SUN** | 4/10/2026 | Gbogbo Israeli ni yo sin mi | Esekieli 20: 39-44 |

## ORO AKOSO

Ife ati aanu Olorun ti o n tesiwaju ko ni je ki o fi awon tire sile titi lae. Onisaamu naa so pe, "Nitori ibinu re wa fun iseju kan pere, sugbon oju rere re wa laaye;..." (Orin Dafidi 30.5, NIV). Olorun binu paapaa si awon omo ati orile-ede ayanfe re, o je apakan ti ife itara re ti a fihan. Sibesibe, ibinu re ko wa titi aye; ife, aanu ati ojurere re ni o wa titi lae ninu aye ti a wa yii. Ileri imupadabosipo fun Israeli olote naa wa laika aidunnu ati ijakule ti Olorun ti fojuwina re lati odo won, gbogbo eleyi ri be nitori ife ati aanu re. Gbogbo awon omo Olorun gbodo ko lati ma se fi owo yepere mu ife ati aanu Olorun, nitori wipe akoko n bo ti ibugbe ikeyin ti gbogbo awon elese ati awon eniyan ika yoo wa ninu adagun ti n jo pelu ina ati sulfuru (Ifihan 14: 10-11; 21: 8).

## EKO

### I. OLORUN SELERI LATI KO ISRAELI JO KURO NI AWON ORILE-EDE (Ezekieli 20: 33-38)

Isote Israeli ti mu ki won so ominira won nu. Won ti fonka si oniruru orile-ede gege bi eru, okan lara awon irufe orilede yi ni Babiloni nibi ti won wa. Awon miran na wa ni awon orile-ede keferi miiran paapaa. Nihin-in, Olorun seleri lati mu won jade kuro ninu oniruru igbekun ti won ti wa.

Oun yoo se eyi ni awon ona wonyi:

**(a) Olorun yoo fi owo lile joba lori awon eniyan re (Esekieli 20: 33)**

Niwon bi won ti je olorun-lile, agberaga, alagidi ati alaigboran, adari ti o ye won ni adari ti o ni opa irin lati mu won wa sona to to, niwon bi won ti ko lati gbo nipa opolopo ebe ati iparowa ti o ti lo siwaju. Won nilo ki a dari won pelu owo ti o le. Won gbodo ni iriri opa ibawi Olorun ti yo mu atunse ba won lati mu won pada si ona toto. Ko si ohun ti o ye ki o je iyalenu ninu eyi. Gege bi oluso agutan ti Olorun je laarin won, a ma a se ise idari ati itosona re nipase lilo ogo ati opa gege bi onisaamu ti je ki o ye wa (Saamu 23:4).

**(b) Olorun yoo mu awon eniyan re jade lati orile-ede ti won ti fon ka, yoo si tun ko won jo (Ezekieli 20:34-36)** - yoo se eyi lati fi han won pe Olorun ni oun, oun ni Olodumare, ko si ohun ti ko le se. Owo Olorun ko kuru lati gbani, iwa ati ise wa li o n ka Olorun lowo ko (Isa.50: 2; 59: 1, 2). Olorun tun seleri lati sedajo won leyin ti o ba mu won jade, gege bi o ti se si awon baba won (Ezekieli 20: 35, 36). Idajo Olorun nipa awon eniyan re fi iwa ododo re han ani gege bi alaanu ati oniyonu bi o ti ri. Pe Olorun saanu ko fun o ni ominira lati ma a tesiwaju ninu ese, bi bee ko, o le kabamo abajade igbesi aye ibaje, aigboran ati aibikita (Rom. 6: 1-2).

**(d) Olorun yoo ye awon eniyan re wo, yoo si we awon olote mo kuro ninu awon eniyan re**

**(Ezekieli 20: 37-38)**

Olorun ti mura lati mu awon eniyan re pada si ile won, ile ileri. Sibesibe, kii se gbogbo won ni yoo je ki won wole sile na. Leyin ti O ba mu won jade ti won si ko won jo lati gbogbo orile-ede tan, ki won to wo ile na, yoo se ayewo awon eniyan na. Yoo mu awon olote/alaigboran naa kuro lara won, ki yoo si je ki won wo ile Israeli.

O je ikorita ipinniya, nibiti a ti n ya ewure kuro lodo awon agutan, ti a si ti nya epo kuro lara alikama (Matt. 13: 24-43; 25: 31-46). Ki ni yoo je ipin re ni ojo ipinya atorunwa yen?

Awon iwe-mimo soro nipa irufe awon ti a ko ni gba laaye sinu ogo ayeraye ni ojo ikehin, laibikita awon ipo won, awon ise tabi awon ore ninu ile ijosin. E je ki gbogbo wa ka awon ese Bibeli won yi lapapo, ki a si so iru awon ti yoo di eni atisode nikehin: Gal. 5: 19-21; Ef. 5: 3-7; Ifi. 21: 8). Oore-ofe si tun wa lati gbe awon igbese wonyi ni bayi saaju ki o to pe ju: 2Cor. 6: 17-18. Gbigbe awon igbese yen mu o wa sinu majemu ayeraye - ti alaafia, ayo, ati iye ainipekun pelu Olorun, gege bi o ti fe lati mu awon eniyan re wa sinu majemu re (Esek. 20: 37).

**II. IMUPADABOSIPO ATI GBIGBA AWON ENIYAN OLORUN (Ezekieli 20: 39-44)**

**(a) Olorun Mimo, oke mimo, awon nkan mimo (Esekieli 20: 39-42)**

E je ka ranti pe okan lara awon ohun ti Olorun fesun kan orile-ede Israeli fun ni lilo josin lori oke Bamah (oke orisa, ojubo) nibiti won si ti n rubo irira ti won si nmu ore elegbin wa (Esekieli 20: 29-31). Si eyi sibe, Olorun si tun n ba won wi ni lilo eeda oro fun won ni siso pe bi o ba wu won ki won tesiwaju pelu lilo irufe ibi be ati niru irubo bee (Esekieli 20: 39). Eda Bibeli kan yo ran wa lowo lati loye re daadaa nigba ti o so pe, "'Ni ti eyin, ile Israeli, eyi ni ohun ti Oluwa Olodumare wi: Ki olukuluku yin lo ma a sin orisa re, sugbon leyin eyi, eyin yoo gbo temi, eyin ko si ni i ba oruko mimo mi je pelu ore ati awon orisa yin mo (Eseki[1]li 20:39). Bayi, fun awon ti yoo yipada si odo re o fi okan re han ati iru ijosin ti o je itewogba niwaju re:

1. **O je Ijosin ti ohun ti a n sin je Olorun tooto ati mimo kan soso (Esekieli 20: 40, 41)**

Won ko gbodo sin awon olorun kekeke tabi orisa, Eni ti won gbodo sin ni EMI NI gegebi O ti fi ara re han won. pelu awon oro bi ' OLUWA OLORUN, 'Emi ni Oluwa' (Esekieli 20: 40, 42, 44). Lati tun fi idi abuda jije mimo re mule fun won, ti o mu un yato si awon Olorun miiran, o so pe, "... Emi yoo fi ara mi han ni mimo laarin yin ni oju awon orile-ede." (Esekieli 20.41). Mase tele tabi josin Olorun alaimo.

2. **Ijosin tooto gbodo wa lori oke mimo Olorun (Esekieli 20: 40)**

Nibo ni o n lo fun ijosin ati awon eto emi? Se won je ibi ti Olorun wa ninu iwa mimo? Oke mimo nihin-in n soro nipa ibikibi ti awon eniyan Olorun pejo fun ijosin Olorun mimo ati nibiti ijemimo je igbesi aye ninu oro ati ise won. Je ki awon omo akeko ka ki won si fesi si ese Bibeli yii: Johannu 4: 21-24.

3. **Olorun n beere fun awon ore, ebun ati irubo mimo ati asayan (Esekieli 20: 40)**

Awon irufe ififunni meteta ti ati so loke wonyi ye ni titenumo loni, sugbon, o gbodo je ore ti a mu wa lati awon orisun mimo (awon orisun tooto ati rere ti o je ona ti owo n gba wole), eyi ti a si mu wa pelu okan tooto ninu iwa mimo.

4. **Igbesi aye ti o n te Oluwa lorun (Esekieli 20: 41)**

Olorun fe ki won je irubo aladun yen funra won. Igbesi aye olujosin gbodo je itewogba ati itelorun si Olorun. O gbodo je oorun didun nitooto, iyo si awon ti o wa ni ayika re (Matt. 5: 13).

A gbodo ranti nigbagbogbo lati beere lowo ara wa irufe eniyan ti a je bi a se n farahan niwaju Eleda wa (Johannu 4: 21-24). Leekan si, e je ki a sayewo ebo ati irubo ti o tobi julo ti a le fi fun Olorun ni Rom. 12: 1-3.

**(b) Ileri imupadabosipo je eyiti o daniloju (Esekieli 20: 42-44)**

Lati fihan pe ileri na je eyi ti o daju, a o se akiyesi awon nkan ti a ko si sale wonyii:

1. Israeli yoo jewo Olorun nigbati o ba mu ileri ti mimu won pada si ile ileri se. Olorun n se gbogbo ohun to n se fun wa ki a le jewo re gege bi Olorun ati Oluwa wa.
2. Israeli kii yoo ni inu didun fun igbesi aye ese ati isote/aigboran re ti o ti gbe koja leyin imupadabosipo. Ese ko ni ere kankan yato si egan, edun okan, adanu, ati iku. Jawo ninu ese ati alaigboran/ jije olote.
3. Ibalo Olorun pelu awon eniyan re ni ile ileri yoo je nipa oruko mimo re, ki i si i se nipa igbesi aye ati ihuwasi awon omo Israeli. E wo baba olufe ati alaanu ti Olorun je! Iwo na le je iru anfani wonyi loni nigbati o ba yipada si Kristi.

Imupadabosipo see se fun gbogbo awon apeehinda loni. Omo oninaakunaa gbadun oore-ofe yen.

O ba baba re se ilaja, a si mu un pada bo sipo ajose to danmoran ati ti o ni eso pelu baba re (Luuku 15: 11-32). Akoko re ni yi lati gbadun iru oore-ofe bi eleyi bi o se ngbe igbese ironupiwada kuro ninu awon ese ati awon isote/aigboran re loni. Kristi ti na owo re nisisiyi, lati gba o ati lati se aye re lewa.

**IBEERE**

1. Ka ese akosori eko toni.
2, Kini idi ti Olorun yoo fi lo owo lile lati dari Israeli ni akoko yii?
3. Awon wo ni Olorun so pe oun ma a mu kuro lara awon eeyan oun, ti Oun ko si ni je ki won wo Israeli? N je eyi kii se iwa ika lati odo Olorun? Salaye.
4. Nibo ni oke mimo Olorun wa ki a le lo sibe lati josin?
5. Ki ni awon nkan ti Olorun beere lowo awon omo Israeli bi won se wa lati josin fun? Nje Olorun nilo irufe awon nkan be lati odo wa loni tabi ko nilo won? Salaye.

**OCTOBER 11, 2026 EKO 41**

# IDAJO NIPA INA ATI IDA

***BIBELI KIKA:-*** *Esekiel 20: 45-49; 21: 1-7*

***ESE AKOSORI:-*** *“Nitoripe Olorun wa, ina ti ijonirun ni.” (Heberu 12:29).*
*“Nitori oro Olorun ye, o si li agbara, o si mu ju idakida oloju meji lo, o si ngunni ani titi de pipin okan ati emi niya, ati orike ati ora inu egungun, on si ni olumo ero inu ati ete okan.” (Heberu 4: 12)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 5/10/2026 | Sodomu ati Gomorra | Gen. 19:12-25 |
| TUE | 6/10/2026 | Ina fun ina | Lefitiku 10:1-7 |
| WED | 7/10/2026 | Tabera | Numeri 11:1-3 |

| | | | |
|---|---|---|---|
| **THUR** | 8/10/2026 | A fi ida pa won run | Eksodu 32:25-28 |
| **FRI** | 9/10/2026 | Ida fun ese | Lefitiku 26:23-25 |
| **SAT** | 10/10/2026 | Ina Idajo | Esekieli 20:45-49 |
| **SUN** | 11/10/2026 | Ida ipinya | Esekieli 21:1-7 |

**ORO AKOSO**

O ye ki a ni oye pe oniruru awon ise iranse ni a fi fun woli Esekieli nipa orile-ede Israeli ati opo awon orile-ede Keferi. Leekan si i, Olorun so fun Esekieli pe ko so ero Re nipa Juda ati Jerusalemu nitori ese won. Ese, bi o ti wu ki o kere to, ki n bi awon iriri ti o dara bi ko se iku (Jakobu 1: 13-15). A ni ise nla nisinsin yi lati kilo fun awon eniyan buburu/awon elese, nitori nigba miiran ijiya won le ma mo ni awon nikan, lopo igba awon olododo na a ma faragba ninu re, gege bi a o ti rii ninu eko toni.

**EKO**

I. **ETO OLORUN LATI FI INA JE AWON ENIYAN RE NIYA (Esekieli 20: 45-49)**

Olorun ni ki woli naa doju ko gusu ki o si so asotele naa ti oun yoo fi fun un. Asotele ibinu ni. E je ka sora fun ibinu Olorun bi a se n gbe igbesi aye wa ninu irin ajo igbesi aye.

**(a) Asotele si papa Gusu (Esekieli 20: 45-46).**

Papa gusu ni papa gbigbe Juda ati Jerusalemu. Juda ati Jerusalemu wa ni gusu lati Babiloni, nibi ti Esekieli ti wa nisinsinyi, nitori naa, won ni ki o gbe oju re siha gusu (Esekieli 20:46), lati ba won soro pe Olorun ti gbe oju re lodi si won, inu Re ko si dun si won. O si pinnu lati pa won run. Oju Olorun le wa fun ise rere enikan, oju Re si le lodi si elomiran. Ti oju Re ba je fun ise rere enikan, o tumo si pe irufe eni be ti ri ojurere ti Oluwa. Lona miran ewe, ti oju Oluwa ba lodi si enikan, o tumosi wipe eni be wa lowo ibinu ati ijiya Olorun. Awon ise wa, a ma fa oju-rere tabi ibinu ati ijiya Olorun. Sayewo eyi ti iwa ati ise re nfa, boya ojurere tabi ijiya, yoo se iranlowo lati je ki o mo iwa re si Olorun ati awon ilana Re.

Ojogbon oluse alaye Bibeli ti o n je Matthew Henry, fun wa ni ijinle oye nipa idi ti a fi lo papa/igbo fun awon eniyan Oluwa bayi: Juda ati Jerusalemu ni a n pe ni papa/igbo, ki i se nitori pe won ti kun fun eniyan nikan, gege bi igi, sugbon nitori pe won ti wa lai ni eso, nitori pe igi eleso ki i hu ninu igbo, igbo/papa si ni idakeji oko eleso, Isaiah 32:15. Awon ti o ye ki o je ogba Oluwa, ati ogba ajara re, ti da bi igbo, ti gbogbo re kun fun egun ati egun ati awon ti o ri bee, ti ko mu eso ododo jade, oro Olorun so asotele lodi si won. N je o si tun n so eso fun ijoba Olorun, ati pe, iru eso wo ni o n so?

**(b) Ina ti ko si enikan ti o le pa (Esekieli 20: 47-49)**

Ina yii kii yoo je ina ti eniyan da. Ki se ina lati ago awon ota won. Ko tile ni je ina lati odo Satani. O maa je ina ti Olorun fun ra re da. E je ki a ranti akoko ti Olorun fe fi iya je Dafidi nitori ese re. A ni ki o yan boya lati jiya iyan osu meje, tabi ki won ma sa ni waju awon ota won fun osu meta, tabi ki won jiya ajakale arun ojo meta. Ko si okan ninu awon ohun meta ti a gbe siwaju re yi ti o rorun lati teri si. Nigbati o pa da so pe ki oun kuku subu si owo Olorun san ju ki oun o subu si owo awon ota gan ko rorun. Ijiya ti o mu yi nikan je ki Israeli padanu awon okunrin ti o ni agbara ti iye won je egberun lona aadorin (2 Sam. 24: 10-17). Haa! Yi o ti buru to lati subu si owo Olorun to n binu.

A se akiyesi pataki nipa iru awon eroja/awon nkan ti a o fi ina sun: igi tutu ati igi gbigbe, gbogbo awon oju lati gusu si ariwa. O tumo si pe ina naa ko ni da enikeni si, yala eniyan nla tabi kekere, otosi tabi oloro, eniti o sanra tabi eniti ko lara, eni ti o mooko-mooka tabi alaimooka, alawo funfun tabi alawo dudu, ati bee bee lo. Awon adari Ijo, awon oloye ninu Ijo, ni a ki yo dasi lowo ina idajo na, ti won ba jebi. Nibo ni awon elese yoo sa lo ni ojo idajo nitori ko ni si aye fun ona abayo ni iru akoko bi eleyi. Ko si awon idi tabi awon awawi ti o le yo enikeni ti o kuna lati ronupiwada kuro ninu ese re ki o si gba Jesu nitooto, ki o si ma tele Kristi gegebi Oluwa ati Olugbala re, kuro ninu adagun ina nla naa (Ifihan 21: 8).

Eniyan ko le pa ina naa, nitori kii se eniyan ni o da Ina na ni ibere. Eniti o da ina nikan ni o le pa a, idi gan-an ni yi ti ko fi si enikan ti o le sa fun ina na (Esekieli 20: 48). O yani lenu pe awon omo Israeli so pe

awon ko loye ohun ti won n so, won si pe e ni owe (Esekieli 20: 49). O dabi ifinisefe. Fifi ohun to n wa lati odo Olorun si awon eniyan re se fe. Iwa yii si wa ninu awon ijo wa loni. Awon olujosin miran ma n fi owo awada mu oro Olorun. Won a fi owo aaibikita, ko kan mi, ati aini ibowo mu oro Olorun. Ronupiwada ti o ba je okan ninu awon ti o ni iru awon iwa won yi.

**II. IDA LATI JERUN (Esekieli 21: 1-7)**

**(a) Sotele lodi si ile ati ibi mimo (Ez. 21: 1-2)**

A tun so fun Woli Esekieli ki o so asotele lodi si ile Israeli ati lodi si ibi mimo, awon ago ijosin mimo. Ibaje awon ibi mimo ti ijosin Olorun tooto ati ile naa lapapo nipase awon asa irira ati isote mu ki Olorun mura tan lati mu iparun wa sori ibi mimo re ati sori awon eniyan re. Idibaje wo ni o mu wa si ile Olorun ati si ori pepe iwasu gege bi oloye ati osise ninu ijo? Won le mu ijiya atorunwa, e je ki a sora.

**(b) Ida bi ona ijiya (Esekieli 21: 3)**

Nigba ti Olorun n soro nipa lilo ina gege bi ona ijiya ti won si so pe awon ko loye ohun to tumo si, o tun gbe ohun elo ijiya miiran jade bayi, o si je ida. Nigba ti Mose so kale lati ori oke ti o ti wa pelu Olorun fun ogoji osan ati ogoji oru, ti o si ri awon omo Israeli ti won ti ba ara won je pelu iborisa, o pase fun awon ti won faramo Oluwa lati fa ida won jade ki won si lo sinu ago. awon arakunrin won, ki won si pa won. L'ojo yen nikan, egberun meta okan ni won fi ida pa (Eksodu 32: 25-28). Ida ki se ohun elo ere; ohun elo idajo ni. Ijiya yii to ni i se pelu lilo ida ni Olorun funra re n so nigba to n kilo fun won saaju akoko. E je ki a ka Lefitiku 26: 23-25. E je ki a yago fun idajo Olorun ni gbogbo ona, ohunkohun ti iba na wa.

**(d) Awon olododo ati awon eniyan buburu ni a o fi ida je niya (Esekieli 21: 3-5)**

Gbolohun kan wa ninu ede Yoruba ti o lo bayi, “Bi elese ba n jiya, olododo a ma pin ninu re.” Eyi je otito nibiyi. Olorun n so pe nigba ti Oun ba mu ida wa sori ile ati ibi mimo, yoo kan gbogbo eniyan, yo kan awon olododo pelu. Eyi gbe ibeere dide ninu okan enikeni ti o ba n ka tabi ti o gbo eyi: kinni idi ti Olorun, Olorun mimo ati olododo yoo fi fiya je awon olododo papo pelu awon eniyan buburu? A gbodo loye re pe ni Israeli igbaani, awujo ni n saba maa n dahun fun aïsedede awon enikokan ti o je omo ilu. Ilana ebi apapo yii ni a rii ninu awon ese bibeli bi Joshua 7: 1-26, nibiti gbogbo orile-ede ti jiya awon abajade fun ese enikan, Akani. Nitorina, a mo pe idajo Olorun je eyi ti o dojuko orile-ede lapapo, dipo awon olododo tabi eniyan buburu kookan. Awon olododo ni Israeli ti kuna lati ni ipa ti yo je idena fun ise ati iwa awon eniyan buburu, eleyi si ti mu ki iwa ibaje o kun orile-ede naa. Nipa ki ko awon olododo po ninu idajo, Olorun n fi gbogbo orile-ede naa lapapo sa be ebi ese na. O se pataki lati se akiyesi pe idajo lapapo yii ko tumosi wipe eni kookan ko ni je iya ese re lotooto. Bibeli ko ni pe olukuluku eniyan ni yoo gba idajo nipa yala ohun ti won se tabi nipa igbeaye igbagbo won (Esekieli 18:1-32, Matiu 25:31-46). Awon olododo ni Israeli yoo si je olododo loju Olorun, sugbon won yoo jiya abajade gigbe ninu awujo oniwà ibaje. Leekan si, e je ki a kiyesi pe jije awon olododo niya pelu awon eniyan buburu kii se nitoripe Olorun je ika. Sugbon, o n safihan agbekale inu Bibeli nipa ojuse ajumose, eyi ti ma n mu ijiya wa sori gbogbo eniyan ti o wa ni adugbo kan nigbati enikan ba dese. Wo awon iwa ati ise re, won le je okunfa iya awon eniyan alailese.

**(e) A so fun Woli pe ki o kerora fun ijiya ti o sun mole (Esekieli 21:6-7)**

Ki awon eniyan naa le nimolara iwuwo ijiya ti yoo de lai pe, Olorun so fun Wolii Ezekiel pe ki o kerora bi eniti o wa ninu irora gbigbona janjan nigbati o ba n jise na. O ni lati:

* kerora pelu okan ti o baje
* kerora pelu ibinuje kikorò

Awon ojise Olorun gbodo ko bi a se n ro awon eniyan lati yipada si Olorun pelu imura ti o dara ati okan ti o wuwo. Agbodo se awon ise iranse kan bi eniti o wa labe irokeke ida funra re ati eniti o tun se abojuto awon eniyan, ti o mo bi ijiya Olorun se le to (2Kor. 5: 11; Juda 22-23).

Gege bi alaaye ati alaanu ti Olorun je, o tun je Olorun elerujeje (Saamu 47: 2). O le sabewo pelu ina ati ida ti ko ni da enikeni si. Bi a se n gbadun aanu re, e je ki a sa fun ese, aìgboràn ati iso te eyikeyi. E je ki a teriba fun un ati ife re ninu ohun gbogbo laida ibikan si.

**IBEERE**

1. Ka awon ese akosori ti eko toni
2. Daruko awon eroja/awon nkan ti ina idajo Olorun yoo je. Bawo ni a se le se alaye eyi loni?
3. Daruko awon ti a o da si nigba ti ina ma ba bo.
4. Ni ibamu pelu eko wa, tani Olorun yoo fi ida je niya?
5. Bawo lo se ye k'awon ojise Olorun ma se agbekale iwasu won lonii?

**OCTOBER 18, 2026** **EKO 42**

# OLORUN TI O N BINU PELU IDA PIPON ATI DIDAN

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 21: 8-32*

***ESE AKOSORI:-*** *"Omo enia, sotele, si wipe, Bayi li Oluwa wi; Wipe, Ida, ida ti a pon, ti a si dan pelu: A pon o lati pa enia pupo; a dan a lati ma ko mana: awa o ha ma se ariya? Ogo omo mi, o gan gbogbo igi." (Esekieli 21:9-10).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| | Ojo | Deeti Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 12/10/2026 | Ibinu Olorun buru jai | Numeri 16: 23-36 |
| TUE | 13/10/2026 | Ese a ma a mu Olorun binu | Numeri 25: 1-5 |
| WED | 14/10/2026 | Idajo oju ese | Numeri 25: 6-13 |
| THUR | 15/10/2026 | Fi enu ko omo na lenu | Orin Dafidi 2:10-12 |
| FRI | 16/10/2026 | Ko si ibi isago si niwaju Olorun | Orin Daf 139.7-12 |
| SAT | 17/10/2026 | Ida apanirun | Esekieli 21: 8-17 |
| SUN | 18/10/2026 | A se Idajo re nitori ifini sesin | Esekieli 21:18-32 |

**ORO AKOSO**

Bi eni kookan tabi orile-ede ti n ba a lo ninu ese, bee naa ni idajo Olorun se n be won wo. Olorun ti ni lati pinnu, gege bi a ti ri i ninu awon eko ti o saaju, lati ma se dake jeje titi yoo fi mu idajo ododo wa si ile Israeli ati laarin awon eniyan re. O han gbangba pe Olorun ko ni dake, nigba ti awon omo re ba sako lo, oun a maa na won, Oun si maa n ba won wi nipase orisirisi ati oniruru awon ohun elo. O ti yan lati tesiwaju ijiya pelu ida, a ti rii pe eyi bere lati inu eko isaaju. Nigba ti a fe soro nipa ida ti o wa ninu eko isaaju a se afihan re pe o wa ninu apofelefele ati pe Olorun yoo mu u jade kuro ninu apofelefele lati mu idajo re se. Bi o ti wu ki o ri, ni fifi ida idajo sile ninu eko toni, kii se ida ti a fi pamo sinu ako lati mu jaade, bi ko se ida ti a ti mura sile fun ise ibi - ki a so lona miran ba yi wi pe, ida ti a ti mura sile fun ogun, ida ti o ti mura sile fun idajo. Eyi n so fun wa pe suuru Olorun ti n din ku, ti fifarada a fun agidi ati isote won si ti n di ohun itiju fun un. Mase ro pe Olorun yo ma wo o ki o si tesiwaju ninu aigboran re titi aye. Ronupiwada nisinsinyi.

**EKO**

**I. IDA TI ENIKENI KO LE SA MO**

**LOWO (Esek. 21:8-17)**

**(a) Ida pipon ati didan (Esek. 21:8-11).**

A tun so fun Wolii naa ki o kede ifihan ida. Lati se afihan iwulo re ati bi o se ni eru to, o menuba leemeji, “ida”, “ida”. Iyen kii se ere omode. Mase sere pelu ikilo atorunwa, o le ja si iku. Apejuwe ida naa pe fun akiyesi. O je ida ti a pon ti o si n dan. Eda Bibeli kan so o lona yii, “o mu bi abe, o si n dan.” O je eru ati ewu lati sise ni ayika iru ohun elo idajo. Se ki n se pe o n fi oro Olorun sere laisi ibowo ati laibikita, oro ti o mu ju idakida oloju meji lo, bii eni ti o nsire pelu ohun isere (Heb. 4: 12)? O lewu lati se be, sora.

Ida naa wa lori ise lati pa, nitorina o je eyi ti a ti pon. Didan re ni lati mu ki awon eniyan wo ati ki o le seda iberu pataki ti o so pataki ti idajo ti n bo.

Ida ninu oran yii kii se si awon alaigbagbo ninu Yahwe, kii se lodi si awon orile-ede aborisa ti aye, awon orile-ede keferi. Ida naa wa fun awon olufe ati awon eniyan Olorun ti won da majemu, awon omo Israeli. Wipe iwo je ayanfe omo re ko da o si kuro ninu ibawi re nigbati o ba se. O n ba awon ti o fee wi (Heb. 12:5-11). O tun dara julo ni ipele ibawi ati ijiya saaju idajo gangan. O je lati dekun iwakiwa ati aibikita saaju idajo ti ko le se alaimawaye. Nihin-in, o je ida idajo ti a pon ti o si n dan lowo oludajo naa. Iborisa, agbere isin, adalu esin, orun lile, ati isote je idi ti a fi pon ida na, ti o si fi n dan fun pipa. Kini yoo mu ibinu ati idajo Olorun wa sori iwo ati idile re lonii?O ko le se alaimo won, nitorinaa, sayewo aye re ki osi yipada.

**(b) A so fun Woli awon nkan to ye ki o se nigba ti o ba n jise re (Esi. 21:12-14 )**

A so fun wolii Esekieli awon ohun ti yo se lati le pe akiyesi awon eniyan ti a ran an si.

A so fun wipe:

**(1) Ki o sunkun, ki o si pohunrere ekun (Es. 21:12a)** -

O ni lati sokun nitori idajo naa yoo buru. Bakan naa, bi o ba ti n sunkun ti o si n sofo, eleyi le mu ki won yiju si i lati gboro na, ki won si fi owo pataki mu un. Igbe re le gba ati pe akiyesi won si oro na ati Eni ti o ran nise naa. Ti o ba pe fun ekun, awon iranse Olorun ni lati se be lati mu oro ati ero okan Olorun wa fun awon eniyan, fun ironupiwada ati atunbi won. Melo ninu awon iranse Olorun lo mu ise iranse oro Olorun ni pataki loni debi ti won a sunkun fun awon ti ko ronupiwada ati awon alaigboran/olote ninu ijo, ki a ma ti le ti soro nipa awon ti ode agbo? Woli Jeremiah ni gbogbo eeyan mo si woli elekun. Ko fi owo yepere mu ise iranse oro na, ko tile ma wa iyin eniyan tabi tabi ki won patewo fun, o setan pelu iduro to daju lati pin oro Olorun pelu omije ki o le so eso ti Olorun n fe. Nibiyi, Olorun so fun woli Joeli bayi, “Je ki awon alufa, awon iranse Oluwa, sokun laarin iloro ati pepe, si je ki won so pe, Da awon eniyan re si, Oluwa, ma si se fi ini re fun egan, ti awon keferi yio fi joba lori won: eese ti won o fi wi ninu awon enia pe, Olorun won ha da? (Joeli 2:17).

**(2) Lu itan re tabi lu aya re (Es. 21: 12)** - E wo iru iriri buburu ti enikan yo ni nigbati Oluwa ba fi ida pipon ati didan re gun iru eni be! Lati sapere eyi, a so fun woli naa ki o jise na pelu lilu itan tabi aya. Eyi yoo mu ki won se akiyesi re, yoo si fi bi oro na ti se wiwo to ati imuna doko oro na ni jijise re han. Bayi ni awon iranse Olorun ni lati jiya ti a ko le fenu so nitori ese awon eniyan Olorun. Jeremiah ni a so fun pe ki o gbe ajaga bo orun lati so okan Olorun fawon eeyan naa (Jer. 27:1-22). A so fun Isaiah ki o maa rin ni ihoho fun odun meta lati fi ibinu Olorun han ati ijiya to nrodede lori awon orile-ede keferi (Isa. 20:1-6). Awon iranse Olorun gbodo mura okan won sile lati se ohun ti ko rorun, sugbon ti o wa ni ibamu pelu Bibeli, lati ri i daju pe okan Olorun di mimo fun awon eniyan Olorun.

**(3) Patewo re titaratitara, ti n sapejuwe lilu owo re (Es. 21:14)** - ipatewo wolii nihin-in kii se lati ye awon omo Israeli olote si tabi lati yin Olorun. O je lati pe akiyesi won si ise iranse ti o n lo lowo. Olorun maa n lo ona eyikeyi ati gbogbo ona lati pe akiyesi awon eeyan re ki oro re le jade daradara. Fun Mose, igbo ti o njo, ninu eyiti leyin ti o ti ri i, o nife si i lati wo bi ere idaraya tabi wo bi fiimu, ni Olorun fi pe akiyesi re (Eks. 3: 1-6). Ki lo de ti o di eti re ti

o si moomo di oju re si ipe emi Olorun nipase awon ona orisirisi fun itonisona re? Se akiyesi awon ami re ati leyin naa si ilana re lonii olufe.

**(d) Ko seni to le bo lowo ida yii (Esi. 21:13-17)**

Ko sona abayo kuro lowo ida pipon ati didan yi. Ibikibi ti awon omo Israeli ba yiju si tabi ti won ba sa lo, ida naa yo be won wo lona lile koko. O je ida ti won so pe ko ni isinmi, ti o kan n fe parun laisi ijanu. O je ida ti o duro si gbogbo ibi abawole ati ibi abajade ilu naa. O lagbara lati yi sotun tabi si osi. Bawo ni eniyan kan se le yo kuro lowo iru ida bee? Bawo ni o se rorun lati sa kuro ni iwaju Oluwa? Onisaamu se itumo ti o gbamuuse si eyi nigba ti o so pe, “Nibo ni emi yoo ti lo kuro lodo Emi re? Nibo ni emi yoo ti sa lo kuro niwaju re? Bi mo ba dide ni iye apa owuro, ti mo ba duro si iha jijinna rere okun, aani nibe ni owo re yoo fi to mi sona, owo otun re yoo si di mi mu sinsin. Bi mo ba so pe, “Dajudaju okunkun yoo pa mi mo, imole ki yoo si di oru yii mi ka, nitori oru ki yoo sokunkun.” bi imole si o.” (Saamu 139.7-12, NIV). Akorin kan korin, “Iwo elese, nibo ni iwo yoo sare lo si ni ojo idajo?” Ona abayo kan soso ni o wa ati pe JESU KRISTI ni ona abayo na. Fifi aye re fun un ni tooto, rinrin pelu Re ni otito, ati sise ife Re pelu okan arojinle, je dandan.

**II. A O BE JERUSALEMU ATI RABA WO PELU IDA (Esi. 21:18-32)**

**(a) A so awon igbese ti woli na yo gbe fun (Esi. 21:18-20)**

Woli Esekieli tun ni itoni lati si ipele idajo ti o tele e paya fun awon olugbo re. O ni lati se awon nkan wonyi:

1. La ona meji to lo si Jerusalemu ati Raba nibi ti ida Babiloni yoo ti mu idajo Olorun se.
2. Se awon ami itosona si awon ibi meji, ki o si gbe won kale si ibere ipa-ona meji naa.

**(b) Jerusalemu yo koko nipin-in ninu iya naa (Esi. 21:21-27).**

Nigba ti oba Babiloni ba de oju ona onigameji na, yo lo afose (awon kan ka a si sise keke, nigba ti awon kan ro pe o ni i se pelu lilo ere tabi ere terafimu) lati pinnu ibi to ye ki won yiju si, yala Juda ni Jerusalemu tabi Raba (olu ilu awon omo Amoni). Leyinoreyin, yo GBA itoni lati dari si Jerusalemu, yo si kori si ona na toguntogun. Ki se afose Nebukadinesari yi ni o mu idahun wa bi ko se eto atorunwa nitori bi Olorun se fe ki o lo (Owe 16:33). Pelu awon omo ogun re, oba yoo wo awon enubode ilu naa lule, yoo si gbe odi agbara ro, yoo si ko ile iso ti ilu naa. Pelu adehun ti a ti fidi re mule pelu awon ara Babiloni, gbogbo isele naa yoo da bi ala ati ohun to soro lati gbagbo, nigba na ni oba yoo je ki won loye pe eyi n sele si won nitori isote/aigboran won. Ese ati iwa aigboran/ isote won ni yo mu ki awon ara Babiloni o ko won ni igbekun, ki se nitori wipe awon ara Babiloni lagbara ju won lo tabi nitori pe Olorun ko le dabobo won. Nje o ti lo akoko lati ronu nipa kini ese ati isote/aigboran yoo mu wa sori iwo ati idile re?

Asotele naa wa sori Sedakiah Oba nihin-in, nigba ti woli naa pe ni omo alade Israeli. Nibiyi, a pe ni ibaje ati omo alade buburu. A o gba aga ni idi re, a o re sile, a o si yeye re, leyin naa ni ijoba naa yoo pa run, leyin naa ni a o si fi ijoba naa ati isakoso re le eni ti o to si ati ti o si ye lowo, asotele yi yoo se ninu Jesu Kristi gege bi iru-omo Dafidi ninu eni ti asotele naa yoo ni imuse ni kikun (Luuku 1:32; 1Ko 15:25).

**(d) A ki yo da awon omo Amoni si lowo Ida (Ez. 21:28-32).**

Asotele iparun awon omo Amoni, ni o wa si imuse lati owo Nebukadinesari ni nnkan bi odun marun-un leyin iparun Jerusalemu. Niwon bi awon aworawo ati awon woli eke won ti n polongo ida eke ni Amoni saaju akoko yii, ida gidi naa yoo be e wo nikeyin lati je run, nitori o ti to akoko fun ijiya re.

Amoni yoo je iya ifinisefe ati egan re, eyi ni die lara awon iwa ote/aigboran re.

Nigba ti iya ti a o fi je won ko i ti de, ti won si n ri i pe Israeli n la idahoro ati iparun koja, won n fi won se yeye won si n kegan won, o ti le seese ki won ma beere pe ibo ni Olorun won wa ati awon ileri agbayanu to se fun won. Sugbon ni bayi, Amoni ni ijiya kan, yoo si sele gan-an ni ile re, ibi ibi re. Eleyi je lati dojuti koja ironu re. Olorun yoo tu ina ibinu re sile sori awon ara Amoni, yoo si tun mu ki awon okunrin ti o buru ti won si jafafa ninu ise ipanirun lati mu iparun ti a ti so asotele re yi wa sori won. Awon nkan ti o lewu meji: Olorun n ba enikan ja, O si tun gbe awon alailaanu eniyan dide lati doju ija ko. Ibanuje ilopo meji ni yen! Olorun kii se ojusaaju eniyan, Iwo ni ki o yago fun ese, isote ati sise eleya awon ohun atorunwa lati dena iriri ibanuje ilopomeji. Amoni yoo je epo fun ina ati iranti re yo di itan. Adagun ina je otito, o si daju fun gbogbo awon olote/alaigboran, ma se wa lara awon epo tabi igi idana nibe (Orin Dafidi 9:17; Ifihan 21:8).

Ikilo ni eyi fun o pe o ti le ma se aigboran ati da awon ese re tipetipe sehin, ki o si ma mu je, nitori pe o yan lati ni suuru pelu re ni, sugbon mase mu suuru re ni ilora re, kii se rara (2Pet. 3: 9). Jade kuro ninu isote re loni ki o si yago fun idajo re ti o sunmo lori re nipa jijowo ife re fun un.

**IBEERE**

1. Se apejuwe irufe ida Idajo ninu eko wa toni
2. So ohun meta ti a so fun woli Esekieli ki o se ti yo pe akiyesi awon eniyan sodo re nigba ti o ba n je ise Oluwa ti a fi ran gegebi agbekale eko wa toni.
3. So ohun meji ti a ni ki woli Esekieli ki o se ti yo je itosona ati itokasi fun oba Babiloni na
4. Tani ika ati alajebanu omo alade na ninu eko yi?
5. Kinni idi ti a o fi fi ida fi je awon omo Amoni na niya?

**OCTOBER 25, 2026** **EKO 43**

# A KEDE ESE JERUSALEMU ATI IJIYA TI YO TE LE

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 22: 1-16*

***ESE AKOSORI:-*** *"Eniti o bo ese re mole ki yio se rere: sugbon enikeni ti o jewo ti o si ko o sile yio ri aanu." (Owe 28: 13)*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| **MON** | 19/10/2026 | Kiyesi ofin Olorun | Eksodu 20: 1-7 |
| **TUE** | 20/10/2026 | Igboran je ohun ti o nilo | Eksodu 20: 8-17 |
| **WED** | 21/10/2026 | Itoju dipo iponloju | Isaiah 58: 6-7 |
| **THUR** | 22/10/2026 | Ni inu didun si ojo Oluwa | Isaiah 58: 13-14 |
| **FRI** | 23/10/2026 | Eje to nke | Gen. 4: 8-12 |
| **SAT** | 24/10/2026 | A tu asiri awon ese Jerusalemu | Esekieli 22:1-12 |
| **SUN** | 25/10/2026 | A o se Idajo Jerusalemu | Esekieli 22:13-16 |

**ORO AKOSO**

Olorun ko ti pari oro iso pelu woli re nipa awon eniyan ati orile-ede ayanfe re, ti won n gbe ninu ese. Woli Esekieli ni a ran nise si Juda ati Jerusalemu. Ise ti a ran naa se afihan opolopo ati orisirisi awon ese won ati idajo ti yoo tele laipe. Mase so pe Olorun ko bikita nipa bi o se n gbe igbesi aye re. O nife si

gbogbo alaye ti igbesi aye re ati ohun ti o n se, idi ti gbogbo eniyan fi gbodo sora bi a se n gbe igbesi aye wa. Idajo ko le se alaiwa lehin irinajo wa ninu aye, leyin gbogbo ohun ti a ba so tabi se. Nitorinaa, e je ki a sora.

**EKO**

**I. ILU EJE (ES. 22:1-4)**

Jerusalemu, ilu Olorun, ti a bowo fun, ti a si gbe ni ola nla nitori pe Olorun yan an lati inu opolopo ibi ti o lewa lati pa ago re, o si tun yan lati fi se ibugbe re, pelu awon oruko rere bi Sioni, Oke Sioni, ilu nla Olorun, ibi isinmi Olorun, ati bee bee lo, (Saamu 48: 1-2, 8; 76: 2; 87: 1-3; 2Kron. 6: 41) wa ni fun ara re oruko ailokiki ati egan, ti o buru ju, oruko kan ti o ni nkan se pelu itajesile. O ye fun afiyesi pe, "oruko ti a fi wa n pe Jerusalemu nibibayi, kii se nitori pe o ti jebii ese itajesile ni pato, sugbon nitori pe awon iwa odaran re lapapo je iwa odaran to buru jai (Isikieli 7:23), irufe eyi to ti so o di alaimo ninu eje re, ti o si ye ki a fi eje fun un lati mu." (Matthew Henry). O fi han kedere pe Jerusalemu lo gba oruko re yii nipase awon iwa ibi ati iwa ika re. Kini oruko re? Oruko wo ni awon eniyan n pe o? Ni agbegbe wa fun apeere, a le ba awon eniyan kan pade ti won, pelu ayo ati awada pe ara won ni iru awon oruko irira, bii, "Oosa", "Ori Oka", "Iku gangan", "Ijaya", "Eyin Ejo", "Gbomogbomo", "iboji', "Japata", "Eegun" (Masquerade), "Egun" (Thorns), "Posi", "Baba Trophy/Stout", "Bobo Pelebe", ati bebe lo. Awon ti o ni ipa ninu iwa yii paapaa tun ni Ife si pipe ati didahun iru awon oruko bee. Igbesi aye wo ni o n gbe ti o je ki awon eniyan fun o ni iru awon oruko bee? Se won je oruko ti n fi ogo fun Olorun ni abi awon ti n mu ki awon orun sofo, ti won si n sokun nitori re? Eyi je ojo kan ti Oro Olorun n wa o jade fun ironupiwada ati iyipada rere. Ronupiwada loni, ki o si mu orun yo lori re.

**II. AKOSILE AWON ESE ATI ISOTE/ AIGBORAN JERUSALEMU**

Olorun, nipase wolii naa toka si die larin awon ese Juda, awon ni wonyi;

**(a) Tita eje sile** - Esekieli 22:2, 4, 5, 9

Se won ti gbagbe ase Olorun laipe to so pe, "Iwo ko gbodo paniyan," (Deu. 20:13)? Won di apaniyan ti n ta eje alaise sile. Olorun yoo beere lowo re gbogbo eje ti o ta sile gege bi O ti se si Kaini nigba ti o so fun un pe eje arakunrin re n ke pe oun (Gen. 4:8-12). Eje alaise ti Manase ta sile ni a ko gbagbe sugbon o pada je ere re ni kikun (2 Awon Oba 24:1-4). Sora!

**(b) Awon ohun irira/ Awon ise irira** -

Es. 22:2. Won lowo ninu awon ise aiwa-bi-Olorun ati ohun irira. Mase je ki a ri o pelu ohunkohun ti o je irira, mase ko pa ninu re.

**(d) Iborisa** - Esek. 22: 3, 4, 9. Saye wo awon orisa ti o wa ni okan re ati awon ti o wa ni owo re. Ohunkohun ti o se pataki fun o ju titele Olorun ati ilana re je orisa. Ka Eks. 20:1-5.

**(e) Asilo ati ilokulo agbara ati ase** –

Esek. 22: 6. Awon ti o wa ni ipo ase, bii awon asaaju esin, awon oselu, awon baale ati ijoye won, awon oga ni ibi ise, awon oludari leka leka, awon obi, awon agba agba ati awon agba ni awon eto ati awon eka, ati bebe lo, nilo lati kiyesara ki won ma ba jebi asilo ati ilokulo agbara.

**(e) Aigboran si ati aibowo fun awon obi** - Es. 22: 7. Eyi tun je okan ninu awon ifihan ti awon iriri igba ikehin, ti o tun fe dabi pe o fe buru ju ohun ti o ti wa lati ojo atijo lo. Awon omode gbodo kiyesara ki won si gba itosona ati itoni. Ka Eks. 20:12; Lev. 20:9; Matt. 15:1-9.

**(f) Ireje ati ibaje** - Ez. 22:7. Bawo ni eyin ti n se si awon ajeji, awon omo orukan, awon opo? Olorun ko fi eleyii ati awon itoni re miran se awada rara. Ka Isaiah 58:6-7.

**(g) Ibaje ohun mimo** - Es. 22: 8. Mase ba ojo Oluwa je sugbon ma a bu ola fun un. Bowo fun oro Olorun ati itoni Olorun. Ma se tun ese awon omo Israeli se.

**(gb) Awon esun eke / iro** - Esek. 22:9.

Won fi esun eke kan awon eniyan niwaju awon ijoye lati jere oju rere ati lati pa emi awon eniyan run. Igba melo ni o ti fi esun eke kan enikan nitori awon idi kan tabi omiran? O je ibi ati ese ti o la ijiya lo. O nilo iyipada aye re ninu Kristi.

**(i) Agbere: Owo nabi, pansaga, agbere, nini ibalopo pelu ibatan eni, ibalopo lona odi, ifipabanilopo**

- Es. 22:9-11. Ka Eks. 20:14; Lef. 20:10-23; 1Kor. 5:1-13. Ibalopo ki ibalopo ti ki se ninu igbeyawo ati laarin awon meji ti won ti gbe ara won ni yawo, ni ona yowu ki o je, je ese, nitorina, a gbodo yera fun un ki a si sa fun un. Arabinrin tabi odobìnrin naa, okunrin tabi odokunrin naa, ti o n sabewo si, tabi ti o n sabewo si o ni ikoko, bawo lo se je? Okunrin tabi obinrin yen, ti e n gbe po, se oko tabi aya re to ti segbeyawo pelu re lona ti o tona ni? Ti o ba ti be, o lewu osi je igbeaye iparun, ayafi ti o ba ronupiwada.

**Akiyesi:** Ibalopo nigba nnkan osu laarin tokotaya, ninu majemu tuntun, kii se ese rara. Ohun ti o kan sele ni wipe o gbodo je wipe won fe be, ati pelu, asoyepo ati ifowosi ni lati waye larin tokotaya ti won ti ferawon nisu loka. Ninu imo ijinle nipa oro ilera, awon obinrin kan wa ti o je wipe awon ojo ti won nse n kan osu won gangan ni ojo ti eyin omo won le di omo ti o ba ri ato oko won, imoran awon onisegun oyinbo fun won ni ki oko won ba won lopo ni akoko bee, paapaa fun awon ti o n duro de Oluwa fun eso inu.

**(h) Ibaje** - Abetele, owo ele, ojukokoro, ere aisododo, ilonilowogba - Es. 22:12

**(j) Gbigbagbe ati kiko Olorun ati awon ofin re sile** – Es. 22: 12. Ka Deu. 4; 23; 6:12; 8: 11-20.

**(k) Iwa aimo** - Esi. 22:13

Ewo ninu eyi ti a ko si oke wonyi ni o wa ninu aye re? Ko si okan ninu awon ti a ko soke wonyi ti o kere tabi je ese nla lati ya eniyan kuro lodo Olorun ati seto enikan fun ijiya ati idajo re. Ronupiwada loni!

**III. IDAJO FUN AWON ESE ATI ISOTE/ AIGBORAN JERUSALEMU**

Niwon bo ti je pe inu Olorun ko dun si awon iwa ese ati isote to wa loke yii, o so idajo ti Oun yo fun awon eeyan re gege bi Olorun to ni ikoraeninijanu ati olododo. Awon idajo wonyi ni a ko si isale yi:

* **Egbe / Iparun** - Esek. 22; 3. Isote ati ipeyinda n yori si iparun, aani iparun awon omo re ayanfe paapaa. Ma a gbe ninu ese ati aigboran, ewu ni yo mu wa fun o. Isa. 1: 19-20.
* **Egan ati Ifinisefe** - A o so won di eni egan ati erin – Esi. 22:4-5.
* **Tituka ati pipinka** - Esek. 22:15. Olorun se ileri lati tu won ka. A o ko won ni igbekun lo si awon orile-ede ajeji ati awon ti won ko mo Olorun, lodi si ife ati igbagbo won.
* **Egbin** - Esek. 22: 16. Ka Jer. 13: 27. Niwon bi won ti ko lati we ara won mo, ki a si so won di mimo, awon keferi yoo tunbo so won di elegbin.
* **Olorun yo ko won, yo si ti won sode** – Esek. 22:16 - Baba onifee ko si ohun ti o fe se nisisiyii ju ki o ko awon tire. O ti pinnu lati le won jade, ki o si so won di eni itanu. Ni opin aye, awon ti won ko lati gba Kristi gege bi Oluwa ati Olugbala won ati awon ti won gbe igbe aye won ninu ese ati aigboran yoo je li le jade kuro niwaju Olorun ati iye ayeraye si idalebi ayeraye. Mase je ki iyen je iwo. Wa sodo Kristi loni ki o si gbe igbe aye iwa mimo ati igboran si oro re. E je ki a ko Orin 166 ninu iwe orin ihinrere wa.

Awon ese kii se awon ise tabi awon nkan ti enikeni ko mo. Ni asiko yii, ko si enikan ti o le so pe oun je alaimokan tabi alailoye ninu awon oran ti ese. Olorun je alaanu nla fun wa, idi ni yi ti o tun fi mu ore-ofe eko yi wa lati tun ran wa leti die lara awon ese wonyi ki a baa le bo lowo iparun ayeraye. Gbogbo ohun ti a nilo ni lati ronupiwada kuro ninu gbogbo awon ese ki a si koju ija si awon ese papaa titi de eje wa, ninu irin ojoojumo wa pelu Kristi (Heb. 12: 4).

**IBEERE**

1. Ki ni oruko Jerusalemu ti Olorun pe?

2. Daruko awon oruko buburu miiran, yato si awon ti o wa ninu eko, ti awon eniyan n pe ara won pelu igberaga loni, sugbon ti awon omo Olorun ko gbodo ko pa ninu re.
3. Soro nipa awon ese marun-un eyikeyi ti Olorun se tan lati fiya je Israeli ninu eko wa lonii
4. Ki ni o ye ki o je iwa wa ati iha ti a ko si awon alejo, awon alainibaba ati awon opo?
5. So ijiya meji eyikeyi ti Olorun yoo mu wa sori Jerusalemu fun ese re.

**NOVEMBER 1, 2026** **EKO 44**

# A KO RI ENIKAN TI O YE LATI DURO NIWAJU OLORUN FUN ISRAELI

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 22: 17-31*

***ESE AKOSORI:-*** *"Emi si wa enikan laarin won, ti iba tun odi na mo, ti iba duro ni ibiti o ya na niwaju mi fun ile na, ki emi ma ba parun: sugbon emi ko ri enikan." (Esekieli 22: 30).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| | Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|---|
| MON | 26/10/2026 | Ipinle Olorun duro sinsin | | Timotiu keji 2:15-19 |
| TUE | 27/10/2026 | A ri gegebi olododo ni Iran re | | Gen. 6:1-13, 17-18 |
| WED | 28/10/2026 | A ri a si pe jade lati inu iborisa | | Gen. 12: 1-7 |
| THUR | 29/10/2026 | A ri a si ya soto lati inu Iya re wa | | Jer. 1: 4-10 |
| FRI | 30/10/2026 | Ina ileru ti Idajo | | Esekieli 22:17-22 |
| SAT | 31/10/2026 | Ikuna ninu isakoso | | Esekieli 22:23-29 |
| SUN | 1/11/2026 | Nibo ni awon olododo wa? | | Esekieli 22:30-31 |

## ORO AKOSO

Wiwa enikan tabi awon kan ti won ni igbeaye ati iwa to lola gbe tabi bi awon ayipada ati idagbasoke rere je ohun kan ti o se pataki ni gbogbo iran. Eredi eyi ni pe nigba ti Olorun ba fe se ohun kan, o sa ba maa n se e nipase awon eniyan, nigbati sise e nipase awon angeli si je ekan laare. Awon okunrin wonyi ti Olorun ri fun ise re tabi imuse awon ife okan re nigbagbogbo ti je awon okunrin olola, alailegbe ati awon ti won ni iroyin/oruko rere. Gbogbo iran ti o ti koja ni o ni awon eniyan daradara ati oloruko rere ti a n so nipa re yi. Abraham ni Olorun ri ti o si pe jade nigba ti o fe seda orile-ede ti yoo yan fun ara re ninu awon orile-ede aiye (Gn. 12:1-7). Saaju akoko yi, Olorun ni lati yan Noa, eni ti Bibeli kowe re pe o je olododo ni gbogbo iran re, lati bere iran miiran (Gen. 6:17-18; 7:1). A yan Mose lati dari awon omo Israeli jade kuro ni oko-eru Egipti (Eks. 3: 7-10) nigba ti a yan Josua lati pin ile ileri fun won (Josh. 1: 1-9). Awon miiran ninu akosile naa ni Jeremiah (Jer. 1:4-10), Jona (Jona 1:1-2), Esteri (Esteri 2:17; 4:12-17), Maria (Luuku 1:26-33), Stefanu atawon alabaakegbe re (Ise 6:1-6), ati bee bee lo. Awon wonyi ni Olorun ri ti won ye ni eniti a yan tabi ran fun ise kan tabi omiran fun un.

Igbesi-aye olote ati aibikita ti awon omo Israeli ati awon adari won ninu eko ti a gbeyewo yi ni o mu ki Olorun pinnu lati je won niya, ni mimu won la ina ileru koja bi awon eroja iyebiye ti a mu la ina koja lati le we mo. Ona yii je iwon ijiya ti Olorun n seto lati se bi o se kede idajo re sori Jerusalemu ati awon olugbe re. Ni aarin gbogbo iwonyi, Olorun n wa o kere tan enikan ti o ni iduro to to ti yoo duro lati maa bebe fun

won ati lati gbe igbese lati dari won pada si ipa ona igboran ati ododo, sugbon o senilanu, Olorun ko ri enikan. Nje Olorun yoo ri o ni olododo nigba to ba be o wo, se yoo ri o pe o ti mura sile lati je ohun elo mimo re, se yoo ri o ni eniti o ti muratan lati ba Oun pade nigba ti Oun ba de?

**EKO**

**I. A O FIYA JE ISIRAELI NINU INA ILERU (ES. 22:17-22).**

Olorun tun binu si ona igbesi aye Israeli ati isote won, o fi oro re ranse si woli re, woli Esekieli, nipa iru idajo ti oun yoo mu wa sori won. A ti rii leralera pe ese, aigboran ati isote loniruru ona, yala isote kekere tabi eyi ti o dabi nkan ti ko lewu, n fa ijiya. Je ki gbogbo awon ti a n pe oruko Oluwa mo kuro ninu aisedede (2 Tim. 2: 19).

Olorun fi Israeli han bi idaro. Iyen je ipo ti won wa gan an. Won kun fun ese ti o mu ki aye won kun fun ohun aimo. Awon ohun aimo wonyi ninu aye won lo so won di idaro. Kini idaro? A o dahun ibeere yii nipa wiwo ohun ti iwe-itumo so nipa idaro, bayi:

Egbin tabi nkan alaimo nkan ti o dogun lara irin ti o mu ki o dabi enipe nkan njera.

Awon nkan aimo ti o ntin ara irin jade.

Egbin ti o njade lati pase sise pelu irin.

Apeere ohun ti ko niye lori tabi nkan yepere.

Laisi oro pupo si i, a le loye ohun ti Olorun n so nipa awon omo Israeli daradara ni akoko yii. Olorun n wo won gege bi egbin, alaimo, asan ati ohun elo ti ko fi bee niye lori. Itiju ni eleyi je fun orile-ede ti Olorun fun raa re yan! Wo aye re jinlejínle. Kini otito aworan re gangan? Ta ni o gan-an? Gbagbe nipa irisi re nita. O mo daju pe isote ni irisi re nita. Se o ki n se ofo ninu ijoba Olorun bayi? Iwo ki i ha se ohun elo elegbin ti n gbiyanju lati fi wiwa si ati kikopa ninu awon eto ijo ati ijosin bo ohun ti o je gan an molebi? Se o ki se ohun abuku si Kristi ati ijo re nipa awon ohun ti o n se ni ikoko ati ninu okunkun, nibi ti eniyan ko si? Ti Kristi ba ma pe o ni oruko kini oruko na yoo je? Se oruko yi ki yo je idaro? Mase gbagbe a ni eniti a pe ni Ikabodu ninu iwe-mimo lati so fun Israeli pe ogo re ti lo ti pe. Nigbati ogo ba lo ki ni ohun ti yo ku? O daju pe itiju ni yo ku. Tori naa, ohun ti o n so ni pe oruko Israeli ni sin yi ni ITIJU (1 Sam. 4:19-22). Ronupiwada ki o yipada awon ona re lati pa IDARO ati ITIJU lara awon oruko ti o wa ninu aye re.

Ibinu gbigbona Olorun ni a o fe sori Israeli gege bi ijiya fun awon ese re gege bi ina ti n jo idaro kuro ninu awon irin iyebiye ti a menukan ninu ese naa, ina naa ko ni jo won fun afomo fun ilosiwaju gege bi o ti ma n ri pelu awon irin sugbon fun iparun. Nitooto, nigba ti awon olote ba jona, iyoku yoo je ohun elo mimo ati ohun elo mimo fun Oluwa gege bi ojulowo wura ati fadaka ti n yori si leyin ti won gba inu ileru koja. E je ka ka awon ese Bibeli yii: Owe. 25:4; Isa. 1: 25-27. Fun irannileti: Ileru kan wa ti n jo lailai ati ti kii ku, fun ijeniya fun gbogbo awon ti yoo ko lati ronupiwada kuro ninu aigbagbo won, ise buburu, aigboran, isote ati gbogbo ese ikoko ati ese gbangba won (Ifihan 21: 8) - ma se deja re - ma sese aibikita pelu anfani yi lati ronupiwada ati ki o si gba Kristi lotito loni, ola le pe ju fun o.

**II. IKUNA AWON ASAAJU (ESEK. 22:23-29)**

Olorun soro ibanuje nipa awon ohun aile ra to wa laarin awujo Israeli. O je ohun iyalenu bi ibi ti n jade ni akoko lati odo awon adari. Eka meteeta ti awon asaaju ni ile naa, ati awon araalu, ni won lowo ninu iwa ika ati ibi ti o gbil e ni ile naa. Awon omo alade, awon oloselu, ati awon alufaa, gbogbo won ni won ti fi owo won sinu iwa aimo ati iwa ika wonyi.

Awon omo-alade ni awon adari/asaaju ti agbegbe awon eniyan Olorun. A fi won we kinníún ti n ke ramuramu. Won lowo ninu gbigbe awon eniyan ile naa je, won n ji eru won gbe, won n fipa gba ohun ti won fe lai beru. Won ni lati je apaniyan ni taarata tabi nipase awon iwa buburu won wonyi, ti o mu ki opo di opo. Awon ise ati iwa wo ni o wa lowo re gege bi adari egbe yala kekere kan, boya ninu ebi, ijo tabi agbegbe? Wo aye re finifini ki o si ronupiwada.

Awon alufa je gbogbo awon asaaju nipa ti emi ninu awujo, bi awon woli, awon oluso-aguntan, ati bebe lo. Won je ibanuje si Olorun gege bi eni ti a gbe ojuse nla ati awon ise mimo julo fun sugbon ti o kuna. Won so awon ofin Olorun di ofo. Won ka oro ati ase Olorun si oro lasan. Eko ati iwasu won tako agbekale oro Olorun. Won so awon ojo isinmi di alaimo. Won ko abuku nla ba Olorun ati oruko re. Eyin oluso-aguntan lori agbo ijo Olorun, bawo ni e se n gbe igbesi aye yin ti e si n boju to ise Olorun ati awon nnkan re lonii? Se e ko ma rin Olorun fin pelu ona ti e ngba dari awon eniyan re? Awon asotele iro ni ibi gbogbo nitori e fe ni okiki ati nitori owo. Kini o so wipe Olorun so ti ko si so? Iwo ti n se bee ni opo igba ki awon eniyan le beru, ki won si ka o si woli ti n ri iran ti o si n gbo lati odo Olorun. Tani o n gbiyanju lati wu gan an? Tani o n tan? Kini yoo je ere re fun gbogbo awon iro re wonyi ati ayederu eni emi ti o nfihan nita yi? O ti so ebun isotele di irinse ipaowowole, fun ere ti ara re. Iwo ko tobi ju eniti Olorun yo je niya lo, nitorina, ronupiwada ki o yi ona re pada loni.

Awon oloselu, awon olori oselu na lowo ninu iwa ika. A fi won we ikooko. Won pa, won si ta eje alaisê sile. Won se ohunkohun fun owo. Naijiria ati awon oloselu re ni oye ohun ti a n soro re yi daadaa. Idi ni yi ti awon eniyan kan fi ma n pe oselu ni ere / ayo idoti. Kii se idoti sugbon awon ti o n ko pa ninu re ni o je ki o ri bi nkan idoti nipase awon ise elegbin ati igbesi aye won. Se o ye ki a tesiwaju ni ona yii? Rara. A nilo ironupiwada tooto loni.

Awon ara ilu na ko gbehin ninu iwa ika yi. Gbogbo eniyan ni o dabi eni pe o ni ipa ninu ise ailola kan tabi ekeji: ilonilowogba, idigunjale, ireje awon talaka/aini, iwa ika si awon alejo, aisedede, ati bebe lo. Sayeewo idile re ti o sunmo o, ile ijosin, ile-iwe, ofiisi, oja, ile-iwosan, agbegbe re, ati bebe lo, se a ko ma ri irufe awon iwa ati ise wonyi paapaa laarin awon omo egbe si omo egbe, laiti so larin awon olori? Gbogbo wa la nilo ironupiwada tooto ati ogidi loni.

**III. AINI OLODODO ATI IDAJO TI O TELE (ESEK. 22:30-31).**

Titobi aanu Olorun je eyi ti o sowon. Laika gbogbo iwa ibi wonyi si, Olorun si n wa ona lati dari ji won ko si fi aanu ba awon eeyan re lo. Idi niyii ti o fi n wa olododo kan lati duro lati ke pe Oun fun aanu nitori ile naa, ki o si tun sise gege bi alatunse ti akoko ati iran yen, lati satunse gbogbo ohun ti ko to, sugbon e wo bi o ti saanu won, ko ri enikan. Ranti oran Sodomu ati Gomora, awon olododo meloo ni Olorun n wa, meloo lo si ri nigbeyingbeyin? Nje a pada da awon ilu na si nikehin tabi a ko da won si (Gen. 18:20-33; 19:24-25)? Se o ro pe Olorun yoo ri olododo kan, eniyan mimo kan, enikan ti o ni okan Olorun, ninu ebi re, ile-iwe, ofiisi, tabi nibi ti o ti ba arara re yen? Se iwo yoo je olododo yen ati alatunse ati eni ti yoo mu iyipada rere wa?

Idajo na je idajo atokewa. Olorun ti se tan lati rojo ina sori Israeli lati jo o run. Olorun fe lati san an fun Israeli gegebi ise ati iwa re. Ronupiwada loni lati yago fun esan ise ati iwa owo re.

Titi doni, Olorun si nwa awon eni ti yo o ri ni olododo, olooto, ati eni ti n so eso rere fun ise re, lati mi aye fun ogo re. Awon ti o ti ya ara won soto, ti o ni ikoraeninijanu, ati ti won si ni ifaaraenijin, ti won si n gbe igbesi aye won gege bi ife re, ni Olorun le ri ni eni ti o ye lati lo. Gbiyanju lati je irufe eni ti Olorun yo ri pe o ye.

**IBEERE**

1a. Kini idaro?
b. Awon wo la fi we idaro, ki si ni idi re?
2. Ki lawon nnkan to le je idaro ninu igbesi aye wa loni?
3. Ki ni ijiya fun jije idaro?
4. Isori awon eniyan wo ni won fi esun iwa ailola kan. Kini awon iwa ati ise ailola na?

5. Kini idi ti Olorun fi n wa enikan laarin awon eeyan re?

**NOVEMBER 8, 2026** **EKO 45**

# AWON IBALOPO AILOLA ATI AITO TI AHOLA ATI AHOLIBA ATI IJIYA WON

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 23: 1-10*

***ESE AKOSORI:-*** *"Nitori enyin mo eyi daju pe, ko si pansaga, tabi alaimo enia, tabi olojuko koro, ti ise oluborisa, ti yio ni ini kan ni ijoba Kristi ati ti Olorun." (Efesu 5: 5).*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| MON | 2/11/2026 | Gbogun ti awon ise ti ara | Gal. 5: 19-21 |
| TUE | 3/11/2026 | Ako gbodo daruko won larin yin | Efesu 5: 1-5 |
| WED | 4/11/2026 | Sa fun ese agbere | Korinti kini 6:12-20 |
| THUR | 5/11/2026 | Ibare aye di ewo | Jakobu 4: 4-8 |
| FRI | 6/11/2026 | Mase feran aye | Johanu kini 2:15-17 |
| SAT | 7/11/2026 | Mase kegan yiyan re | Orin Dafidi 78: 67-69 |
| SUN | 8/11/2026 | Sora fun agbere emi | Esekieli 23:1-10 |

## ORO AKOSO

Olorun ko dake rara ni siso ero re fun awon iranse re. Gbogbo awon ti won n teti si itosona Emi ti won si n yi opopona temi won pada si ohun Olorun laijafara yoo tun gba oro lati odo re. A ko gbodo di eni ti ko gboro, a gbodo se itara lati gba awon ifowosi ati itosona Olorun. Woli Esekieli gbadun eyi ni idurosinsin, nitorinaa Olorun n ba a soro. Maa wa ni ibamu pelu Emi Olorun nigbagbogbo. Olorun maa n soro, sugbon die ni awon ti n gbo.

Ise iranse yii je nipa ibinu Olorun si igbe aye ati iwa irekoja ti orile-ede Israeli, awon ti Olorun yan. Ife won pelu awon orile-ede alaikola ati awon asa iborisa won ni a salaye ati dida lebi pelu ijiya ti o tele. Olorun je Olorun owu ti o ri enikeji ti o ni awon olorun miiran pelu re gege bi pansaga, alagbere ati asewo, nitorinaa o ye fun ijiya Olorun. Ma se je pansaga, alagbere tabi asewo, yala ni awon nnkan ti ara tabi ni awon nnkan ti emi. Sa fun agbere; sa fun pansaga (1 Kor. 6:12-20).

## EKO

**I. AWON ASEWO NI EGIPTI (Esekieli 23:1-3)**

Olorun wa sodo woli re ni ona owe. Bi Jesu se maa n soro pelu awon owe si awon olugbo re lati so awon iwasu pataki pelu otito ti o jinle. Fun apeere, owe afurugbin (Luuku 8:4-18). Ni akoko yii, je ki awon akeko daruko o kere tan awon owe meje ti Kristi so, ki oluko si ye awon idahun won wo.

Oro ti a fi ran woli naa so nipa awon obinrin meji ti o wa lati odo iya kan naa sugbon ti won fi ara won fun ise asewo sise. Won ta ara won fun awon okunrin ni pasipaaro fun awon ohun ti won ro pe o je rere sugbon ti a ba wo daradara, a o ri wipe, awon nkan ti won ro wipe awon yoo rigba naa ko si ni be. Ni Egipti ni iwa buburu yii ti waye ni ilodi si ofin ati ase Olufe won akoko. Awon obinrin meji yii je ki awon ajeji fowo kan, fowo ro ati fowo pa omu won.

O seni laaanu loni pe iru iwa kan naa n sele laarin awon odo kan ninu ijo ati awon ti won ti segbeyawo paapaa. Itelorun ibalopo, eyikeyi ti o wu ki o je wa fun awon ti won ti segbeyawo nikan, pelu ilana ti o le wipe inu igbeyawo nikan ni o ti gbodo waye. Sora fun ife pelu enikeni ti o ko ba segbeyawo pelu re pelu ifowosi labe ofin, o je eewo. Ma se so pe a kan se ifenukonu ni, o si fowo kan omu mi laisi pe mo bo aso

mi, ko si fi nkan omokunrin re sinu nkan omobinrin mi, nitorinaa mo si je wundia. Rara. Lesekese ti o ba fi eyikeyi eya ara re fun ifowosi ibalopo nigbati o ko ti se igbeyawo tabi ti ki se pelu eniti o se igbayewo pelu re, o ti wonu iwa palapala ti o je ibalopo, o ko si ye ni eniti a le pe ni wundia, yala ni ti ara tabi ni ti emi, ti Jesu n wa. Ma se ni ifekufe si elomiiran, ma se je ki elomiiran ri ihoho re tabi fowosi eyikeyi eya ara re yato si eni ti o ti segbeyawo pelu. Dawo agbere tabi pansaga ti o ti wa ninu re duro ti o ba je wipe o ti gba emi ati iwa palapala yi laye ninu aye re, Jesu si nife re.

Iwa asewo/pansaga awon arabinrin meji yii waye ni Egipti. Egipti, ile awon alaikola. Egipti, ile okeere. Egipti, ile ajeji. Egipti, aye ati eto re. Awon arabinrin meji yii ko ye ki won wa ni Egipti ni akoko, ki a to wa so pe ki won wa ninu ibasepo kankan nibe pelu awon eniyan re. Kini idi ti o fi wa ninu ibadore pelu aye ati eto re? Wo ohun ti Bibeli so nibi: Jakobu 4:4; 1 Johannu 2:15-17. Kini idi ti iwo gege bi Kristeni, si n darapo mo awon ore re lati jokoo ni ayika tabili nibi ti won lo mu oti, ti o si n so pe o ko mu pelu won, pe a kan jade lo fun igbadun papo ni? Ye ara re wo ki o si pada sodo Eleda ni bayibayi.

## II. FIFI ENITI AWON OBINRIN MEJEJI YI JE HAN (Esekieli 23:4)

* **Ahola** - Eleyi ti o je egbon ninu awon obinrin mejeji yi ni won pe ni Ahola tabi Ohola gege bi agbekale awon eda Bibeli kan. Ni tooto, Aholah tumo si, “O ni ago tire”. Oruko yii ni a lo lati sapere iborisa ti ijoba Israel. Ijoba yii ni a sapere gege bi obinrin oniwa palapala, pansaga, ti o fi ara re fun awon ohun irira ati iborisa ti awon ara Egipti ati Asiria. Eyi ni idi ti won fi ko o ni igbekun, ti ijoba re si dopin (Saamu 78:67-69; 1 Awon Oba 12:25-33; 2 Kronika 11:13-16). Kini oruko re? Oruko re tooto safihan gbogbo igbe aye re. Oruko re fi eni ti o je han.

* **Aholiba** - Aholiba tabi Oholiba je aburo. Aholiba tun tumo si, “Ago mi wa ninu re.” Oruko yii ni a lo ni isapeere fun Jerusalemu, nitori o ti ko ijosin Olorun tooto sile ti o si fi ara re fun awon iborisa ti awon orile-ede ajeji. Eni ti Olorun feran ti o si n gbe inu re pinnu lati ko o sile fun elomiiran. Ki lo n mu o lati ronu nipa kiko Olorun sile? Se awon igbadun aye yii ti o je fun igba die ni? Ronu nipa eyi, ma si se se bi Demasi (2 Timoti 4:10).

Awon nkan ti a ti gbeyewo ni oke wonyi ni aworan ti ijoba Israel ti o pin si meji ati bi won se lo sinu iborisa. Ijoba ariwa ni akoko, ti Samaria nsapeere, ati leyin naa ijoba guusu, ti Jerusalemu sapeere. Ni erefe, Ahola ni Israeli (Samaria = Ijoba ariwa) ati Aholiba si je Judah (Jerusalemu = Ijoba Guusu).

## II. AHOLA NINU ISE ASEWO/ PANSAGA ATI IJIYA RE (Ezekieli 23:5-10)

Orile-ede Assiria je orile-ede iborisa pelu awon asa ti o lodi si ti Yahweh, Olorun ti Israel seleri idurosinsin si. Nigba ti Israeli di alaini itara ti won si gbojege, won lo sinu awon asa bii ti orile-ede yii ati ti Egipti, orile-ede ti won ti lo igba odo won. O je idagbasoke buburu bi Olorun se n ran awon woli re si won lati kilo fun won ni owuro ati loru sugbon won ko fetisi. Leyin naa, o mu awon orile-ede yi kan naa lodi si won ti won si ko won ni igbekun lodi si ife okan won. Gbogbo eyi ni a sapeere gege bi ise asewo tabi pansaga, fifi ara won fun awon okunrin, oniruuru ifekufe, awon okunrin ti n ba a lo, omu re ti won n fowo ro, ati bee bee lo. Bakan naa, fifi ihoho re han, kiko awon omo re kuro lodo re, pipa, ati bee bee lo, je awon ijiya ti o de ba a.

Kiko Olorun sile, ipadaseyin, ilowowo si awon nnkan emi, ati bee bee lo, je sise agbere/asewo emi ti o si n fa idajo Olorun wa. A gbodo sora ki a si se ohun ti o ye bi Olorun se n ran oro re wa si wa leekan si i loni ni owuro yi.

Nigbati o ti wa sodo Kristi ti o si so wipe o ti fi aye re fun gegebi Oluwa re, nje o mo wipe o ti wonu majemu lati je iyawo re? Irinajo igbeyawo ti o pe fun jije olooto ni eyi je. Kilode ti o fi gba iwa agbere ati pansaga laye? Kilode ti o fi ni olorun miiran pelu re? Kilode ti o ti fi mu awon nkan aye ni pataki ju wiwa pelu Eleda re lo? Ji loju orun, yi pada si Kristi ati ife re lati dena iya ayeraye.

**IBEERE**

1. Kini o loye nipa gbolohun naa, “Olorun je Olorun owu,” ni ibamu pelu eko wa loni?
2. Dahun si eyi: “A lomìnira lati lo ara wa bi o ti wù wa nitori a wa la ni ara wa.”
3. Ese wo ni a fi we iborisa ninu eko naa?
4. Kini awon oruko ati itumo awon obinrin mejeji ti a gbeyewo ninu eko wa? Kini awon oruko won nsapeere?
5. Daruko awon orile-ede meji ti won darapo mo lati se pansaga/asewo.

**NOVEMBER 15, 2026** **EKO 46**

# KIKO OLORUN SILE JUDA ATI JERUSALEMU ATI AWON ABAYORISI RE

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 23: 11-35*
***ESE AKOSORI:-*** *“Ori awon enia buburu li a o da si orun apadi, ati gbogbo orile-ede ti o gbagbe Olorun.” (Orin Dafidi 9: 17).*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| | Ojo | Deeti Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| **MON** | 9/11/2026 | Mase gbe ninu ara mo | Peteru kini 4: 1-6 |
| **TUE** | 10/11/2026 | Pa eran ara ati awon ise re | Kol. 3: 1-6 |
| **WED** | 11/11/2026 | Kiyesi awon ona re | Awon Oba keji 21:1-8 |
| **THUR** | 12/11/2026 | Mase je ki Olorun ko o sile | Awon Oba keji 21:9-16 |
| **FRI** | 13/11/2026 | Sora fun ikosile Olorun | Samueli Kini 15: 22-26 |
| **SAT** | 14/11/2026 | Isekuse temi | Esekieli 23:11-22 |
| **SUN** | 15/11/2026 | Ijiya fun isekuse temi | Esekieli 23:23-35 |

**ORO AKOSO**

Olorun ko fi kiko Olorun sile ati ipehinda sere rararara. O je Olorun owu ti n so oruko ati ogo re pelu owu. Dipo ki Juda ko eko lara arabinrin re Israeli, o tun se pansaga ju u lo. O ri ara re sinu iborisa lodi si ofin ati ase Eniti O mo o. Awon ise iborisa re mu Olorun banuje ati pe o mu ki Olorun korira ibasepo pelu re, eleyi wa mu ki Olorun pinnu lati je e niya bi o ti fiya je egbon re Ahola. Fun apeere, ki lo de ti a si fi n ri awon eniyan ti n jale leyin ti won ri wipe won dana sun ole kan niwaju won? Ma se gbe ninu isote pelu okan ti iye re ti ra. Idajo je otito, yoo si de ba gbogbo awon elese, nitorinaa, ronu piwada loni.

**EKO**

**I. AHOLIBA TELE AHOLA (EZE. 23:11-22)**

Titele ipase eni ti o ti subu sinu koto ko je ona ogbon. Eyi ni igbese asiwere ati isote ti Aholiba na gbe. Aholiba, ti o sapere ijoba guusu Israeli ti a mo si Juda pelu olu-ilu Jerusalem, ko lati ko eko lati ara iparun ijoba ariwa, ti a mo si Israeli pelu olu-ilu ni Samaria. Iyerira ati ironu omugo won, to o mu ki won ro wipe awon keferi ko le bori Yahweh ati pe Yahweh ko le ta awon eniyan Re ti o feran si awon orile-ede alaikola bi won tile tesiwaju ninu iwa ika, aigboran, iborisa ati isote won, mu ki won se alaibikita si awon ikilo Olorun ti O ran awon woli re ti o gbe dide lati fi oro re fun won ati lati to won.

Juda buru si i ninu ese re ju Israeli lo (Eze. 16:51). Apeere gboogi kan ni ti ijoba Oba Manasseh (2 Oba 21:1-16). Awon kan a maa so wi pe awon maa da ese de bi ti Olorun yoo fi binu to bee ti yoo ju awon koja ina idajo, awon yoo ba bo lowo ijiya. Bawo ni eyi se le seese? Eyi je okan lara Ifihan okan ti iye re ti ra. O je awada ti ko mu ogbon dani.

Wonyi ni awon ese ati irekoja re:

1. O darapo mo awon ara Assiria.
2. O ka awon okunrin won si elewa ju awon arakunrin re lo.
3. O lowo ninu ijosin orisa won.
4. O se ifekufe pelu won.
5. O bowo fun orile-ede alaiwa-bi-Olorun.
6. O darapo pelu awon ara Babiloni, o darapo mo awon olori Babiloni, o si gbe awon aworan, orisa, pepe ati tempili won wole, o si mu won wonu ijosin won.
7. O tun se pansaga pelu awon ara Egipti.

Abajade iwa ese ati ika re ni pataki ni wipe Olorun ko nife si i mo, o si yago fun un. Nigba ti Olorun ba pinnu lati yago fun aye enikan, ile tabi owo enikan, gbogbo wa na mo wipe abajade re ko ni dara. Ma se se ohunkohun ti yoo mu ki Olorun yago fun o.

Bakana ni o nsele pelu awon kan ti won n wonu oniruuru ese lo, awon miran nlo lati odo oko/aya kan si omiran, awon miran nrinrin ifekufe kiri, awon miran n lo lati ijo kan si omiran laironu, awon miran n lo lati odo enikan si omiran fun iranlowo ninu aisododo, Olorun ko dunnnu si igbe aye isote ati aikiyesara. Olorun je Olorun owu.

## II. IJIYA AHOLIBA (ESEK. 23:22-35)

Olorun pinnu lati je Juda niya. O so ete Re:

1. Awon alabaarinpo re (Babiloni, Kaldea, Assiria, ati bee bee lo) yoo dide si i fun ijiya, iparun ati mimu lo sinu igbekun.
2. A oo ja awon ohun-ini re gba lowo re.
3. A oo ja si ihoho ti yoo doju ko itiju ati egan.
4. Yoo je gbogbo irufe iya ti arabinrin re Ahola je.

Gbogbo ijiya yii yoo je nitori ese ati igbe aye aibikita re. Juda ati Jerusalem gbe Olorun ti, won lo ba awon orisa miiran, nitorinaa won ni lati doju ko abajade naa ni oun nikan. Bawo ni igbe aye re se ri? Se o ko wa ninu ibasepo ese ikoko ti Olorun ko dun si i? Se ki nse wipe o si n wa iranlowo losi awon orisun ti ki nse odo Olorun otito? Se o ko lowo ninu adalu esin nitori ife lati ri ojutu si awon ipenija aye? Ronu piwada loni ki o si tele Kristi ni ona ti o to ati pelu emi ti o to.

Oro owe Yoruba kan so pe, “Eni ti o wa niwaju ti o si subu sinu koto ko awon ti n bo leyin ni eko.” Aholiba ye ki o ko eko latara asise ati ijiya arabinrin re Ahola, ki o ma si rin ni ona kan naa. O se ni laanu wi pe ko se bee, o tun hu iwa ika ati ese ju arabinrin re lo. Oluwa ko dunu si i, o si se tan lati je e niya. Ranti, o ye ki o ko eko latara asise ati ijiya awon elomiiran ki o ma baa subu sinu koto kan naa. Je ologbon; gbe igbe aye ododo ti o dun mo Olorun.

**IBEERE**

1. Ta ni eko oni dojuko, Ahola ni tabi Aholiba?
2. Daruko awon orile-ede ti o se pansaga pelu re.
3. So awon ese marun ti o kopa ninu won.
4. So awon ijiya meta ti Olorun so pe yoo je.
5. Bawo ni enikan se le yera fun ijiya Olorun?

**NOVEMBER 22, 2026** **EKO 47**

# A KEDE IDAJO LORI AHOLA ATI AHOLIBA

***BIBELI KIKA:-*** *Esekieli 23: 36-49*

***ESE AKOSORI:-*** *"Alafia ko si fun awon enia buburu, li Oluwa wi." (Isaiah 48:22)*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| | Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|---|
| **MON** | 16/11/2026 | Se ilaja pelu omo na nisinyi | | Orin Dafidi 2:10-12 |
| **TUE** | 17/11/2026 | Sora fun awon nkan ewo | | Deu. 7: 25-26 |
| **WED** | 18/11/2026 | Ki a mase ri won larin yin | | Efesu 5: 3-7 |
| **THUR** | 19/11/2026 | Ko latara Akani | | Joshua 7:19-26 |
| **FRI** | 20/11/2026 | Ida fun ese | | Eksodu 32:25-28 |
| **SAT** | 21/11/2026 | Awon ise to je ewo | | Esekieli 23:36-44 |
| **SUN** | 22/11/2026 | Sora fun Idajo Olorun | | Esekieli 23:45-49 |

**ORO AKOSO**

Ko si ani-ani, Olorun ko ni inu didun si awon iwa irira ti awon eniyan ati orile-ede re ti o feran n se. Ninu awon eko ti o koja, Olorun soro nipa ikookan awon arabinrin wonyi ati iwa agbere won, ati iha ti O ko si iwa buburu yii, lotooto. Ninu eko oni, a ri Olorun nihin-in ti o n soro nipa awon oran awon arabinrin meji naa papo, ti o n tÍka si awon ese won ati ijiya ti o fe mu wa si ori won. AHOLA ti i se Israeli, ati Aholiba ti i se Juda, ti kuna, won si ti da ife ti olufe won atorunwa ni fun won, nipa bee, ko si ohun miiran ti o le se ju ki o kede Idajo Re lori won. Ma se foju kere ife onirele ati aanu Olorun, ma si se ka Ife Re si aile ra tabi ilora, O n ni suru pelu re ki o le ronu piwada ki o si yipada si ife re ati ife-inu re ki ojo ikeyin to de, ti yo mu ijiya re ti ko rorun lati gba sara wa sori re.

**EKO**

I. **IKEDE AWON IWA IRIRA TI AHOLA ATI AHOLIBAH (ES. 23: 36-44)**

Awon iwa irira wonyi ni a ti ka si gege bi ohun irira, ti o tumo si, ohun ti enikeji ko gbodo se tabi kopa ninu re. Ni oro miiran ewe, Ere ije Kristeni je eyi ti o soro ni taarata tabi ni ona ti o farasin, nipa awon ohun ti ko ye ki a ri pelu tabi ninu aye omo Olorun. Igbe aye Kristeni ye ki o je igbe aye Kristi ti o n tele awon oro gbolohun wonyi: "Awon miiran le se, emi ko le se", "Awon miiran le se, emi ko ni se", "Awon miiran le se, emi ko gbodo se", nigba ti o ba kan awon nkan ailola ninu irinajo wa ninu aye. Sayeewo awon iwe mimo wonyi ki o si se awon akiyesi ti o ye ati ti o mogbon wa: Deu. 7: 25-26; 12: 29-32; 17: 2-5; Efe. 5:3-7.

Nibayi, a o se idanimo awon iwa Irira naa nisale:

1. **Agbere/Pansaga** - Won tele awon olorun miiran lodi si itoni oko won ti o feran won.
2. **Ita eje sile** - Won ta eje alaise sile. Won pa awon omo won fun awon orisa bi eni pe won n pa ewure. Omo meloo ni iwo naa ti pa nipa iseyun, boya gege bi eni ti o ti segbeyawo tabi ti ko tii se? Ti o ba ti se eyi, owo re kun fun eje. O ni lati jewo eyi fun Olorun ki o si ronu piwada kuro ninu iwa yii, ki o ma se pada sinu iru eyi mo.
3. **Mimu awon omo won koja ninu ina** - Iwa buburu ati irira kan ti o je ajeji si ijosin Yahweh, Olorun majemu ti Israeli.
4. **Didoti ile mimo Olorun** - Won ba ile Olorun ati pepe re je pelu gbogbo iru ebo ati iwa ti ko ba ilana Olorun mu.
5. **Biba Ojo isinmi je** - Siso ojo Oluwa di ojo ti ko lowo, ti ko si wulo. Won fi owo egan ati aibowo mu Ojo Oluwa.
6. **Iwoso ati irisi ti n fa ifekufe ati idewo** - Won mura bi asewo, ni ona ti o n pe awon pansaga okunrin. Iran ti wa yi je iran iwokuwo ati oniruru irisi - wiwo aso ti o lemo ara pekípekí tabi fun ju bi o ti se ye lo, aso ti o nfi ihoho han, aso penpe iwolowe obinrin, pata idokunrin, aso iwosun obinrin, ati bee bee lo, ni won nwo jade sita ati lo sode. Ni akoko ero ayelujara yii, ofe ni ihoho lode, ihoho lori ate laisanwo - opo a mura tan won a si fi apakan awon ibi ipamo ara won han, nigbati awon miran ko ti le ni wo nkankan rara sugbon ti won yo wa ni ihoho bi a se bi won. Awon ise ati iwa wonyi je irira si Olorun.

Awon omo Israeli se gbogbo nnkan wonyi lati da bi awon orile-ede alaiwabi Olorun ti Olorun parun fun won ti won si gba ile won. Sora ki o ma se fe lati da bi aye.

## II. IKEDE IJIYA LORI AHOLA ATI AHOLIBA (ES. 23: 45-49)

Juda ati Israeli yoo gba idajo bi o ti to ati bi o ti ye. Won ti mu ibinu Olorun wa, won yoo si doju ko ijiya gege bi ije olododo Re se pe fun.

Wonyi ni awon ohun/ona ti a o fi je won niya je:

1. **Ipaya ati ifipajerun** - Won yoo je ki won jiya ipaya atorunwa. Awon olododo ni Bibeli so pe, won ni igboya bi kinníún, ki i se elese, ipa elese ni aisi isinmi, iberu ati aini alaafia (Owe 28: 1; Isa. 48: 22; 57: 21). Won yoo ja won lole ohun gbogbo ti o dara. Won yoo ja won lole alaafia. E je ki awon akeko jirooro awon ese Iwe Mimo wonyi ni ibamu pelu afojusun eko yi: Owe 13: 21; Oniwasu 2: 26. Eese ti o fi yan lati je elese? Eese ti o ko ronu lori ona re loni ki o si gbe iyoku aye re fun Kristi?
2. **Siso lokuta ati ipakupa** - Won yoo so won lokuta, won yoo si pa awon omo won pelu ida. Bawo ni ijiya pelu siso lokuta se rorun to? Tabi ida? Awon akeko ni lati dahun awon ibeere wonyi: Lati inu Bibeli, so apeere meji ti awon ti won so lokuta ti won si ku, ati ohun ti won se. Tun so oruko eniyan meji ti won pa pelu ida ati ese won. Sa fun idajo Olorun ki o si sa sodo Kristi nisinsinyii.
3. **Won yoo sun awon ile won** - ese n so eniyan di alainile ni ile ayeraye, sora.
4. **Opin yoo de fun agbere ati pansaga** - Nípase ijiya, awon miiran yoo ko lati ma se lo ni ona awon elese, ati pe eyi yoo mu opin wa si agbere esin ati ti emi laarin awon eniyan Israeli.
5. **Ijiya fun pansaga ati iborisa** - Awon atunbotan wa fun gbogbo ipinnu ati ise, Juda ati Israeli yoo ni lati san idiyele nla fun kikopa ninu iborisa. Iwo na yoo san idiyele fun awon ese re, ko si ona abayo ayafi bi o ba ronu piwada ki o si yan Kristi, ododo ati iwa mimo loni.

Bi o tile je pe Olorun yan won ti O si feran won, Israeli se asilo irufe anfani nla yii, nitorina, won yoo si doju ko abajade iwa omugo won ni didara po mo awon olufe ajeji, ibagbepo ajeji, igbe aye ati ijosin ajeji. Sora, Olorun ti o ma n saanu tun je Olorun idajo.

**IBEERE**

1. Oruko eyokan wo ni won lo fun awon iwa irira gege bi eko naa?
2. Gege bi eko naa, kini gbolohun Kristeni ye ki o je?
3. Daruko awon iwa irira marun.
4. Kinni awon ijiya merin ti won yoo je fun awon agbere won?
5. Ka ese akosori fun eko oni ki o si waasu lori re fun iseju meta.

**NOVEMBER 29, 2026** **EKO 48**

# IBERE IDOTI/IDOJUKO JERUSALEMU

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 24:1-14*

***ESE AKOSORI:-*** *“Omo Enia, Iwo ko oruko ojo, na,ani ojo kanna yi:oba Babilori doju ko Jerusalemu li ojo kanna yi : Esekeli 24:2*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 23/11/2026 | Ye ona re wo 1 | Haggai 1:1-5 |
| Ojo Isegun | 24/11/2026 | Ye ona re wo 2 | Ekun Jer. 3:39-41 |
| Ojoru | 25/11/2026 | Ma sora 1 | Eksodus 23:32-33 |
| Ojobo | 26/11/2026 | Ma sora 2 | Eksodus 34:10-12 |
| Ojo Eti | 27/11/2026 | Kiyesi oro Olorun 1 | Johannu 8:42-47 |
| Ojo Abameta | 28/11/2026 | Kiyesi oro Olorun 2 | Orin Dafidi 1:1-3 |
| Ojo Aiku | 29/11/2026 | Olorun si tun soro | 1 Samueli 3:8-11 |

**ORO AKOSO**

Ni odun kesan, Osu kewa ,li ojo kewa osu naa: gege bi Olorun ti pase, Esekiel fi pelepele si akosile isotele re. Eyi je ojo iyipada orile ede ati igbesi aye, ti won yio maa ranti fun ojo pipe. Akawe irufe ojo yi ni, ojo ikookanla ni osu kesan odun Eegba ole okan, ti o ni se pelu isele ikolu tabi gbogunti orile ede Amerika.Oje ojo manigbagbe fun awon olugbe orile ede Amerika ati gbogbo agbaye.

**EKO**

**I. ORO OLORUN (ESE 1 – 2)**

Oro Olorun to Woli Esekieli wa ni ojo keedogun osu kini odun 588 BC{saaju ibi Jesu} (January 15, 588 B.C,) ojo ti idoti bere ni orilede Jerusalemu, ojo yii le gan ni, ti a fi so nipa re ninu iwe awon oba ikeji 25:1-3 bakan na ninu Jeremiah 52:4-6 ni gba odun ikonileru, awon Ju maa nse odun merin ni iranti bi a se wo Jerusalemu lule. (Sekariah 7,8:18-23) Won a maa se iranti igba ti idoti naa sele (osu mewa) ati, wiwo odi na pale (osu kerin) ati igba ti inajo tempili ati ti ase ku pa Gedaliah bale (Ninu Ose keje Jer 41: 1 – 2) Ojo won yii ni akosile ninu Awon oba keji 25:1, Jer. 39; ati 52:4. Bakan naa ni a tun mo ojo naa ninu Sekariah 8:19 pe ojo yii je, ojo buburu fun awon ti won wa ni oko eru, ojo okan ninu ojo iranti awon ojo ti o lewu, ojo ti ilu mimo subu. Ojo ti oba Babiloni bere igbogunti Jerusalemu:

Ojo yi se pataki nitori pe oje ojo ti ileri ti Olorun se fun ojo pipe, bere si wa si imuse ti igbogunti ti o gbeyin,  ojo ti ikogunja  ni, ti a si pa Jerusalemu run . Ojo ekun.

**II.  ILE OLOTE (ESE 3)**

Olorun pe awon Judah ni ''ile olote'' kii se wipe won ko ofin re ni kan ati riru majemu re, sugbon nitori Sedekiah ti ba adehun re pelu Babiloni je,  eyi si fa aidunu Nebukadnessari. Awon ofin Olorun melo ni o ti ru, ni igbati enikan ba ru ofin eleda re, irufe eni be ti bo si owo ota re. Sugbon alanu ni Olorun, pada sodo Re, yoo dari gbogbo ese re jin o, yoo si mu o pada sodo ara Re.

**III.  OWE IKOKO IDANA (ESE 4 – 5)**

Owe ikoko idana, nibi yii, woli lo aworan yii gegebi afiwe awon adari ni Jerusalemu. Beeni Olorun yoo ke ''ibi ti oni eran'' sinu ikoko (Jerusalemu) yoo si bo eran ati egungun (Igbogun Babiloni).Ko ni ''se'' ara eran yoo je won ni! (Esekieli 10) Yoo si tun awon panti jade, yoo si jo ikoko na fun rare: Jerusalemu je ilu buburu, ti okun fun ese gege bi ikoko ti o dotin  ti a fi iwa ibaje we ni ipele. O ti ta eje alaise sile ati wipe ko tile bo eje naa. O gbodo mo wipe Olorun ri gbogbo awon iwa buburu re, ijiya yio si de lai pe.

**IV. IKEDE IDAJO NAA -  ESE  9-14**

Olorun kede egbe si ori won nitori ese won ti won lero wipe Olorun ko ri. Ni oro miran ewe, gege bi iranse Olorun, osise ati omo ijo, ninu ijo Olorun ohun gbogbo ti ase tabi ti a nse nipa sise lodi si ofin Olorun ati si awon alase nitori ipo wa tabi oro wa, ti aro wipe akose bawi. Ranti pe. Olorun le ba enikeni wi ni igba yowu ati akoko ti oba wu u. (Gen 4:10 Lef. 17:13, Deut. 12:16, 24: 15:23).

Ninu aye ti angbe ni ode oni, okun fun aigbagbo ati aroso nitori gege bi awon Ju ti igba Esekieli, won ko gba ase oro Olorun. Awon eniyan si tun gbagbo pe , owo ni osunwon ohun ti enikan je ati aseyori, ati wipe erongba wiwa laye ni lati se faaji ati lati se ohun ti won ba fe. Enikan le gba ohun yowu gbo nipa Olorun, ati awon elomiran, pelu ireti wipe ohun gbogbo yio dara nitori pe ko si ijiya. Sugbon ni ojo kan, Olorun yoo tu gbogbo asiri iwa omugo ati ero odi re, beeni gbogbo aye ni yio mo wipe o ti ju, atubotan wa fun ohun ti a gbagbo ati bi a se nwuwa.

**AWON IBEERE**

1. Nje odara ki eniyan je olote?
2. Kini owe ikokoo idana tumosi?
3. Kini idi ti Olorun fi pe Judani ni ile olote?
4. Nje o lero  wipe Olorun le gboju agan si awon eniyan re?
5. Kini awon ijiya ti Olorun kede lodi si won?

**DECEMBER 6, 2026 EKO 49**

# IKU IYAWO ESEKIELI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 24:15-27*

***ESE AKOSORI:-*** *"Omo enia, kiyesi i, momu ife oju rekuro lodo re, nipa lilu kan: sugbon iwo ko gbodo gbawe, beni iwe ko gbodo sokun, beni omije re ko gbodo sansile"  - Esekieli 24:16.*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kik |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 30/11/2026 | Dandan ni iku 1 | Orin Daf. 22:14-20 |

| | | | |
|---|---|---|---|
| Ojo Isegun | 1/12/2026 | Dandan ni iku 2 | Oniwaasu 7:1-3 |
| Ojoru | 2/12/2026 | Ni bo lo nlo leyin aye ese yi? | Luku 23:42-43 |
| Ojobo | 3/12/2026 | Ni bo lo ti fe lo ayeraye re? 1 | Ifihan 20:11-12 |
| Ojo Eti | 4/12/2026 | Ni bo lo ti fe lo ayeraye re? 2 | Ifihan 20:13-14 |
| Ojo Abameta | 5/12/2026 | Mo daju wipe iwo yio lo lojo kan | Oniwaasu 3:1-3 |
| Ojo Aiku | 6/12/2026 | Asan ni aye yi je. | Oniwaasu 1 :1-11 |

**ORO AKOSO**

Nje a le so wipe Olorun ko se daradara nigba miran? Ni odun die ti mo ti lo ninu ise iranse gege bi iranse Olorun, ni gba ti enikan ba padanu okan ninu ara re, awon eniyan sa ba maa nbere wipe kinni idi ti won fi ku, ati wipe kini iditi Olorun se se eleyii? Won atun ma bere wipe kilo de ti Olorun se mu awon ti won fe lo bi o ti je pe eni won ti oku yii tile je agbalagba, ti won ku lai ni ijamba tabi ohun miran, opo igba ni o ma nya wa lenu tabi bere wipe kini ojuse tabi kini Olorun nwo nigbati a ba padanu eni wa tabi ololufe wa kan. O je ohun ti osoro nigbati eniti o su mo wa tabi ore wa ba ku. A ki i fe ki won ku, bakan naa, ni a ma ro wipe ko dara. A ma nro wipe ta ni o le se ti eniyen ko ni ku bikose Olorun. Sugbon, se ebi Olorun ni bi? Isele kayefi ti a ka ni ipari iwe Esekieli 24 fi dawa loju gbangba pe ki abere lowo Olorun pe se o jebi ohun ti o sele ti o dabi ibi ti a ko reti tabi se pataki.

**I. ISOTELE NIPA IKU IYAWO ESEKIELI - ESE 15-16a**

Bibeli ko so fun wa ohun ti o fa iku iyawo re, sugbon o han gbangba wipe, iku re je gege bi eto Olorun - gege bi iku enikookan ti ri (kaa Orin Dafidi 31:15, 139:16 Oniwasu 3:2). Eyi ni akosile Esekieli nipa isele yi, bere pelu ikede Olorun fun Esekieli wipe iyawo re yio ku :*Oro Oluwa si to mi wa, wipe, Omo eniyan, kiye si i, mo mu ife oju re kuro lodo re, nipa lilu kan,*ese 16 a . A gbodo mo gege bi Kristiani, Olorrun le e fi ibi ti o nbo han laiyi danu. O se eyi lati pese okan wa sile fun un, ki o ma ba bawa lojiji. A o dan igbagbo re wo, gbaradi fun un.

**II. IKILO SAJU IKU IYAWO ESEKIELI ESE 16b-17**

A ki Esekieli ni lo saju iku airotele iyawo ati ololufe re, Olorun yo mu eyin loju re lo. A ma nbere ki lode ti irufe eleyii yoo se sele, sugbon Olorun tesiwaju lati ki Esekieli nilo eyi tun mu ki ibere posi:Sugbon o ko gbodo sokun tabi ki omije jade loju re. Ki o kan ni irora okan; ma se kedun fun oku. *Di lawani ati salubata re le; ma se bo irun enu ati irugbon re tabi je ounje ti eniti o sofo maa nje*. Olorun je Kabio o si ninu ise re. Oye gbogbo re ko lee ye wa. Nigba ti Olorun ba gba ohun ti o ko ni oye re lati sele si o, iwo sa ti gba bee pelu igbagboo mase so oro odi si Olorun. O ti dara fun okan re.

**III. IDIYELE TI O GBODO DI SI SAN NINU ISE IRANSE**

Esekieli san idiyele ti o ga ju gbogbo awon woli lo.Lati le je ise iranse, Esekieli nilati ri iku ojiji iyawo re ati wipe ko gbodo fi ami ofo han. Olorun so fun wipe o ma ku, ko si gbodo se bi awon Juu ti ma nse ni igba ti won ba padanu ololufe won, sugbon a gba laye lati kerora okan ni pele sugbon ko gbodo sokun beeni omije ko gbogdo bo sile ni oju re. Ti a ba le bere lowo awon baba wa ninu Oluwa, awon idiyele ti enikokan won ti san tabi san lowolowo pelu ifi ara eni rubo ti won ti se ninu ise iranse, a mo wipe ise iranse ko rorun rara. Bakan naa, opolopo Kristiani ni o ti ni idojuko ti o po. Ko si eni ti o wa si aye ti ko fi ara pa. Ki Olorun je itunu wa. Ohun ti o sele si Esekieli je apeere ibi ti o nbo wa sele si Israeli alaigboran. (kaa, ese 25-27). Kiko lati se ife Olorun, yio mu ijiya wa. Ronupiwada!

**AWON IBEERE**

1. Nje Olorun se dada pelu iku iyawo Esekieli?
2. Iru idiyele wo ni o ti san gegebi

Kiristian? Pin iriri re pelu wa.
3. Nje o ro wipe Olorun jare iku iyawo Esekiel?
4. Bawo lo se ye ki a se si isele ibi ti oye re ko ye wa?
5. Kinni ofo(iku iyawo) Esekieli n se apeere?

**DECEMBER 13, 2026 EKO 50**

# IDAJO AWON ORILE-EDE TI O JE IBATAN ISRAELI

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 25: 1-14*

***ESE AKOSORI:-*** *"Si wi fun awon ara Ammoni pe, Egbo oro Oluwa Olorun: Bayi ni Oluwa Olorun wi; Nitori ti lwo wipe, Aha, si ibi mimo mi, nigbati odi ailowo, ati si ile Israeli, nigbati odi ahoro; ati si ile Juda, nigbati nwon lo ni igbekun". Esekieli 25:3.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 7/12/2026 | Gbo Ohun ti emi nso 1 | Genesisi 26:1-8 |
| Ojo Isegun | 8/12/2026 | Gbo Ohun ti emi nso 2 | Genesisi 26:9-14 |
| Ojoru | 9/12/2026 | Wa Oluwa ki o to pe 1 | Marku 10:29-30 |
| Ojobo | 10/12/2026 | Wa Oluwa ki o to pe 2 | Matteu 6:33-34 |
| Ojo Eti | 11/12/2026 | Mase je olote omo 1 | Eksodu 10:27-29 |
| Ojo Abameta | 12/12/2026 | Mase je olote omo 2 | Eksodu 19:11-14 |
| Ojo Aiku | 13/12/2026 | Kiyesara | Genesisi 31:24-29 |

**ORO AKOSO**

Awon ara Ammoni,Moabu ati Edomu je ibatan tabi eje awon Ju.Awon Ammoni ati Moabu je ara kan na pelu Israeli lati ipa Loti omo arakunrin Abrahamu. Ammoni ati Moabu je awon omo ti awon omo obinrin Loti bi fun un(Gen 19:29-38) Edomu je oruko miran fun ibeji Jakobu ti a moo si Esau (Gen 25: 30; Edomu tun mosi ''pupa'') Jakobu si je Baba awon eya mejilati Israeli. A le lero wipe awon orile-ede wonyii ti won tan mo ara won yoo ran ara won lowo, sugbon awon orile-ede meta yi ni ikorira olojo pipe si Israeli ti won si je ki ija na ma tesiwaju.

**EKO**

**I. IDAJO FUN AMMONI (ESE 1-7)**

Ni igba ti awon omo Isreali nkoja lo si ile ileri,won segun opo orile-ede, Olorun pa se fun won ki won ma se ba awon ara Ammoni ja, nitori ohun ti fun won ni ile naa (Deut 2:19) Won je oni jagidijagan eniyan (Jer-40:4; 41:5-7), Saulu ati Dafidi ba won ja ti won si bori won (I Sam. 11:1; I kronika 19: 1, 20:8) awon ara Ammoni ti parapo mo awon ara Moabu lati ba awon Juda jagun, sugbon gbogbo won ba ijakule pade, nitori awon Juda bori won (II kronika 20) Olorun ti kede pe oun yoo fi awon Ammoni le awon okunrin ti o wa ni iha ila oorun lowo (Esekieli 25:4) ti o tumo si pe awon omo ogun Babiloni. Nigbati Nebukadnessari lo si oju ogun, o de arin ona meji ninu eyi ti okan lo si Jerusalemu ti ekeji si lo si Rabba ti nse olu ile Ammori (Esekeli 21:18-24) nibe ni o ti beere ona lowo awon alafose, Olorun si ri wipe o ti gba ona Jerusalemu lo. Okan awon ara Ammoni bale ti won si kun fun ayo, nigbati won mo wipe Jerusalem ti di ohun ti a kolu, ti a si ba Tempili re je, sugbon igbati won na ti de bayi. Olorun yoo pa gbogbo orile-ede Ammoni run patapata kuro ni ile aye.

**II. IDAJO FUN MOABU (ESE 8-11)**

Oba Balaki ti ilu Moabu ni o be woli Balamu lowe lati wa fi awon omo Israeli re nigbati won wa ni Moabu(Numeri 22:24) Balaamu yi naa ni o lo ko awon ara Moabu lati mu awon omo Israeli dese si Olorun won (Numeri 25:1-9; 31:16). Ese awon ara Moabu je ohun abuku si awon omo Israeli, ni kiko lati ri awon Ju gege bi eniyan ooto ni owo Olorun. Si awon ara moabu, ohun ti won soro le lori ni wipe, isubu Jerusalemu fi han pe won je eniyan lasan won ko yato si awon eya yooku, ti won ba je eniyan ooto, bawo ni won yoo se ni iriri isubu ati ijakule nla yii ? Huh! Nje o le duro die ki o si ronu jinle laarin yii, kini awon ohun ti o ti so ni igbati o ba ri ti enikan ti o subu, papa julo ni igbati iranse Olorun kan ba subu, kini on so? Ati wipe iru awon oro wo lo ma njade lenu re si isubu won? Mo bee o jowo sora gidigidi fun awon ohun ti o ma so nitori pe ni igbati Olorun npe e ati wipe ni igba ti Olorun yoo mu pada bo si po, o ko ni si nibe. (Numeri 23:8-10). Awon ara Moabu je oni gberaga eniyan nitoripe won ro wipe ilu won ko ni se wo (Isaiah 36:6) Oke ni Moabu wa, pelu okun ni ila oorun ati aginju ni iwo oorun. Sugbon Olorun so fun won wipe ohun yoo mu awon ota fi ogunja won, ibi ti won ro wipe kose wo yoo di ibi ti a o fi ogun ja (Esekieli 25:9) Bi o ti je ibi abo ti won ro wipe ko le se wo, awon ara Assiria ko gun ja won ti won si subu patapata, ti ako si ranti Moabu gege bi okan lara awon orile-ede mo.

**AWON IBEERE**

1. Awon Oba meji wo ni o segun Ammoni?
2. Nje o dara lati kegan eniti o ba subu?
3. Bawo ni awon Moabu se mu awon omo Israeli dese si Olorun?
4. Kinni ese awon ara Moabu?

**DECEMBER 20, 2026 EKO 51**

# IROYIN AYO NINU PAPA ITOJU ERANKO

***BIBELI KIKA:-*** *LUKU 2:8-20*

***ESE AKOSORI:-*** *"Nitori a bi Olugbala fun nyin loni ni ilu Dafidi, ti ise Kristi Oluwa.''. (Luku 2:11)*

**BIBELI KIKA OJOOJUMO**

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 14123/2026 | Iru Omo Olorun | Genesisi 3:12-15 |
| Ojo Isegun | 15/12/2026 | Ami Olorun | Isaiah 7:10-14 |
| Ojoru | 16/12/2026 | Alakoso Lori Israeli | Mika 5:1-5 |
| Ojobo | 17/12/2026 | Omo Olorun | Hosea 11:1-4, Matt. 2:14-15 |
| Ojo Eti | 18/12/2026 | Eka Ododo | Jeremiah 23:1-6 |
| Ojo Abameta | 19/12/2026 | Ogo ni Fun Olorun L'oke orun | Luku 2:8-14 |
| Ojo Aiku | 20/12/2026 | Omo owo naa ni ibuje eran | Luku 2:15-20 |

**ORO AKOSO**

Ko ye ki ibi Jesu se ajeji si awon Ju nitori, awon asotele ti o ti wa nipa re ninu majemu lailai. Opolopo awon woli majemu lailai ti so asotele nipa ibi Jesu Kristi, awon ti o se pataki ninu won ni Isaiah ati Mika. Isaiah sotele wipe wundia kan yio loyun, yio si bi omokunrin kan. (Isaiah 7:14, 9:6) Mika sotele wipe a o bi Messiah ni Bethlehemu. (Mika 5:2) Awon asotele wonyi, wa si imuse ninu majemu titun nipa ibi Jesu ni Bethlehemu ati ibi re nipase wundia ti a mo si Maria. Awon asotele Olorun nipa aye re lee fale, sugbon, yio wa si imuse ti o ba duro ninu Jesu Kristi.

**I. AWON OLUSOAGUTAN ATI ANGELI NINU PAPA ITOJU ERANKO - ESE 8-14**

**(a) Awon Olusoagutan naa-ese 8**

Ise osin eranko je gbajugbaja ni ile Israeli lati akoko awon Baba nla won. Eko wa ti oni se afihan awon olusoagutan ninu papa ti won ti nsin awon eranko won, won nso awon owo eranko won ni oru nitori awon eranko buburu ati awon olosa. Awa naa ni olusoagutan ti wa, tii nse Jesu Kristi, eniti o nso eso lori wa t'osan t'oru. (Orin Dafidi 23, 121:4-8).

**(b) Angeli Oluwa naa - ese 9-11**

Iriri ajeji tabi alejo kan farahan ni papa ti won ti sin eranko, eyiti o deruba awon olusoagutan. Bibeli wipe, angeli Oluwa kan si yo si won,ogo Oluwa si ran yi won ka, beeni eru si ba won gidigidi. Angeli mu won lokan le, o si pin iroyin ayo nla nipa ibi Olugbala lati idile Dafidi pelu won. E jeki a maa reti iroyin ayo ninu ile wa ati awon ibi ise wa bi odun yi se nwa si ipari.

**(d) Awon ogun orun lopolopo - ese 12-14**

O dabi angeli kan ti a so nipa re nigba isaaju ni o wa ni aworan eniyan lati gbebi fun Maria wundia. Leyin eyi, o kede ibi Jesu Kristi pelu awon ami fun awon olusoagutan (ese 12). Nigba t'oya, opolopo ogun orun darapo mo o, lati yin ati lati fi ogo fun Olorun ni oke orun (ese 13-14) ki gbogbo won to pada lo si orun(ese 15). Ibi Jesu Kristi mu ayo wa ba aye ati orun, isele kan yio sele ninu idile re ni odun yi, ti yio mi orun ati aye pelu pariwo ayo. Nje o setan fun un?

**II. AWON OLUSOAGUTAN KEDE IROYIN AYO NAA. -ESE 15-20**

**(a) Awon Olusoagutan gbagbo - ese15-16**

Lai jafara rara, won gba oro naa gbo, beeni won si lo ibi naa gan an ti a bi Jesu si. Won ri Josefu ati Maria ati omo owo naa ti o dubule ni ibuje eran. Ma se iyemeji si oro Olorun mo, gba a gbo! Fun ire ara re ni.

**(b) Awon Olusoagutan pin iriri won - ese 17-18**

Won pin iriri won pelu awon obi Jesu Kristi ati awon eniyan ti o wa nibe, beeni enu si ya won. Iwo ni okan lati so eri nla ti yio ya awon eniyan lenu bi odun yi se nwa si opin.

**(d) Igbese rere Maria.-ese 19**

Maria pa gbogbo awon iroyin naa mo sinu okan re. Awon obi gbodo ko bi a se npa asiri asotele nipa awon omo won mo nitori awon eniyan buburu. Ma se so asiri aye re mo fun awon a ba ogo je.

**(e) Igbese rere awon Olusoagutan - ese 20**

Won pada, won bere si ni nfi ogo fun Olorun fun iriri ti won ri. A gbodo ko bi a se nfi ogo ati iyin fun Olorun fun ohun ti O ti fun wa ni anfani lati ni iriri re ninu aye wa, paapa julo, igbala ati aabo wa.

**AWON IBEERE**

1. Daruko awon woli meji ninu majemu lailai ti won sotele nipa ibi Jesu Kristi.
2. Iru iroyin wo ni angeli naa pin pelu awon Olusoagutan?
3. Kini o sele ni paapa ti won ti nsin eranko?
4. Kinni awon igbese rere ti awon Olusoagutan gbe?
5. Eko wo ni ale e ko lara Maria?

**DECEMBER 27, 2026** **EKO 52**

# IDAJO ORILE-EDE TI O JE IBATAN ATI EYI TI O WA NI AGBEGBE

***BIBELI KIKA:-*** *ESEKIELI 25: 12-17*

***ESE AKOSORI:-*** *"Je ki iwa-buburu awon enia buburu ki o de opin: sugbon mu olotito duro; nitori ti Olorun olododo li o ndan aiya ati inu wo" - Orin Dafidi 7:9.*

## BIBELI KIKA OJOOJUMO

| Ojo | Deeti | Akori | Bibeli Kika |
|---|---|---|---|
| Ojo Aje | 21/12/2026 | Iru Eniyan wo lo je? 1 | Orin Dafidi 1:1-3 |
| Ojo Isegun | 22/12/2026 | Iru Eniyan wo lo je? 2 | Orin Dafidi 1:4-6 |
| Ojoru | 23/12/2026 | Eni buburu kan ki yio lo la jiya 1 | Orin Dafidi 3:1-8 |
| Ojobo | 24/12/2026 | Eni buburu kan ki yio lo la jiya 2 | Orin Dafidi 7:6-9 |
| Ojo Eti | 25/12/2026 | Ere nbe fun ohun gbogbo 1 | Ifihan 22:11-12 |
| Ojo Abameta | 26/12/2026 | Ere nbe fun ohun gbogbo 2 | Danieli 6:21-26 |
| Ojo Aiku | 27/12/2026 | Iru ere wo ni yio je tire? | Matteu 25:15-28 |

## ORO AKOSO

Lekansi akori oro ti anpe ni igberaga, ikorira, ati igbesan wa saaju ese ti ole ru awon orile-ede soke ni aye ode oni pelu. O je ohun ti o rorun fun oni jagidijagan eniyan lati maa se bi eni ti oni ife orile -ede re, ikorira gege bi igbona okan fun orile-ede, ati igbesan gege bii idajo ododo. Nigbati a ti jiroro ijeniya ese awon orile-ede ti o je ibatan fun awon omo Isreali tan, Olorun wa doju ko awon orilede ti o wa ni agbegbe won.

## EKO

### I. IDAJO FUN AWON ARA EDOMU (ESE 12-14)

Ikorira awon ara Edomu si awon Ju ti bere lati igbati Esau ti fi iwa omugo ta ojo ibi re fun arakunrin re, Jakobu, ati igba ti iya won tun fi ogbon ewe gba isure lati odo baba won fun ojulowo omo re, Jakobu (Gen. 25:29-34; 27) Jakobu sa kuro nile lo si Harani lati lo gbe pelu ibatan mama re ati kuro lowo ibinu egbon re. Awon omo Esau pada wa di alagbara ijoye (Gen 36). Sugbon, awon omo Jakobu je oludasile eya Israeli mejila, awon eniyan ti Olorun yan lati mu gbogbo ero ngba re ni ile aye wa si imuse. Olorun yoo bi Edomu subu nitori awon ona ti won gba lati korira awon Ju, (Obad.10-14) Ni gbati a ko gun ja Jerusalemu, awon ara Edomu bere sin yin awon ara Babiloni (Orin dafidi 137:7) ti won kosi ran awon ti won saala lowo, kaka be won ran awon ara Babiloni lowo lati mu awon ti won salo pada, won si yo si isele ibi ati laluri nla ti o ba awon Juu. Pelu awon ara Babiloni ni won ko opolopo leru ti won si ja awon ibatan won ni l'ole. Ese si iran eniyan je ese si Olorun, nitoripe ada eniyan ni aworan Olorun, nitorina sora fun awon ohun ti onse si enikeji re, ki ohun ti osele si orile-ede yii ma ba sele si iwo naa( ka Ekun Jer. 4:21-22). Ise ti Olorun ran si awon ara Edomu ran wa leti pe ija ninu idile je ohun ti oni agbara gan ni ti o si buru jai. Awon ara Edomu korira awon Juu lati iran de iran won. Onkowe ti a npe oruko re ni T. Washington so wipe,"Mase je ki enikan mu o wa le lati korira re'' Ma se gbagbe ohun ti eleda re so ninu. Mattiu 5:44.

### II. IDAJO AWON ARA FILISTINI (ESE 15-17)

Lehin ti awon omo Israeli de ile Kenani ti won si gba ile naa, awon aladugbo won ti nse awon ara filistini wa di ota awon omo Israeli ti o le gan ni. Ninu awon onidajo Samgari (Onidajo 3:31) ati Samsoni (Onidajo 14:16-20) ba won ja. Bakan naa ni Samueli ati Saulu ba won ja pelu. Sugbon Dafidi ni o pa da wa bori awon fililstini, won si wa labe isakoso titi ise ijoba Solomoni (II Samueli 5:17; 21:15-22; 23:9-17).

Nigbati awon Israeli pin si meji, awon Filistini di ominira, won si je onisowo ati oloko owo pelu awon ara Foenikia. Awon ara filistini fi ikorira awon Juu sokan won fun igba pipe ti won si nwa gbogbo ona lati gbogun ti won. Ki se Esekieli ni o je woli akoko ti o so asotele idajo Olorun lori awon ara Filistini (ka Jer.47; Amosi 1:6-8 Sefiniah 2:4-7) Awon ara Filistini darapo mo awon ara Egipti ni igbiyanju lati tako Nebukadnessari, Babilioni si po ju won lo tabi l'agbara ju won lo, a bori awon ara Filistini bi awon orile-ede to ku ti a si le won jade kuro lo ni ile won. (Jer 25:15-32;47) O ye ki a mo irufe awon eniyan ti a nba rin, ki a ma ba bo si inu ewu.

**AWON IBEERE**

1. Kini ese awon ara Filistini?
2. Awon melo ni won ti doju ija ko Filistini ni igba isaaju? Daruko won?
3. Tani o pada wa bori won?
4. Kini ibasepo ti o wa laarin Edomu ati Israeli?
5. Eko wo ni a lee ri lo nipa ibasepo ti o wa laarin Edomu ati Israeli?